# Ilana Muhammad – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi awọn ijọsin rẹ ati awọn ibaṣepọ rẹ ati awọn iwa rẹ

Ẹniti o ṣe e ni ṣoki ni
Dokita Ahmad ọmọ Uthmaan Al'maziid

Pẹlu orukọ Ọlọhun Ọba Ajọkẹ aye Aṣakẹ ọrun

Ọpẹ ni fun Ọlọhun, ikẹ ati ọla ki o maa bẹ lori ojiṣẹ Ọlọhun ati awọn ara ile rẹ ati awọn saabe rẹ Lẹyin naa Dajudaju ninu eyiti o tobi ju ninu awọn idẹra Ọlọhun lewa lori ni idẹra Islaam Toripe oun ni ẹsin abinibi ati ẹsin ti o wa ni iwọntuwọnsi Ẹsin ti o kun fọfọ ti o si pe Ẹsin imọ ati awọn iwa Ẹsin ti o ba gbogbo igba ati aaye mu Ẹsin irọrun ati ikẹ Ẹsin ti o jẹ wipe inu rẹ ọna abayọ si gbogbo wahala wa Iyẹn lo fi nmu wa ni bukaata si ṣiṣe alaya awọn ẹsa ẹsin yi ati awọn daada rẹ fun gbogbo agbaye, pataki julọ ni asiko ti a wa yi Ki aworan ododo ti o mọ kanga ti nbẹ fun ẹsin Islaam le baa han si wọn Atipe dajudaju ilana Muhammad – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – ni imulo iṣẹ ṣiṣe fun ẹsin yi Atipe niti paapa o ti sarajọ sinu ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – gbogbo awọn ẹsa yẹn eleyi ti o sọ ẹsin Islaam di ẹsin ti o rọrun lati wọ ati lati mulo; Latari wipe o ko gbogbo agbegbe iṣẹmi ti o jẹ ti ijọsin ati iṣe ati iwa sinu, ti o nii ṣe pẹlu ọrọ alumọọni ati ẹmi. Atipe o nbẹ ninu tira yi eleyi ti mo mu u jade lati inu tira (Zaadul Ma'aad fi Ad'yi khairil Ibaad, ti Imaam Ibnul Qoyyim) – eleyi ti o wa ninu awọn tira ti o lọla ju ti wọn kọ nipa ilana Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – ohun ti o sunmọ ilana rẹ ni awọn agbegbe iṣẹmi aye rẹ ki a le ba kọṣe rẹ ki a si le rin lori ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a

A nbeere lọwọ Ọlọhun ẹmi imọkanga ati itẹwọgba, atipe ki O fi alubarika si inu tira yi

Dokita Ahmad ọmọ Uthmaan Al'maziid
dralmazyad@hotmail.com

# Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi imọra ati bibiya bukaata

Ilana rẹ nibi bibiya bukaata: O jẹ ẹniti maa nsọ ti o ba ti wọ ile ẹgbin pe: Allaahummọ inni ahuudhu bika minal khubuthi wal khabaaithi (Iwọ Ọlọhun mo fi O wa iṣọ kuro lọdọ awọn akọ alujannu ati awọn abo wọn) Ti o ba si jade yio sọ pe: Guf'roonak (mo wa aforijin Rẹ) O si pọ lẹniti maa nbẹrẹ nigbati o ba fẹ tọ O jẹ ẹniti maa nfi omi ṣe imọra nigba mii, ti o si maa nmọra pẹlu awọn okuta nigba mii, a si maa lo mejeeji papọ nigba mii O jẹ ẹniti maa nmọra pẹlu osi rẹ O jẹ ẹniti ti o ṣe wipe ti o ba fi omi mọra yio fi ọwọ rẹ lu ilẹ lẹyin rẹ O si jẹ ẹniti o ṣe wipe ti o ba lọ gbọ bukaata ni irin-ajo rẹ, yio jina si awọn saabe rẹ ti wọn o nii ri i O jẹ ẹniti maa ndi gaga pẹlu aaye ti o ga nigba mii, a si maa lo idipọ igi ọpẹ nigba mii, a si tun maa lo awọn igi ti o ba wa laaye naa nigba mii. O si jẹ ẹniti maa nwa aaye ti o ba rọ lati gbọ bukaata rẹ O si jẹ ẹniti o ṣe wipe ti o ba joko lati gbọ bukaata rẹ ko ni ka aṣọ rẹ soke titi ti yio fi sunmọ ilẹ O si jẹ ẹniti o ṣe wipe ti ẹnikẹni ba salamọ si i ti o si ntọ lọwọ ko ni da a lohun

# Ilana rẹ nibi aluwala ṣiṣe:

O jẹ ẹniti maa nṣe aluwaala fun irun kọọkan ni ọpọlọpọ igba, igba mii yio ki gbogbo irun pẹlu aluwaala kan soso

O jẹ ẹniti maa fi Mudu kan ṣe aluwaala nigba mii, a ṣi maa lo idameji ninu idamẹta rẹ nigba mii, a si tun maa lo jubẹ lọ nigba mii

O si jẹ ẹniti sisẹ omi aluwaala rẹ kere ju ninu awọn eeyan, ti o si maa nki awọn ijọ rẹ nilọ kuro nibi lilo omi ni ilokulo

O jẹ ẹniti maa ṣe aluwaala ni ẹẹkọọkan, a si maa ṣe e ni meji meji, a si tun maa ṣe e ni mẹta mẹta Atipe a maa fọ apakan ninu awọn orike ara rẹ ni eemeji a si maa fọ awọn apakan ni ẹẹmẹta, ko si tayọ mẹta ri

O si tun jẹ ẹniti maa nyọ ẹnu rẹ ti si maa nfin imu rẹ pẹlu omi ọwọ kan nigba mii, a si maa lo ọwọ meji nigba mii, a si maa lo ọwọ mẹta nigba mii, o si jẹ ẹniti maa nso yiyọ ẹnu ati fifin imu papọ

O si tun jẹ ẹniti maa nfi ọwọ ọtun fin omi si imu ti o si maa nfi ọwọ osi fin in jade

Atipe ko si ṣe aluwaala Kankan ayaafi ki o yọ ẹnu ki o si fin omi si imu

O si tun jẹ ẹniti maa npa gbogbo ori rẹ, atipe nigba mii yio fi ọwọ rẹ mejeeji pa ori lọ si iwaju yio si tun pa a lọ si ẹyin

O si tun jẹ ẹniti maa npa aaso ori rẹ ti yio si pari iyoku lori lawani rẹ

O si tun jẹ ẹniti maa pa eti rẹ mejeeji – tinu tẹyin – pẹlu ori rẹ

O si tun jẹ ẹniti maa nfọ ẹsẹ rẹ mejeeji ti ko ba si khuffi tabi abọsẹsẹ nibẹ
Aluwaala rẹ si jẹ ohun ti maa nto tele ara wọn ti ko si kin jina si ara wọn, ko si fi igbakan fi silẹ lai ṣe
O si tun jẹ ẹniti maa nbẹrẹ aluwaala rẹ pẹlu didarukọ Ọlọhun, o si maa nsọ ni ipari rẹ pe: Ash’adu an laa ilaha illalloohu wah’dahu laa shariika lahu, wa ash’adu anna muhammadan ab’duhu wa rosuuluhu, allaahummo ij’alni minat’tawwabiin waj’alni minal mutatohhiriin (mo jẹri wipe ko si olujọsin fun Kankan ayafi Alloohu ni Oun nikan ti ko si si akẹgbẹ fun Un, mo si tun jẹri wipe Anabi Muhammad ẹru Rẹ ni ojiṣẹ Rẹ si tun ni, Irẹ Ọlọhun jẹ ki nmaa bẹ ninu awọn ti maa ntuuba ki O si tun jẹ ki nmaa bẹ ninu awọn ti maa nmọra) O tun maa nsọ pe: Sub’haanakal laahummọ wa bi’amdika, ash’adu an laa ilaaha illaa anta, astagfiruka wa atuubu ilaik (mimọ Irẹ Ọlọhun ti Ẹ si ni ẹyin pẹlu, mo jẹri wipe ko si olujọsin fun Kankan ayaafi Irẹ, mo wa aforijin Rẹ mo wa tuuba wa si ọdọ Rẹ). Ko si ki nsọ ni ibẹrẹ rẹ pe: Mo daniyan lati gbe ẹgbin kuro tabi lati sọ irun di ẹtọ, oun o ki nsọ ọ ko si tun si ẹnikẹni ninu awọn saabe rẹ ti maa nsọ ọ
Ko si ki nkọja igunpa ati kokosẹ
Ko si ki nduni mọ ninu awọn orike ara rẹ
O si tun jẹ ẹniti maa nya awọn ọmọ-ika rẹ, ko si ki nduni mọ ọn
O si tun jẹ ẹniti maa nya awọn ọmọ-ika rẹ, ko si ki nduni mọ ọn
Ko si si ninu ilana rẹ wipe ki wọn maa ba a ṣẹ omi ni gbogbo igba ti o ba ti nṣe aluwaala, sugbọn ni igba mii a maa da a funra rẹ, ẹlomii si le ran an lọwọ lati da a nigba mii fun idi kan

# Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi pipa khuffi rẹ mejeeji

O fi ẹsẹ rinlẹ lati ọdọ rẹ wipe o pa a ni ile ati ajo, o si fi ọjọ kan ati oru rẹ silẹ fun ẹniti o wa nile lati fi pa a, o si fi ọjọ mẹta pẹlu oru rẹ silẹ fun arin irin-ajo lati fi pa a
O si jẹ ẹniti maa npa oke khuffi, atipe o pa ibọsẹ na Atipe o pa lawani rẹ nikan, o si tun pa a pẹlu aaso ori rẹ
Ko si ki nla ohun ti o yatọ si ipo ti ẹsẹ ba wa bọ ara rẹ lọrun, bi kii ṣe wipe ti o ba jẹ wipe inu khuffi ni mejeeji wa yio pa a ni, ti mejeeji ba si wa ni sisi silẹ yio fọ ọ ni

# Ilana rẹ nibi aluwaala eleepẹ

O maa nṣe tayammam pẹlu ilẹ ti o maa nkirun ni ori ẹ, o jẹ iyepe lasan ni tabi ilẹ iyọ tabi ilẹ yanrin, o si maa nsọ pe: Ibikibi ti irun ba ti ba ọkan ninu ijọ mi, ibẹ naa ni masalaasi rẹ ati imọra rẹ
Ko si ki ngbe iyepẹ dani lọ si irin-ajo ti o ba gun, ko si paṣẹ pẹlu ṣiṣe bẹ
Ko si fi ẹsẹ rinlẹ lati ọdọ rẹ ṣiṣe aluwaala eleepẹ fun irun kọọkan, bi kii ṣe wipe o tu aluwaala eleepẹ silẹ o si gbe e si ipo aluwaala olomi
O maa nṣe tayammam pẹlu fifi ọwọ lu ilẹ ni ẹẹkan ti yio si fi pa oju ati ọrun ọwọ rẹ mejeeji

# Ilana rẹ nibi irun

## Ilana rẹ nibi bibẹrẹ irun ati kika nkan

O jẹ ẹniti o ṣe wipe ti o ba ti dide lati ki irun yio sọ wipe: Alloohu Ak’bar, ko si ki nsọ nkankan siwaju rẹ, ko si wi aniyan jade ri rara
O si tun jẹ ẹniti maa ngbe ọwọ rẹ mejeeji soke pẹlu rẹ ti yio si na gbogbo awọn ọmọ ika rẹ lẹniti o da oju kọ qiblah de ibi eti rẹ mejeeji - ati de ibi ejika rẹ mejeeji – lẹyinna ni yio wa gbe ọwọ ọtun rẹ lori ẹyin ọwọ osi rẹ
O si jẹ ẹniti maa nbẹrẹ irun nigba mii pẹlu gbolohun: Allaahummọ baahid bainii wa baina khọtọyaaya kamọọ baahad’ta bainal mọsh’riq wal mọg’rib, Allaahummọg-sil’nii min khọtọọyaaya bil mọọhi wath’thal’ji wal barad, Allaahummọ naq’qinii minadh-dhunuubi wal khọtọọya kamọọ yunaq’qọth-thaobul ab’yadu mind-danas A si tun maa sọ ni igba mii pe: Waj’jahtu wajhiya lilladhii fatọrọs-samọọwaati wal ar’dọ aniifan muslimọn wa mọọ ana minal mush’rikiin, inna sọlaatii wa musukii wa mah’yaaya wa mọmọọtii lillaahi rọbbil aalamiin, laa shariika lahu, wa bidhaalika umir’tu, wa anaa awwalul muslimiin
Bẹẹ lo maa nsọ pe 'AUDHU BILLAAHI MINASH-SHAYTAANI-R-RAJIIMI' ìyẹn lẹyin igba ti o ba ṣe adua aṣeṣirun. Lẹyin naa ni yoo wa ka suratul faatihat
O si ni aye idakẹjẹẹ meji kan ;eyi ni idakẹjẹẹ diẹ laarin ṣiṣe gbolohun igbe Ọlọhun tobi akọkọ ati igba ti o ba fẹ kọkọ ka nkan lori irun. Ariyanjiyan si nbẹ nipa aye idakẹjẹẹ ẹlẹẹkeji Awọn kan gba ẹgbawa pe lẹyin kike faatihat nii bẹẹ ni ẹgbawa ọrọ miran sọ wipe siwaju ki o to rukuu nii Ti o ba si ti pari kike faatihat tan yoo mẹnu le kike Surat miran. A maa jẹ ki Surat naa gun nigba miran bẹẹ a si maa ṣe e ni fifuyẹ fun idi kan tabi omiran gẹgẹ bii irin-ajo tabi idi miran, ṣugbọn lọpọlọpọ igba lo maa wa ni iwọntun-wọnsi. O jẹ ẹni

ti o maa nka aaya bi ọgọta si ọgọrun lori irun idaji O  fi suratu Qaaf ki i ri O fi suratu Ruum ki i ri O fi suratu 'IDHAṢH-ṢHAMSU KUWWIRAT' ki i ri O fi  suratu 'IDHAA ZULZILATIL ARDU ZILZAALAHAA' ki i lori rakaa kinni-keji ri O fi suratul MU' AWWIDHATAYNI (IYẸN QUL AUDHU MEJEEJI) ki i ri nigba ti o nbẹ lori irin-ajo lọjọ kan O ki i lọjọ kan ti o si mẹnu le suratul MU'MINUN lori iduro akọkọ, o ka a titi to fi de ibi ti ọrọ anọbi Musa ati Haaruna ti jẹyọ ni ikọ ba wu u gidigidi o si rukuu nitori rẹ A  maa fi suratu ALIF LAAM MIIM ti sajdat ati suratu HAL ATAA ALAL INSAANI ki i loojọ ọjọ jimọ Ṣugbọn lori irun zuhr (aila) o maa nfa keu kike rẹ gun nigba miran Ṣugbọn lori irun alaasari ti o ba fẹ ko gun a maa ke deede ilaji nkan ti o ke lori irun zuh'r. A si maa ṣe e ni odiwon re ti o ba fẹ ko kuru

ṣugbọn  irun magrib, o fi suratu TUR ki i ri, bẹẹ lo si fi suratul MURSALAAT ki i nigba miran naa.

ṣugbọn  lori irun ishai o ka suratu WATTIINI lori rẹ ri koda o ṣe e ni ilana fun Muadh nibi irun Ishai yii pe ki o maa fi suratu WAṢṢHAMSI WADUHAAHAA, suratu SABIHISMA RABBIKAL A'LAA, suratu WALLAYLI IDHAA YAGHSHAA tabi awọn surat bi iru awọn wonyii ki i. O si kọ fun-un bi o ṣe ka suratul BAQARAT lori irun ishaai yìí.

Ninu arikọṣe ilana rẹ ni kika odidi Surat kan lori raka kan. A si maa ka odidi Surat kan naa lori raka meji. Nigba miran a maa ka awọn ibẹrẹ Surat lori irun, ṣugbọn ko pẹlu nkan ti a mọ mọ ọn pe ki o ka awọn ipari Surat ati aarin rẹ bakan naa.

ṣugbọn kika Surat meji lori raka kan, lori irun nafilat lo ti maa nṣe bẹẹ Ṣugbọn  pipin Surat kan ke lori raka meji o kere nigba ti o maa nṣe bẹẹ. Kii sii ṣe adayanri Surat kankan lọna to ṣe wipe ko si bi yoo ṣe keu lori irun lai ni ka a ayafi lori irun jimọ ati irun yidi mejeeji nikan. O si ṣe adua kunut lẹyin igba ti o gbori soke kuro ni itẹriba (ruku') l'ori irun afẹmojumọ fun oṣu kan, lẹyin naa o fi i silẹ ko ṣe e mọ. Bẹẹ ṣiṣe kunut rẹ yii waye nitori iṣẹlẹ ojiji kan nigba ti o si ti re kọja o fi i silẹ ko ṣe e mọ. Eyi jẹ ki a mọ wipe ilana rẹ ni lati maa ṣe adua kunut lasiko awọn iṣẹlẹ meriiri alagbara nikan ati wipe ko da ṣiṣe rẹ yanri fun irun afẹmọju nikan.

# Ilana-iṣe rẹ- ki Ọlọhun ṣe ikẹ ati igẹ rẹ fun un- nipa bi a ṣe nkirun

O jẹ ẹni ti o maa nfa raka akọkọ gun ju ẹlẹẹkeji lọ nibi gbogbo irun (ti o ba ki)

Bẹẹ  lo jẹ pe igbakigba ti o ba keu tan (lori raka) yoo dakẹ diẹ ni odinwọn igba ti eemi rẹ yoo fi (sinmi) pada si i lara. Lẹyin naa yoo gbe ọwọ rẹ soke yoo si ṣe Allahu akbar ti yoo si ruku, yoo si gbe ọwọ rẹ mejeeji le orunkun rẹ mejeeji bi igba ti o fi di wọn mu, yoo wa fi apa rẹ mejeeji ṣe bi okun orun ọfa bẹẹ yoo si gbe wọn jina si ẹgbẹ rẹ mejeeji, yoo si tẹ ẹyin rẹ pẹrẹsẹ yoo naa silẹ yoo si jẹ ko tọ, kii si na ori rẹ soke tabi ki o kii bọnu bi ko ṣe wipe yoo wa ni ibamu pẹlu ẹyin rẹ

O si maa nsọ pe SUBHAANA RABBIYAL AZEEM Nigba miran a tun maa sọ nibẹ bayii SUBHAANAKALLAAHUMMA RABBANAA WABIHAMDIKA, ALLAAHUMMAGFIR LII (Mimo fun Ire Oluwa mi, Ire Oluwa, Oluwa wa ati pe pelu eyin Re, Ire Oluwa, fi orijin mi) A tun maa sọ bakan naa pe SUBBUUHUN QUDDUUSUN RABBUL MALAAIKATI WARRUUHI Ruku rẹ ti o maa nsaba ṣe maa ngun to deedee asiko ti eeyan yoo fi ṣe afọmọ (iru eyi ti a nṣe lori ruku) lẹẹmẹwa, bẹẹ gẹgẹ naa ni gigun iforibalẹ rẹ. Ṣugbọn nigba miran a maa jẹ ki ruku ati iforikanlẹ rẹ o ṣe deede (gigun) iduro rẹ ṣugbọn o maa n ṣe bẹẹ lẹẹkọọkan lori irun nafilat oru ni o. Ilana-iṣẹ rẹ to pọju lori irun naa ni ṣiṣe e ni iwọntunwọnsi ati ṣiṣe amojuto ibaramu rẹ. O si maa nṣiri soke lati ipo ruku ti yoo sọ pe : SAMIALLAAHU LIMAN HAMIDAH Yoo si gbe ọwọ rẹ mejeeji soke, yoo na ogooro ẹyin rẹ. Gẹgẹ bẹẹ naa ni o ṣe ńṣe nigba ti o ba gbori soke lati iforikanlẹ. O si sọ pe: “ko si irun naa ti o ṣee gba nirun ti ẹni ti n ki i ko ba jẹ ki ogooro ẹyin o na pada si aye rẹ nigba ti o ba tẹri ba ati nigba ti o fa f'ori kanlẹ” Ti o ba ti wa duro deede tan yoo sọ pe : RABBANAA WALAKALHAMD. Nigba miran o le sọ pe “RABBANAA LAKALHAMD',tabi ALLAAHUMMA RABBANAA LAKALHAMD A si maa jẹ ki origun yii o gun ni deede gigun ruku rẹ a si maa sọ l'ori rẹ bayii Allaahumma Rabbanaa walakalhamd mil'assamaawaati wamil'al ardi wamil'a maa baynahumaa wamil'a maa shi'ta min shay'in ba'du ahlath-thanaai walmajdi ahaqqu maa qaalal abdu wakullunaa laka abdu, laa maani'a limaa a'tayta walaa mu'tiya limaa mana'ta walaa yanfa'u dhal jaddi minkal jaddu. Lẹyin naa yoo ṣe Allahu akbar yoo si wo ti yoo f'ori kanlẹ bẹẹ, kii si gbe ọwọ rẹ soke laaye yii. A si maa kọkọ fi orunkun rẹ mejeeji kanlẹ, lẹyin rẹ ni ọwọ mejeeji, lẹyin rẹ ni iwaju ori re ati tente ori imu rẹ. A si maa lo iwaju ori rẹ ati ori imu rẹ f'ori kanlẹ yatọ si ẹlọ lawani ori rẹ O si maa nfori kanlẹ lọpọlọpọ lori iyẹpẹ ati ilẹ ẹrẹ tutu, ati itẹ ti wọn fi imọ ọpẹ ṣe , ati ẹni ti wọn fi imọ ọpẹ ṣe, ati awọ ti wọn rẹ lose

O si jẹ ẹni ti o ṣe pe nigba ti o ba fori kanlẹ yoo fi ori ati imu lelẹ daadaa yoo si gbe ọwọ rẹ mejeeji jina ẹgbẹ rẹ yoo jẹ ki wọn yakata debi wipe eeyan yoo maa ri funfun abẹ abiya rẹ mejeeji.

O si maa ngbe ọwọ rẹ mejeeji lasiko iforikanlẹ si deedee ogangan ejika ati eti rẹ, bẹẹ yoo si ṣe deede lori iforikanlẹ rẹ a si maa fi tente ori ọmọ ika ẹsẹ rẹ doju kọ Qiblat (ibudojukọ kirun), yoo si tẹ atẹlẹ ọwọ ati ọmọ ika rẹ silẹ, kii si ya ika rẹ tabi ki o ka a ko.

O si maa nsọ pe SUBHANAKALLAAHUMMA RABBANAA WABIHAMDIKA ALLAAHUMMAGFIR LII O tun maa nsọ pe: SUBBUUHUN QUDDUUSUN RABBUL MALAAIKATI WARRUUHI Lẹyin naa yoo gbe ori rẹ soke ti yoo si ṣe Allaahu akbar lai ni gbe ọwọ rẹ soke, lẹyin naa yoo joko ti yoo tẹ ẹsẹ rẹ, yoo tẹ ọpa ẹsẹ osi rẹ silẹ yoo joko le e, yoo si ka ọpa ẹsẹ ọtun rẹ sẹyin yoo fi ẹsẹ ọtun rẹ tilẹ. A si maa gbe ọwọ rẹ mejeeji lè itan rẹ mejeeji ti tente awọn ọmọọka yoo si wa lori orunkun rẹ mejeeji. Yoo wa ka meji ninu awọn ọmọọka ọwọ ọtun rẹ ko yoo si fi ṣe bi oruka. Lẹyin naa yoo na ika ifabẹla ti yoo si maa ṣe adua pẹlu bẹẹ ti yoo si maa fi ika naa, Lẹyin naa yoo wa maa sọ pe ALLAAHUMMAGFIR LII, WAR'HAMNI , WAJBURNII, WAHDINII, WARSUQUNII Eyi ti o si jẹ ilana arikọṣe rẹ - ki Ọlọhun ṣe ikẹ ati igẹ rẹ fun-un - ni fifa origun irun yii gun ni odinwọn asiko ti o fi forikanlẹ Lẹyin naa yoo fi iwaju ẹsẹ rẹ dide ti yoo si sinmi le itan rẹ. Ti o ba ti wa dide tan yoo bẹrẹ lati maa keu siwaju sii lai ni dakẹ diẹ bi iru idakẹ igba ti o ṣẹṣẹ ṣi irun rẹ. Lẹyin naa yoo ki raka irun keji gẹgẹ bii takọkọ ayafi nibi nkan mẹrin kan {ni yoo fi yatọ sii} ; eyi ni idakẹ diẹ, adua ti a fi nṣi irun, kabara akọkọ (Allaahu akbar) ti a fi nfun irun lọwọ ati fifaa gun. Nitori iṣe rẹ ni fifa iduro akọkọ gun ju ẹẹkeji lọ koda a maa fa a gun titi ti ko fi ni gbọ iro ẹsẹ (pe enikan ṣẹṣẹ nwọ irun) ko to wa lọ si rukuu. Nigba ti o ba si joko lati ka gbolohun ijẹri (attahiyyat) yoo gbe ọwọ ọtun rẹ le itan ọtun yoo si gbe t'osi naa le itan osi yoo wa fi ìka ifabẹla rẹ tọka si ọọkan. Kii si ṣe iṣe rẹ lati na ika naa soke bẹẹ kii d'ẹnu rẹ kọlẹ bi ko ṣe pe yoo rọra tẹ ẹ kọkọrọ diẹ yoo si maa min in, yoo wa ka ika ookayẹmi ati ọmọdinhun rẹ ko, yoo fi ika aarin rẹ ati atanpako ṣe oruka, yoo na ifabẹla rẹ siwaju ti yoo si maa ṣe adua lọ bẹẹ, bẹẹ naa ni yoo dari oju rẹ sara ika ifabẹla naa. Gbogbo igba ni o maa nka ataaya lori ijoko yii bẹẹ lo si maa nkọ awọn sahabe rẹ lati maa kaa pe ATTAHIYAATU LILLAAHI WASSALAWAATU WATTAYYIBAAT, AS SALAAMU ALAYKA AYYUHA-N-NABIYYU WARAHMATULLAAHI WABARAKAATUHU, ASSALAAMU ALAYNA WA ALAA IBAADILLAAHI-S-SAALIHIIN, ASH'ADU AN LAAILAAHA ILLA-LLAAHU WA ASH'ADU ANNA MUHAMMADAN ABDUHU WARASUULUH A si maa yara ka a gan-an lọpọlọpọ gẹgẹ bi igba to ṣe pe ori okuta gbigbona lo ti nkirun ni Lẹyin naa yoo fi inu ọmọ ika ẹsẹ rẹ ati orunkun rẹ tilẹ dide dide ti yoo fi itan rẹ gbera duro, yoo si ṣe Allaahu akbar. Bẹẹ a maa gbe ọwọ rẹ soke (nigba ti o ba ṣe Allaahu akbar) laaye yii Lẹyin naa yoo ke suratul faatihat nìkan, nigba mii a si maa ke ju suratul faatihat lọ lori raka mejeeji to gbẹyin irun naa Oun (anọbi) -ki Ọlọhun ṣe ikẹ ati igẹ rẹ fun un- si jẹ ẹnikan to ṣe pe nigbakigba to ba joko fun gbolohun ijẹri (attahiyyat) to kẹyin irun a maa joko rẹ ti yoo fi kekeru idi rẹ lelẹ. Yoo fi kekeru idi tilẹ yoo si yọ ẹsẹ rẹ sita si ẹgbẹ kan naa

Yoo fi ẹsẹ osi rẹ sabẹ itan ati ọpa ẹsẹ rẹ, yoo si fi ẹsẹ ọtun rẹ tilẹ, nigba miran a maa tẹ ẹsẹ rẹ sẹyin pẹrẹsẹ

Yoo si gbe ọwọ ọtun rẹ le itan ọtun rẹ yoo si pa awọn ọmọ ika rẹ mẹtẹẹta pọ yoo si yọ ika ifabẹla rẹ soke

Bẹẹ a si maa ṣadua lori irun rẹ laaye yii. A si maa wi pe Allaahumma  innii auudhu bika min adhaabil qabri, wa audhu bika min fitnatil masiihi dajjaal, wá auudhu bika min fitnatil mahyaa walmamaat Allaahumma innii audhu bika minal ma'thami walmaghram Iṣesi rẹ lẹyin naa ni ki o salamọ si apa ọtun rẹ pe: AS-SALAAMU ALAYKUM WARAHMATULLOOH, yoo si tun sa a bẹẹ si apa osi rẹ

O si pa ẹnikẹni ti o ba fẹ kirun laṣẹ pe ki o wa gaga fun irun rẹ koda bi o ju pẹlu ọfa tabi ọpa lọ. Oun gan-an naa a maa ṣe bẹẹ nigba ti o ba wa lori irin ajo tabi lori papa gbansasa, yoo ti ọkọ bọlẹ yoo si maa kirun si i lara ti yoo jẹ gaga fun un. Nigba mi a maa dabu nkan'gun rẹ yoo si maa kirun si i, koda a maa mu gaari ẹsin yoo gbe e kalẹ daadaa yoo si maa kirun sara eti rẹ lọwọ ẹyin.

Nigba ti o ba kirun sara ogiri, iṣesi rẹ ni lati fi alafo ti yoo to ewurẹ gba kọja saarin oun ati ogiri naa, kii si ta kete si gaga ifikirun rẹ koda o ti pa aṣẹ pe ki a maa sunmọ gaga ikirun wa.

## Itọnisọna ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi awọn nkan ti o maa nṣe lori irun

Yiyi oju kaakaakiri lori irun o si ninu itọnisọna rẹ

Bakannaa didiju lori irun o si ninu itọnisọna rẹ.

Ti o ba si ti wa lori irun, yio da ori rẹ kọlẹ‹ O si maa nwọ irun lẹniti yio wa fẹ lati fa irun naa gun, ti o ba ti wa gbọ ẹkun ọmọ kekere, yio wa ṣe irun naa ni fufuyẹ ni ẹniti o fi npaya wipe ki oun ma baa ni iya ọmọ naa lara. Bakannaa, o si tun ma nki irun ọranyan ni ẹniti yio gbe Umaamah ọmọọmọ rẹ lobinrin kọrun, ti o ba ti wa dide soke yio gbe e dani, bakannaa ti o ba ti fẹ rukuhu ati iforibalẹ, yio gbe e silẹ. O si nmaa kirun ti Hasaan tabi Hussein o wa ba a, ti yio si pọn si ẹyin rẹ, yio  wa fa iforikanlẹ rẹ gun ni ẹniti o fi nkọ pe ki o ma baa rebọ lẹyin rẹ

O si tun ma nkirun ti iya wa Aisha o si fẹ wa ba a, yio wa rin lati ba a ṣi ilẹkun, lẹyin igba naa ni yio wa pada si aaye ikirun rẹ.

O si tun ma nda salamọ pada nigba ti o ba nkirun lọwọ pẹlu lilo ami itọka fun dida salamọ pada. .

O si maa n fenu fategun lori irun ti ba nki, bakannaa, o si tun ma nsukun, o si tun maa ngbeko ti o ba bukaata si i..

O si ma nkirun lẹniti ko ni wọ bata nigba mii, o si tun ma nwọ bata nigba miran. Ó wa paṣẹ pẹlu mimaa kirun pẹlu wiwọ bata ni ifi yapa ilana awọn Yahuudi.
O si ma nkirun ninu aṣọ kan nigba mii tabi aṣọ meji nigba miran, oun si ni o pọ ju.

## Itọnisọna ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - nibi awọn iṣesi rẹ nigba ti o ba kirun tan :

Ti o ba ti salamo, o jẹ ẹniti o ma nwa aforijin pẹlu gbolohun (Astaghfirullah) lẹẹmẹta, lẹyin igba naa ni yio wa sọ gbolohun “Allahumma anta-s- Salaam wa minka-s- Salaam Tabaarak'ta yaa zal Jalaali Wal ikraam”. ( Mo pe iwọ Oluwa mi! Iwọ ni Ọba alaafia, ọdọ Rẹ si ni alaafia ti nwa, Gbigbọn-n-gbọn Rẹ, Iwọ Ọba ti O ni titobi ati apọnle) . Ko si ni pẹ ni idajukọ Qiblah ayaafi deedee odiwọn ohun ti yio fi sọ gbolohun yẹn, ṣugbọn ooo, yio yara lati yira si ọdọ awọn ero ẹyin, bakanaa o si ma nyi si ẹgbẹ ọtun rẹ ati si ẹgbẹ osi rẹ.
Ti o ba ti kirun Alufajari tan, yio joko si aaye ikirun rẹ titi ti orun o fi yọ sita. .
O wa jẹ ẹniti o ma nsọ gbolohun yii lẹyin irun ọranyan : “Laa ilaaha illa laah, Wah'dahu laa shariika lahu, lahul Mulku wa lahul Hamdu Wa uwa ala kulli shaein Qodiir,Allahuma la maaniha lima A'tayta Wa la mu'tiya lima mana'ta wa la yan'fahu zal jaddi Minkal jaddu” (Ko si eniti ijosin to si ayafi Allah nikan, ko si orogun fun Un, ti E ni ola se, atipe ti E ni eyin se, atipe O je alagbara lori gbogbo nkan, Ire Oluwa, ko si oludena fun nkan ti O ba fun ni, atipe ko si olufunni ni ohun ti O ba ko funni atipe oro kole wulo fun oloro ni odo Re). “Wa la haola wa laa kuwwata illa billaahi, Wa la na'budu illa iyyah, lahun ni'matu wa lahul fadlu wa lahu-th-thanaahul hasan, Laa ilaaha illa laah, mukhlisiina lahud diin wa Lao karihal kaafirun”
O wa ṣe e ni sunnah fun awọn ijọ rẹ pe ki wọn o maa sọ gbolohun wọn yii ni ẹyin gbogbo irun ọranyan kọọkan "Subhaanallaah" ni ẹẹmẹtalelọgbọn, ati "Alhamdulillaah" ni ẹẹmẹtalelọgbọn bakannaa ati "Allahu Akbar" ni ẹẹmẹtalelọgbọn, ati fifi gbolohun "Laailaaha illa laah wah'dahu laa shariika lahu, lahul- mul’ku wa lahul-ham’du, wa uwa ala kuli shaein kọdiir" ṣe ọgọrun rẹ.

## Itọnisọna ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - nibi awọn iṣẹ ifinufindọṣe ati didide loru.

O maa nki gbogbo awọn irun aṣegbọrẹ ati awọn irun ifinufindọ ki ni eleyi ti ko si sababi kankan fun un ni ile rẹ, agagajulọ naafilah irun maghrib. .
O si ma ntẹramọ  lati ki awọn rakah mẹwa nigba ti ko ba si ni irin-ajo ni gbogbo igba, yio ki rakah meji siwaju dhur ati rakah meji lẹyin rẹ, bakanna o si ma nki rakah meji lẹyin irun maghrib ati rakah meji lẹyin ishai ni ile rẹ, bakannaa yio si tun ki irun rakah meji siwaju irun asunba. .
Titẹramọ irun naafilah asunba rẹ jẹ ohun ti o tẹramọ ju ninu awọn naafilah to ku, bakannaa ko si ki ngbe e (naafilah irun asunba) ati irun naafilah witiri silẹ boya o wa nile ni o abi ori irin ajo. Wọn o si gba a wa lati ọdọ rẹ pe o ki irun naafilah kankan lori irin ajo yatọ si awọn mejeeji ti a darukọ siwaju.
O si tun ma nfi ẹgbẹ ọtun rẹ lelẹ lẹyin igba ti o ba ti ki irun naafilah Asunba tan
O si ma nki naafilah rakah mẹrin siwaju irun dhur nigba mii, ti irun rakah meji ba ti wa bọ mọ ọn lọwọ lẹyin irun Dhur , yio wa san an pada lẹyin irun Asr'.
Eleyi ti o wa pọju ninu irun oru rẹ naa ni eyi ti o maa nduro ki, igba mii a si maa ki i ni ẹniti o joko, nigba mii aa ka nkan ni eniti o joko ti o ba wa sẹku keu kekere nibi ohun ti o nke, yio wa dide ti yio si wa ruku lẹniti o duro.
O si ma nki irun rakah mẹjọ, o si maa nsalamọ lẹyin gbogbo rakah meji meji, lẹyinna ni yio wa ki witri pẹlu rakah maarun leyiti yio ki i tele ara wọn, ti ko si ni joko ayafi igba ti o ba to de ipari wọn, tabi ki o ki witiri pẹlu rakah mẹsan, ti yio si ki mẹjọ ninu rẹ ni tẹle-ntẹle, ko si ni joko ayafi ti o ba to de ibi rakah ẹlẹẹkẹjọ, lẹyin igba naa yio wa dide soke ti ko si ni salamọ, lẹyin igba naa ni yio wa ki rakah ẹlẹẹkẹsan, lẹyin igba naa yio wa joko ti yio si ṣe ataaya, yio wa salamọ, lẹyin igba naa ni yio ki rakah meji lẹyin igbati o ti salamọ, tabi ki o ki witiri pẹlu rakah meje gẹgẹ bi o ṣe ṣe nibi rakah mẹsan alakọkọ ti wọn darukọ siwaju, lẹyin igba naa ni yio wa ki rakah meji lẹyin rẹ ni ori ijokoo.
O si ma nki irun witiri rẹ ni asiko akọkọ loru abi aarin rẹ abi ipari rẹ, o wa sọ pe: "Ẹ maa fi irun witiri ṣe igbẹyin irun yin loru".
O si jẹ ẹniti o ma nki irun rakah meji lẹyin irun witiri ni ori ijoko nigba mii, ati pe nigba miran o si ma nkeu nibi rakah mejeeji ni ẹniti o joko, ti o ba ti wa fẹ ruku yio wa dide ti yio wa ruku.
Ti o ba ti wa sun lọ tabi ti o ni ara riro ti o pọ, yio fi ki rakah mejila ni ọsan.
Yio wa dide loru pẹlu mimaa ke aayah kan, yio wa maa paara rẹ titi di afẹmọjumọ.
O maa nke (Alukurani) ni jẹẹjẹ nibi irun oru nigba mii, o si tun ma nke e soke nigba miran, bakanaa ni pe o ma nfa iduro gun nigba mii, o si tun ma nṣe e ni fufuyẹ nigba mii.

O wa ma nka surah ti o bẹrẹ pẹlu ( SABI IS'MA RỌBIKAL A'LAH) ati surah ti o bẹrẹ pẹlu (QUL YA AYUAL KAAFIRUN) ati surah ti o bẹrẹ pẹlu (QUL UWA LLAAAHU AHAD) nibi irun witiri rẹ
Ti o ba ti wa salamọ, yio wa sọ gbolohun (SUB'HAANA LMALKIL QUDDUUS) ni ẹẹmẹta, o si ma nfa ohun rẹ gun nibi ẹlẹẹkẹta, ti yio si gbe e soke.

## Itọnisọna ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi irun Jimoh.

Gbigbe ọjọ Jumuah tobi ati pipataki rẹ ati sisa a lẹsa pẹlu awọn nkan ti o jẹ nkan ẹsa nbẹ ninu itọnisọna rẹ ; ninu wọn naa ni: wiwẹ ni ọjọ naa, ati wiwọ aṣọ ti o dara julọ ni ọjọ naa, ati didakẹ fun gbigbọ khutubah ni nkan ti o jẹ dandan, ati pipọ ni sise asalaatu fun Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a. Ti wọn ba ti wa kojọpọ tan, yio wa jade sì wọn yoo si salamọ si wọn, lẹyin igba naa ni yoo wa gun ori minbari, yio wa doju kọ wọn, yio si tun salamọ si wọn, lẹyin igba naa ni yio wa joko, Bilal o wa perun, ti o ba ti wa pe e tan, yio dide yio si ṣe khutubah fun wọn laini fi aye kankan silẹ laarin piperun ati ṣiṣe khutubah, o si maa ṣe khutubah lẹniti o nrọgbọku sori ọrunfa tabi ọpa siwaju ki o to maa lo minbari.
O ma nṣe khutubah ni ori iduro, lẹyin igba naa ni yoo wa joko ijoko fufuyẹ kan, lẹyin igba naa ni yoo dide, yio wa bẹrẹ khutubah ẹlẹẹkeji.
O wa jẹ ẹniti o ma npa awọn eniyan laṣẹ pe ki wọn o sunmọ oun ati didakẹ fun gbigbọ khutubah, yio wa maa sọ fun eyikeyi arakunrin  ti o ba sọ fun ẹnikeji rẹ pe: Dakẹ, niti paapa o ti sọrọ ti ko sanfaani, ẹniti o ba si sọrọ ti ko sanfaani, ko si laada Jimoh fun un.
O si jẹ ẹniti oju rẹ mejeeji maa npọn nigbati o ba nṣe khutubah, ti ohun rẹ o si lọ soke, ibinu rẹ o si pọ, ti yio wa da bi pe o nṣe ikilọ fun awọn ti wọn lọ si oju ogun.
O wa jẹ ẹniti o ma nsọ gbolohun (AMMA BA'DU) nibi khutubah rẹ yio wa ṣe khutubah rẹ ni kekere ti yio si fa irun naa gun.
O wa ma nkọ awọn sahabe rẹ nibi khutubah nipa awọn opo Isilaamu ati awọn ofin rẹ, o si tun maa npa wọn laṣẹ ti si maa nkọ fun wọn nigba ti aṣẹ kan ba wa ba a abi kikọ kan
O si tun ma nda khutubah  rẹ duro  nigba ti bukaata kan ba yọju si i, abi ti o ba fẹ dahun ibeere ẹnikan ti o ba bi i leere, lẹyin igba naa ni yio ṣẹri pada sori khutubah rẹ ti yio si pari rẹ, bakannaa nigba miran, o ma nsọkalẹ lati ori minbari lati wa gbọ bukaata lẹyin rẹ ni yio pada si ori minbari, o si ma npa wọn laṣẹ nibamu si iṣesi wọn ba ṣe wa si nibi khutubah rẹ. Ti o ba ti wa ri ẹniti o osi nta abi ẹniti o fẹ gbọ bukata, yio pa wọn laṣẹ pe ki wọn o ṣe saara fun un, yio wa ṣe wọn loju ọyin lori ẹ,
o ma nṣe itọka pẹlu ọmọnika rẹ (ọwọ ataaya) nibi khutubah rẹ nigba ti o ba de ibi iranti Ọlọhun, bakanaa ti ojo ko ba si rọ, yio tọrọ rirọ ojo lọdọ Ọlọhun nibi khutubah rẹ.
Bakanaa ti o ba kirun Jimoh tan yio wọ ile rẹ ti yio si yan naafilah rakah meji ti o jẹ aṣegbọrẹ rẹ, o wa pa ẹniti o ba ki I (Jimoh) laṣẹ pe ki o kirun rakah mẹrin lẹyin rẹ.

## Itọnisọna ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - nibi irun yidi mejeeji ( Eidul fitr' ati Eidul-Ad'ha).

O ma nki irun yidi mejeeji ni ori papa-ikirun, o si ma nwọ eyi ti o ba dara julọ ninu awọn aṣọ rẹ.
O ma njẹ awọn eso dabinu ni ọjọ ọdun itunu awẹ siwaju ki o to jade kuro nile, o ma njẹ wọn ni onka ti meji o le ge ṣugbọn ni ọjọ ọdun Ileya, ko ni jẹ nkankan titi yoo fi de lati papa-ikirun o si ma njẹ ninu ẹran ijọsin fun Ọlọhun ti o ba pa, o ma nlọ irun ọdun itunu awẹ lara, ti o si maa ntete kirun ọdun ileya.
O ma njade ni ẹniti yio fi ẹsẹ rin, ti wọn o si gbe ọpa tele e niwaju rẹ, ti wọn ba ti wa de ibẹ wọn o naa duro siwaju e, ki o fi le kirun si i lara.
ti o ba ti wa de ibi aaye ikirun, yio bẹrẹ si ni kirun laini pe irun tabi ṣe ikọọmọ, bakanna ko si ni sọ gbolohun (AS-SALAATU JAAMIATUN), Ti oun ati awọn sahabe rẹ ba ti de papa-ikirun, wọn o ni kirun kankan siwaju rẹ tabi lẹyin rẹ. O ma nkọkọ kirun siwaju ki o to ṣe khutubah, yio wa kirun rakah meji (irun yidi), yio wa kabara meje ni tẹlentẹle nibi rakah alakọkọ pẹlu bibẹrẹ pẹlu kabara wiwọ irun (TAKBIIRATUL IHRAM) yio wa maa dakẹ laarin kabara meji meji ni didakẹ kekere, Ko si asikiri kan pato ti o maa n se laarin awọn kabara naa, Ti o ba ti wa pari awọn kabara rẹ tan, yio wa bẹrẹ si ni ka keu (Alukurani), ti o ba wa pari rẹ tan yio kabara yio si ruku, lẹyin igba naa ni yoo kabara marun ni tẹlentẹle nibi rakah ẹlẹẹkeji, lẹyin rẹ ni yio wa bẹrẹ si ni ka keu (Alukurani), Ti o ba ti wa pari yio wa ṣe khutubah fun awọn eeyan ti wọn o si joko si aaye saafu wọn, yio wa ṣe waasi fun wọn, yio si tun pa wọn laṣẹ daadaa ati pe yio tun kọ iwa ibajẹ fun wọn. O wa ma nka surah to bẹrẹ pẹlu (Qọọf) ati (Iq'tarabat) ni kika tan perepere, nigba mii o si ma nka surah to bẹrẹ pẹlu (Sabi) ati suratul Gọọshiyah
Bakanaa ni pe o ma nṣe khutubah lori ilẹnlẹ, tori ko si minbari kankan.
O wa ṣe e ni fufuyẹ nibi aima maa joko fun khutubah, atipe irun yidi ti to fun irun Jimoh ti ọdun ba waye lọjọ naa (Jimoh).

Ni ọjọ ọdun, ọna ti o maa n gba pada maa n yatọ si eyi ti o maa n gba lọ

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nigbati ọsan ba di oru

Nigbati ọsan di oru, o jade lọ si mọsalaasi lẹniti nyara ti o sin bẹru ti nfi aṣọ rẹ gbalẹ, o wa bọ siwaju o si ki rakaah meji, o ka faatiah nibi alakọkọ ati suurah ti o gun, o si ka a soke, lẹyinna ni o wa rukuu o si pẹ ni rukuu, lẹyinna ni o gbe ori kuro o si pẹ lori iduro, ti ko si to iduro alakọkọ O wa sọ nigbati o gbe ori kuro ni rukuu pe: Samihalloohu liman amidahu, robbanaa wa lakal am'du Lẹyinna ni o wa bẹrẹ si ni nka nkan, lẹyinna ni o wa rukuu, ti ko si to rukuhu alakọkọ Lẹyinna ni o gbe ori kuro ni rukuu, lẹyinna ni o wa lọ si iforikanlẹ kan ti o gun ti o si pẹ ni iforikanlẹ na Lẹyinna ni o ṣe nibi rakaah keji iru ohun ti o ṣe nibi rakaah alakọkọ, ti o si jẹ wipe rakaah kọọkan ni o ni rukuu meji ati iforikanlẹ meji Lẹyinna ni o wa kuro, ti o si ba awọn eeyan sọrọ ni ibasọrọ ti o de ogongo

O si paṣẹ nigbati ọsan ba ti oru pẹlu imaa ranti Ọlọhun ati irun kiki ati adua ṣiṣe ati wiwa aforijin ati saara ṣiṣe ati ibọkun lọrun ẹru

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi wiwa ojo

O jẹ ẹniti maa nbeere fun ojo lori minbari nigbati o ba nṣe khutubah lọwọ, o si tun maa nbeere fun ojo yatọ si ọjọ jimoh O tun beere fun ojo ni igbati o joko si inu mọsalaasi, o si gbe ọwọ rẹ soke o si kepe Ọlọhun ti O biyi ti O gbọnngbọn Ohun ti wọn ha ninu adura rẹ nibi iwa ojo ni: Allaahummọs'qi ibaadaka wa bahaaimọka wan'shur rah'mọtaka wa ah'yi baladakal mọyyit (Olohun fun awon erusin Re ni omi mu, Olohun fun awon daaba re ni omi mu, Olohun fon ike re ka, Olorun bani ji ilu re to ti di oku), Allaahummọs'qinaa gaythan mugiithan mọriian mọriihan naafihan gayrọ doorin, haajilan gayrọ aajilin (Iwo Olohun ro ojo fun wa ni ojo ti yoo ba wa mu idaamu wa kuro, ti igbeyin re yoo si dara, ojo ti yoo mu ki ile o ruwe, ti yoo si se wa ni anfaani, ti ko nii ni wa lara, ro o fun wa laipe, ma se je ki o pe).

O si jẹ ẹniti o ṣe wipe ti o ba ti ri ẹsujo ati afẹfẹ wọn o ti ri i ni oju rẹ, yoo maa lọ yoo maa bọ, ti o ba ti wa rọ ojo oju rẹ o tuka

O si jẹ ẹniti maa nsọ ti o ba ti ri ojo pe: Allaahummọ sọyyiban naafihan (Olohun bani se ojo yii ni ohun ti yio wulo, ti yio se anfani) Yoo wa ka aṣọ ki ojo fi le kan ara rẹ Wọn wa bi i leere nipa rẹ: o si sọ pe: Toripe Ọlọhun sẹsẹ da a ni Nigba ti ojo pọ, wọn ni ki o ba awọn beere fun ki ojo wawo, o si beere rẹ fun wọn O sọ pe: Allaahummọ hawaalayna wa laa halayna, Allaahummọ halaz zirọọbi, wal aakaam, wal jibaal, wa butuunil aodiyah, wa manaabitish shajar (Iwo Olohun, awon ayika wa ni ki o maa ro o si ma se ro o le wa lori, je ki o maa ro sori awon ile giga ati awon oke keekeekee, ati si inu awon afonufoji ati sara awon itakun igi).

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi irun oju-ogun

Ninu ilana rẹ ni wipe ti ọta ba wa laarin rẹ ati qiblah yio to awọn musulumi si ẹyin rẹ ni saafu meji Yio wa kabara ti gbogbo wọn na o si kabara, lẹyinna ni wọn o rukuhu ti wọn o si gbe ori kuro papọ Lẹyinna ni saafu alakọkọ ti o tele e maa fi ori kan ilẹ, ti saafu ti o wa ni ipari si maa da oju kọ ọta, ti o ba ti wa dide lọ si rakaah eleekeji saafu ti o kẹhin maa fi ori kan ilẹ ni eemeji Lẹyinna wọn o dide wọn o si bọ si aaye saafu alakọkọ, ti saafu alakọkọ o si bọ si aaye wọn; ki ọla ti nbẹ fun saafu iwaju le baa maa jẹ ti ikọ mejeeji Atipe ki saafu keji naa o le ba ṣe iforikanlẹ mejeeji ti rakaah eleekeji pẹlu rẹ Ti o ba ti wa rukuhu awọn ikọ mejeeji a ṣe gẹgẹbi wọn ṣe ṣe ni akọkọ, ti o ba ti wa joko fun ataya, saafu ti o kẹhin maa fi ori kan ilẹ ni eemeji, wọn o si pada wa ba a nibi ataya, yio wa salamọ pẹlu wọn lapapọ Ti o ba wa wa ni ibiti kii ṣe agbegbe qiblah; nigba mii yio pin wọn si meji: ikọ kan maa da oju kọ ọta, ikọ kan maa ki irun pẹlu rẹ ọkan ninu ikọ mejeeji maa ki rakaah kan pẹlu rẹ, lẹyinna ni wọn a kuro ni ori irun wọn lo si aaye ikọ keji, ti ikọ keji naa maa wa si aaye wọn, ti wọn si maa ki rakaah keji pẹlu rẹ lẹyinna ni yio wa salamọ, ikọ kọọkan a wa da rakaah kọọkan pada lẹyin salamọ imaamu Atipe nigba mii yio ki rakaah kan pẹlu ọkan ninu awọn ikọ mejeeji, lẹyinna yio dide lọ fun eleekeji, ti ikọ naa maa ki rakaah kan nigbati oun si duro, ti wọn o si salamọ siwaju ki o to rukuhu Ikọ keji naa maa wa wa ti wọn o si ki raka'ah keji pẹlu rẹ, ti o ba ti wa joko fun ataya wọn o dide lati san raka'ah kan, ti oun nreti wọn nibi ataya, ti wọn ba ti wa ka ataya yio salamọ pẹlu wọn Nigba mii yio ki raka'ah meji pẹlu ọkan ninu awọn ikọ mejeeji ti yio si salamọ pẹlu wọn, ti ikọ keji naa si maa wa ti yio si ki raka'ah meji pẹlu wọn ti yio si salamọ pẹlu wọn Nigba mii yio ki raka'ah kan pẹlu ikọ kan ninu ikọ mejeeji, ti wọn o si lọ lai ni san nkankan Ti ikọ keji naa si ma wa ti yio si ki raka'ah kan pẹlu wọn ti wọn o si ni san nkankan, oun o wa ki raka'ah meji, ti awọn o si ki raka'ah kọọkan

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi ipalẹ oku mọ

Ilana rẹ ni o jẹ ilana ti o pe ju nibi ṣiṣe eto oku, ti o yatọ si ilana awọn ijọ yoku, ti o ko daada ṣiṣe si oku sinu ati si awọn ara ile rẹ ati awọn alasunmọ rẹ Alakọkọ rẹ ni bibẹwo loore-koore nigba aisan rẹ, ati riran an leti nipa ọjọ ikẹhin, ati pipa a laṣẹ pẹlu asọtẹlẹ ati tituuba, ati pipa ẹniti o ba wa pẹlu rẹ laṣẹ pẹlu ki o maa wi gbolohun laa ilaaha illalloohu si i ni ẹnu

O si jẹ ẹniti maa nyọnu ju ninu ẹda Ọlọhun si idajọ Ọlọhun ti o si maa npọ ni fifi ẹyin fun Un, o si sunkun latari iku ọmọ rẹ Ibrọọhiim lẹniti fi nkaanu rẹ, ti o si fi ṣikẹ rẹ, ti ọkan rẹ si kun fun yiyọnu si idajọ Ọlọhun ati didupẹ fun Un, ti ahọn rẹ naa si ko airoju pẹlu iranti Rẹ ati ẹyin Rẹ

O tun maa nsọ pe: Oju a maa da omi ọkan a si maa bajẹ atipe ao ni sọ nkankan tayọ ohun ti yio yọ Ọlọhun ninu

O si kọ kuro nibi imaa gba eti, ati imaa gbe ohun soke pẹlu igbe kike ati aaro sisun

Atipe ninu ilana rẹ ni ki o maa yara lati palẹ oku mọ lọ si ọdọ Ọlọhun, ati mimọ ara fun un ati fi fọ ọ mọ ati fifi aṣọ funfun si i lara

Atipe ninu ilana rẹ ni bibo oju oku ati ara rẹ, ati fifi ọwọ wọ oju rẹ mejeeji walẹ

Atipe nigba mii a maa fẹnu ko ori oku

O si maa npaṣẹ pẹlu wiwẹ oku ni ẹẹmẹta tabi ẹẹmarun tabi ju bẹ lọ ni ibamu si iwoye oluwẹ, o si maa npaṣẹ pe ki wọn lo kafura nibi iwẹ ti o ba gbẹyin

Ko si ki nwẹ ẹniti o ba ku si oju ogun, o si ma nbọ awọn awo ati irin kuro ni ara rẹ, o si maa n sin won ninu aso won ko si nii kirun si won lara.

O si tun paṣẹ wiwẹ ẹniti o gbe arami pẹlu omi ati sidiru, wọn o si sin in si inu aṣọ arami rẹ, o si kọ kuro nibi fi fin in ni lofinda ati bibo ori rẹ

O si tun jẹ ẹniti maa npa alamojuto oku wipe ki o ṣe daada pẹlu aṣọ ti yio fi sin in ki o si sin in pẹlu aṣọ funfun, o si kọ kuro nibi imaa fi owo ti o pọ lapọju ra aṣọ isinku

O si tun jẹ ẹniti o ṣe wipe ti aṣọ oku ba kere lati bo gbogbo ara rẹ yio bo ori rẹ, yio si fi koriko bo ẹsẹ rẹ mejeeji

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi irun kiki si oku lara

O jẹ ẹniti maa nki irun si oku lara ni ita masalaasi, nigba mii a maa ki i si i lara ninu masalaasi, sugbọn iyẹn kii ṣe ilana ti o dunni mọ

O si jẹ ẹniti o ṣe wipe ti wọn ba gbe oku wa ba a yio beere wipe: njẹ o ni gbese lọrun? Ti ko ba ni gbese lọrun yio ki irun si i lara, sugbọn ti o ba ni gbese lọrun ko ni ki irun si i lara, yio wa pa awọn saabe rẹ laṣẹ ki wọn o ki i si i lara

Nigbati Ọlọhun wa gba a laye o jẹ ẹniti maa nki irun si onigbese lara ti yio si ba a san gbese rẹ, ti yio si fi dukia rẹ silẹ fun awọn ti wọn o jẹ ogun rẹ

Ti o ba ti wa bẹrẹ si ni nki irun yio ṣe Alloohu Akbar yio si dupẹ fun Ọlọhun yio si fi ẹyin fun Un yio si ṣe adura, o jẹ ẹniti maa nkabara ni ẹẹmẹrin o si tun kabara ni ẹẹmarun

O jẹ ẹniti maa paṣẹ mimo adura kanga fun oku, ohun ti wọn ri ha ninu adura ti maa nṣe ni: Allaahummọg’fir lihayyinaa wa mọyyitinaa, wa sọgiirinaa wa kabiirinaa, wa dhakarinaa wa un’thaanaa, wa shaahidinaa wa gọọibinaa, Allaahummọ mọn ah’yaitahu minnaa fa ah’yihi alal is’laam, wa mọn tawaf’faytahu minnaa fa tawaf’fahu alal iimaan, Allaahummọ laa tah’rimnaa ajrọhu wa laa taf’tinnaa bah’dahu (Olohun forijin eniti o nsemi ninu wa ati oku wa, ati eniti o wa ati eniti ko lee wa, ati omo kekere inu wa ati agbalagba, ati okunrin inu wa ati obinrin inu wa, Olohun, eniti O ba da emi re si ninu wa, ba ni je ki o maa semi ninu esin Islam, eniti O ba pa ninu wa, ba ni pa a lori ini igbagbo, Olohun ma je ki a padanu esan re, Olohun ma je ki a sonu leyin iku re). Wọn tun ha ninu adura rẹ bakanna pe: Allaahummọg’fir lahu war’hamhu, wa haafihi, wah’fu han’hu, wa ak’rim nuzulahu, wa wa was’sih mud’khọlahu, wag’sil’hu bil’maahi wath’thal’ji wal barọdi, wa naq’qihi minal khọtọọyaa kamaa yunaqqọth thaobul abyadu minad’danasi, wa ab’dil’hu daarọn khọyrọn min daarihi, wa ah’lan khọyrọn min ah’lihi, wa zaojan khọyrọn min zaojihi, wa ad’khil’hul jannata wa ahiz’hu min hazaabil qọbri wa min hazaabin naar (Olohun ba ni forijin in, ki O si bani ke e, bani se amojukuro fun un, bani pon isokale re sinu saare re le, bani fe iho inu saare re fun un, bani fo o mo pelu omi ati yinyin ati omi ti o tutu, Olohun bani mo on kuro ninu ese gege bi a se maa n mo aso funfun kuro nibi egbin, Olohun bani fi ile to daaju ile re lo ropo fun un ati awon alabagbeere to dara ju aye re lo, ati aya ti o dara ju aya re lo, Olohun bani mu u wo alujanna, ba ni so o kuro nibi iya saare ati iya ina).

O jẹ ẹniti maa nduro nibi ori ọkunrin, ati ni aarin meji obinrin

O si jẹ ẹniti maa nkirun si ara oponlo, ko si ki nki irun si ara ẹniti o ba pa ara rẹ, ati ẹniti o ba ji ninu ọrọ oju-ogun

O si ki irun si ara arabinrin ti o wa lati idile Juhaynah eleyi ti o lẹ loko zina

O si ki irun ti maa nki si oku lara fun Najaashiy, ko si si ninu ilana rẹ ki o maa ki irun si gbogbo oku ti o ba ku lẹyin lara

Atipe ninu ilana rẹ nipe ti irun kiki si oku lara ba bọ mọ ọn lọwọ yio ki i si ara saare

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi sisin oku ati awọn nkan ti o sorọ mọ ọn

O jẹ ẹniti o ṣe wipe ti o ba kirun si oku lara yio tele e de itẹ lẹniti nrin ni iwaju rẹ Wọn ṣe e ni sunnah fun ẹniti o ba ngun nkan ki o wa lẹyin rẹ Atipe ti o ba jẹ ẹniti nrin yio sun mọ ọn, ninu ki o jẹ ẹyin abi iwaju, tabi ni ẹgbẹ ọtun tabi ni ẹgbẹ osi, o si maa npaṣẹ yiyara pẹlu ẹ

O si jẹ ẹniti kii joko titi ti wọn o fi gbe e si ilẹ

O si paṣẹ didide fun oku nigbati wọn ba gbe e kọja, o si fi ẹsẹ rinlẹ lati ọdọ rẹ wipe o joko

Atipe ninu ilana rẹ nipe ko ki nsin oku nigbati oorun ba nyọ, ati nigbati o ba nwọ, ati nigbati oorun ba wa ni atari

Atipe ninu ilana rẹ lahadi wa, ati ki saare o jin, ati ki o fẹ nibi ori oku ati ẹsẹ rẹ mejeeji

O si tun maa nbu iyepẹ si oku nigbati wọn ba sin in lati ibi ori rẹ lẹẹmẹta

O si tun jẹ ẹniti o ṣe wipe ti o ba ti pari sinsin oku tan yio duro sibi saare rẹ ti yio si beere idurosinsin fun un, o si pa awọn saabe rẹ laṣẹ pẹlu bẹẹ

Ko si ki njoko lati kan nkan si ori saare, ko si tun ki npe gbolohun kankan si oku lẹnu

Atipe ninu ilana rẹ ni gbigbe titufọ oku silẹ, atipe o tun maa nkọ funni kuro nibẹ

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – ni itẹ ati ibanikẹdun

Ko si si ninu ilana rẹ ki saare o maa ga, ati mimọ ọn ati pipo o lẹrọfọ, ati mimọ agọ le e lori

Atipe o gbe Aliyy dide lọ si Yaman wipe ko gbọdọ fi ere Kankan silẹ afi ki o run un yanga-yanga, atipe ko si gbọdọ fi saare ti o ga Kankan silẹ afi ki o sọ ọ di pẹrẹsẹ, ohun ti o si jẹ sunnah rẹ ni sisọ gbogbo saare ti o ba ga di pẹrẹsẹ

Atipe o kọ ki wọn maa rẹ saare, ati ki wọn mọ nkan si i lori, ati ki wọn kọ nkan si i lara

O si tun maa njẹki ẹniti o ba fẹ mọ saare rẹ o da a mọ pẹlu gbigbe okuta si i

O si tun kọ kuro nibi imaa sọ awọn saare di masalaasi, ati imaa tan atupa si ori rẹ, o si ṣẹbi le ẹniti o ba ṣe bẹẹ

O si tun kọ kuro nibi imaa ki irun si saare lara, atipe o si tun kọ kuro nibi sisọ saare rẹ di ọdun

Atipe ninu ilana rẹ nipe ki wọn ma yẹpẹrẹ saare ki wọn si ma gun un lori, ki wọn si ma joko lori ẹ, ki wọn si ma rọgbọkun le e lori, ki wọn si ma gbe e tobi

O jẹ ẹniti maa nbẹ saare awọn saabe rẹ wo lati ṣe adura fun wọn ati lati toro aforijin fun wọn O si ṣe e ni sunnah fun olubẹwo ki o maa sọ pe: As salaamu alaykum yah ahlad- diyaar minal mu'miniina wal muslimiin, wa innaa in sha Allahu bikum laahiquun, nas'alu llaha lanaa wa lakumul aafiyah...... Alaafia Ọlọhun ki o maa ba yin ẹyin ara itẹ ninu ẹyin olugbagbọ ododo ati musulumi, ati pe awa naa nbọ wa pade yin pẹlu ogo Ọlọhun, awa tọrọ alaafia lati ọdọ Ọlọhun fun yin ati fun awa naa. Atipe ninu ilana rẹ ni imaa ba awọn ara ile oku kẹdun, ko si si ninu ilana rẹ ki o maa ko awọn eeyan jọ fun ibanidaro ti wọn wa maa ka Al'qurani, kii ṣe e nibi saara ati ibiti o yatọ si i

Atipe ninu ilana rẹ nipe awọn ara ile oku kii la wahala ina-dida bọ ara wọn lọrun, bi kii ṣe wipe awọn eeyan ni wọn maa se ounjẹ fun wọn

# Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi zakah ati saara

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi zakah

Ilana rẹ ninu ẹ ni ilana ni o pe ju nipa asiko rẹ ati iye rẹ ati odiwọn ti zakah wọ Ati ẹniti o jẹ dandan fun ati ibiti a maa npin in si, o ṣe akiyesi anfaani awọn ti wọn ni dukia ati anfaani awọn alaini O si ṣe e ni dandan ninu dukia awọn abọrọ ohun ti yio to awọn talika lai ni ipalara Kankan ninu

Atipe ti o ba mọ wipe ẹnikan wa ninu awọn ti wọn ni bukaata si i yio fun un, ti ẹniti ko mọ nipa ipo ti o wa ba beere ninu ẹ, yio fun un lẹyin igba ti o ba ti jẹ ki o ye e wipe abọrọ Kankan o ni ipin ninu ẹ ati ẹniti o ba ni agbara lati ṣe iṣẹ

Ninu ilana rẹ si ni ki o maa pin in fun awọn ti wọn ni ẹtọ si i ninu ilu ti dukia naa wa, eyiti o ba wa ṣẹku ninu ẹ wọn o gbe e lọ ba a yio si pin in

Ko si ki in ran wọn lọ si ọdọ ẹnikankan ayaafi awọn ti wọn ba ni dukia ti o fi oju han ninu awọn ẹran ti a nsin ati awọn irugbin ati awọn eso

O si maa n ran ẹniti maa se odiwọn nkan lọ si ọdọ awọn ọlọpẹ lati fi oju diwọn awọn eso ara ọpẹ wọn ati eso inab, ti yio si wo iye apo ti yio mu jade, ti yio wa si isiro zakah wọn pẹlu odiwọn rẹ, nti njẹ Al'khar'su ni fifi-oju bu nkan Ko si si ninu ilana rẹ ki o maa gba a ninu ẹṣin ati ẹru, ati ibaaka ati kẹtẹkẹtẹ, ati awọn ewebẹ, ati awọn eso eleyi ti wọn o ki n wọn ti wọn o si ki n fi pamọ, ayaafi eso inab ati dabinu, ti ko si ki n ṣe iyatọ laarin tutu ati gbigbẹ rẹ Ko si si ninu ilana rẹ ki o maa gba a ninu ẹṣin ati ẹru, ati ibaaka ati kẹtẹkẹtẹ, ati awọn ewebẹ, ati awọn eso eleyi ti wọn o ki n wọn ti wọn o si ki n fi pamọ, ayaafi eso inab ati dabinu, ti ko si ki n ṣe iyatọ laarin tutu ati gbigbẹ rẹ

Ko si si ninu ilana rẹ ki o maa gba awọn to ni ọla ju ninu awọn dukia, bi kii ṣe awọn to wa laarin meji

O jẹ ẹniti maa nkọ fun ẹniti o ba ṣe saara ki o ra saara rẹ pada, o si tun ṣe e lẹtọ fun abọrọ ki o jẹ ninu ẹ nigbati talaka ba fi tọrẹ fun un

O si jẹ ẹniti maa njẹ gbese lori saara nigba mii fun anfaani awọn musulumi, o si tun maa beere fun yiya saara lọwọ awọn to ni i nigba mii

O si jẹ ẹniti o ṣe wipe ti ẹnikan ba mu zakah wa yio ṣe adura fun un, yio si sọ pe: Allaahummọ baarik fiihi wa fi ibilihi, nigba mii yio sọ pe: Allaahummọ sọlli alay'hi

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi zakaatul fitri

O ṣe zakaatul fitri ni dandan sọọhun kan ninu dabinu, tabi sọọhun kan ninu jeero tabi sọọhun kan ninu aqit tabi sọọhun kan ninu zabiib

Atipe ninu ilana rẹ ni ki o yọ ọ siwaju irun ọdun O sọ pe: Ẹniti o ba yọ ọ siwaju irun, oun ni zakaah ti wọn tẹwọgba, ẹniti o ba wa yọ ọ lẹyin irun, saara kan ninu awọn saara lo jẹ

Atipe ninu ilana rẹ ni ki o sẹsa awọn alaini pẹlu rẹ, ko si ki npin in fun awọn iran mẹjọ ti a maa npin zakaah dukia fun

Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi saara aṣegbọrẹ

O jẹ ẹniti fi nṣe saara ju ninu awọn eeyan pẹlu ohun ti o wa ni ikapani rẹ , o si jẹ ẹniti ohun Ọlọhun ba fun un kii pọ loju rẹ, ko si ki nfi oju kere rẹ

O si jẹ ẹniti o ṣe wipe ẹnikankan o ni beere nkan ni ọdọ rẹ ayaafi ki o fun un, o kere ni abi o pọ

Atipe idunnu rẹ si ohun ti o ba fun eeyan tobi ju idunnu ẹniti ngba a pẹlu ohun ti o gba lọ

O jẹ ẹniti o ṣe wipe ti ẹniti o ni bukaata kan ba wa ba a yio gbe e lori ara rẹ, nigba mii pẹlu ounjẹ rẹ, nigba mii pẹlu aṣọ rẹ

Atipe o jẹ ẹniti maa ṣe amojukuro fun ẹniti o ba ropọ mọ ọn

O jẹ ẹniti maa npin ọrẹ ati saara rẹ ni oniranran, nigba mii yio jẹ ẹbun, nigba mii yio jẹ saara, nigba mii yio jẹ ọrẹ, nigba mii yio jẹ rira nkan ti yio si fun ẹniti o nta a ni owo ati ọja ti o ra, nigba mii yio ya nkan ti yio si da ohun ti o ju u lọ pada, nigba mii yio gba ẹbun ti yio ṣe adapada rẹ pẹlu ohun ti o ju u lọ

# Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi aawẹ gbigba

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi aawẹ ramadan

Ninu ilana rẹ ni wipe ko ni wọ inu aawẹ Ramadan ayaafi pẹlu riri oṣu ti o daju, tabi pẹlu ijẹri olujẹri, ti ko ba wa si riri oṣu ti ko si si ẹlẹri yio ka oṣu sha'abaan ti yio pe ọgbọn

O si jẹ ẹniti o ṣe wipe ti esujo ba kọdi riri oṣu rẹ ni oru ọgbọn, yio ka sha'abaan ti yio pe ọgbọn, ko si ki ngba aawẹ ni ọjọ ti kurukuru ba bo oju sanmọ

Atipe ninu ilanaa rẹ ni ki o jade kuro ninu oṣu aawẹ pẹlu jijẹri awọn meji

O jẹ ẹniti o ṣe wipe ti ẹlẹri meji ba ti jẹri pẹlu riri i (oṣu) lẹyin igbati asiko ọdun ba ti kọja, yio tunu yio si pa wọn laṣẹ pẹlu wipe ki wọn tunu, yoo si ki irun yidi lẹyin ọjọ keji ni akoko rẹ

O jẹ ẹniti maa nyara ṣinu, ti o si maa ṣeni ni oju-ọyin si i, o si maa njẹ saari o si tun maa ṣeni ni oju-ọyin si i, o si maa nlọ ọ lara o si maa nṣeni ni ojukokoro sibi lilọ ọ lara

O jẹ ẹniti maa nṣinu siwaju ki o to kirun, o si maa ṣinu pẹlu awọn dabinu tutu, ti ko ba wa ri, yio lo eso dabinu tamru, ti ko ba wa ri, yio lo gẹẹ omi

O si tun jẹ ẹniti maa nsọ nigbati o ba fẹ ṣinu pe: Zahabaz zọmọhu, wab'tallatil uruuq,wa thabatal aj'ru in shaa'al loohu tahalaa (Ongbe ti lo bayii, awon isan si ti tutu, laada si ti fi ese mule ti Olohun ba fe)

O si tun wa ninu ilana rẹ ninu oṣu Ramadan pipọ ni ṣiṣe awọn oniranran ijọsin, Jubriil si jẹ ẹniti maa nka Al'qurani pẹlu rẹ ninu oṣu Ramadan

O si tun jẹ ẹniti maa npọ ni saara ṣiṣe pẹlu daada ṣiṣe ati titọ Al'qurani ati irun kiki ati ṣiṣe iranti ati ṣiṣe atipo ni ile Ọlọhun ninu rẹ (oṣu Ramadan)

O si tun jẹ ẹniti maa ṣẹsa rẹ pẹlu awọn ijọsin ti kii ṣẹsa oṣu mii pẹlu rẹ, debi pe a maa gba agbayipo ninu ẹ nigba mii, ti o si maa nkọ fun awọn saabe rẹ kuro nibi agbayipo, o si pepe lọ sibi saari jijẹ ninu ẹ

Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi nkan ti o ṣe leewọ ati nkan ti o ṣe lẹtọ ninu aawẹ

O kọ fun alaawẹ kuro nibi iṣekuṣe ati ariwo pipa ati eebu bibu, ati imaa fesi fun eebu, o wa pa a laṣẹ ki o sọ fun ẹniti o ba bu u pe: dajudaju emi alaawọ ni mi

O si ṣe irin ajo ninu oṣu Ramadan ti o si gba aawẹ ti o si tun ṣinu, o wa sa awọn saabe rẹ lẹsa pẹlu eyiti o ba wu wọn ninu alamọri mejeeji

O si tun jẹ ẹniti maa npa wọn laṣẹ pẹlu siṣinu nigbati wọn ba ti sunmọ ọta

Ko si si ninu ilana rẹ ṣiṣe odiwọn irin ajo ti alaawẹ le tunu nibẹ

Awọn saabe jẹ ẹniti o ṣe wipe ti wọn ba ti gbera irin ajo wọ o nii gba aawẹ laini woye si kikọja awọn ibugbe Ti wọn si maa sọ wipe iyẹn ni ilana ati sunnah rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a.

O jẹ ẹniti alufajari maa nyọ ba a ti yio si jẹ ẹniti o ni janaba lara latari wipe o sunmọ awọn arale rẹ, ti yio si wẹ lẹyin ti alufajari ba yọ ti yoo si tun gba aawẹ

O si tun jẹ ẹniti maa fi ẹnu ko ẹnu awọn kan ninu awọn iyawo rẹ ti o si wa lẹniti o gba aawẹ Ramadan

O si tun jẹ ẹniti maa nrun pako ti yio wa lẹniti o gba aawẹ, o si maa nfi omi yọ ẹnu o si tun maa fin omi si imu ti yio si wa lẹniti o gba aawẹ, o si tun maa da omi si ori rẹ ti yio si wa lẹniti o gba aawẹ
Atipe ninu ilana rẹ nipe o maa ngbe sisan aawẹ pada kuro fun ẹniti o ba ṣeesi jẹ tabi mu
O si ṣe idẹkun fun alaisan ati arinrin-ajo lati ma gba aawẹ ki wọn si san an pada, pẹlu oloyun ati ẹniti nfun ọmọ lọyan ti wọn ba npaya lori ẹmi ara wọn bakannaa

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – ninu aawẹ afinufindọ gba

Ilana nibe ni ilana ti o pe ju wa, ati ohun ti o tobi ju lati debi erongba ti o si rọrun ju fun ẹmi
O jẹ ẹniti maa ngba aawẹ titi ti wọn fi maa nsọ pe: ko ni tunu, o si tun maa tunu titi ti wọn fi maa nsọ pe: ko ni gba aawẹ
Ko si gba oṣu Kankan pe ri yatọ si Ramadan, ko si ki npọ ni aawẹ gbigba ninu oṣu Kankan to bi o ṣe maa npọ ninu oṣu Sha'baan Ko si kin jade kuro ninu oṣu Kankan titi ti yio fi gba aawẹ  ninu ẹ
Atipe ninu ilana rẹ ni kikọ ṣisesa ọjọ Jimoh pẹlu aawẹ, o si maa nmu gbigba aawẹ Monday ati Thursday ni ọkunkundun
Ko si ki ntunu ni awọn ọjọ inu oṣu oju-ọrun kọọkan (13/14/15) nigbati o ba wa ni ile ati nigbati o ba wa ni irin-ajo, o si tun maa nṣeni ni ojukoro gbigba aawẹ rẹ
O si tun jẹ ẹniti maa ngba aawẹ ọjọ mẹta ni ibẹrẹ gbogbo oṣu
O si sọ nibi aawẹ mẹfa oṣu shawwal pe: Gbigba aawẹ rẹ pẹlu Ramadan ṣe deede aawẹ ọdun kan
O si tun maa mu gbigba aawẹ ọjọ kẹwa oṣu muharam ni ọkunkundun ju awọn ọjọ yoku lọ, o si sọ pe gbigba aawẹ rẹ maa npa ẹṣẹ ọdun ti o rekọja rẹ ni
O si tun sọ nibi ọjọ Arafa pe: Gbigba aawẹ rẹ maa pa ẹṣẹ ọdun ti o rekọja ati eyiti o nbọ rẹ, ninu ilana rẹ si ni imaa tunu ni ọjọ Arafa ti o ba wa ni Arafa Ko si si ni ilana rẹ ki o maa fi gbogbo ọdun gba aawẹ, amọ o sọ pe: Ẹniti o ba gba aawẹ gbere, ko gba aawẹ ko si tunu Nigba mii yio daniyan aawẹ afinufindọ gba lẹyinna yio si ja a, o si maa nwọle tọ awọn ara-ile rẹ ti yio si sọ pe: njẹ nkankan nbẹ lọdọ yin ni jijẹ bi? Ti wọn ba sọ pe: rara, yio sọ pe: dajudaju emi ti ngba aawẹ O sọ pe: Ti wọn ba pe ẹnikẹni yin si ibi ounjẹ, ti o si jẹ ẹniti o gba aawẹ ki o ya sọ pe: dajudaju emi alaawẹ ni mi

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - nibi ṣiṣe atipo ni ile Ọlọhun

O jẹ ẹniti maa ṣe atipo ile Ọlọhun ni ọjọ mẹwa ti o gbẹyin oṣu Ramadan titi Ọlọhun fi pa a, o si fi i silẹ ni ẹẹkan, ti o si san an ninu oṣu shawwaal
O si tun ṣe atipo ile Ọlọhun ni mẹwaa akọkọ ni eekan soso, lẹyin naa ni o ṣe e ni mẹwaa ti aarin, lẹyin naa ni o ṣe e ni mẹwa ti o gbẹyin lẹniti n wa oru laylatul-qad'r lẹyin naa ni o wa han si i wipe inu mẹwaa ti o gbẹyin lo wa, o si waa dunni mọ ṣiṣe atipo ile Ọlọhun titi ti o fi lọ pade Ọba rẹ ti O biyi ti O si gbọnngbọn
Ko si ṣe atipo yi ri ayaafi pẹlu aawẹ O si maa ni ki wọn ba oun ta atibaba ti wọn o si ba a ta a si masalasi lati dawa nibẹ O si jẹ ẹniti o ṣe wipe ti o ba gbero lati ṣe atipo ile Ọlọhun yio ki irun al'fajari lẹyin na ni yio si wọle sibẹ"
O si tun jẹ ẹniti o ṣe wipe ti o ba ṣe atipo ile Ọlọhun, wọn yio ba a gbe ibusun rẹ si ibiti o ti nṣe atipo na, o si jẹ ẹniti maa nwọ inu atibaba rẹ ni oun nikan soso
Ko si ki nwọ inu ile rẹ ayaafi lati lọ gbọ bukaata ti ọmọniyan maa ngbọ
O si jẹ ẹniti maa n yọ ori rẹ jade si yara iya wa Aaisha ti yio si ba a ya irun rẹ ti o (Aaisah) si jẹ ẹniti n ṣe nkan oṣu lọwọ
Awọn kan ninu awọn iyawo rẹ si maa nbẹ ẹ wo nigba ti o nṣe atipo lọwọ, ti o ba ti wa nlọ yio dide pẹlu rẹ lati sin in, iyẹn maa nṣẹlẹ ni alẹ"
Ko si ki n fi ara ro ọkankan ninu awọn iyawo rẹ nigbati o ba nṣe atipo lọwọ yala pẹlu fifi ẹnu ko o lẹnu ni tabi eyiti o yatọ si i
O maa ṣe atipo ile Ọlọhun fun ọjọ mẹwa ninu ọdun kan, nigbati o wa di ọdun ti Ọlọhun mu ẹmi rẹ sọdọ, o ṣe atipo fun ogunjọ

# Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi Haj ati Umurah

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi Umurah

O ṣe Umurah ni ẹẹmẹrin; akọkọ rẹ ni: Umuran Udaybiyyah, awọn oṣẹbọ si kọdi rẹ lati wọle, ni o ba du ẹran ti o si tun fari ni aaye ti wọn ti kọdi rẹ, o si tun bọra silẹ
Ẹlẹẹkeji ni: Umurah Adapada; leyiti o jẹ wipe o san an pada ni ọdun ti o tẹle e
Ẹlẹẹkẹta ni: Umurah rẹ ti o dapọ mọ Haj rẹ
Ẹlẹẹkẹrin ni: Umurah rẹ ti o ṣe lati aaye kan ti a npe ni Jih'roonah
Ko si si ninu awọn Umurah rẹ ti o ṣe Umurah kan ti o jade kuro ni Makkah, bi kii ṣe wipe gbogbo rẹ patapata o ṣe e lẹniti nwọle si Makkah ni

Wọn o si ri ha lati ọdọ rẹ wipe o ṣe Umurah ninu ọdun kan ju ẹẹkan soso lọ, ko si ṣe Umurah ninu ọdun kan ni ẹẹmeji
Atipe gbogbo Umurah ti o ṣe si waye ninu awọn oṣu Haj
O sọ pe: Umurah kan ninu Ramadan ṣe deede Haj

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi Haj

Nigbati wọn ṣe Haj ni ọranyan o tara sasa lati ṣe e lai si idaduro Kankan, ko si ṣe ju Haj kan lọ, o si ṣe Haj lẹniti o gbe Arami rẹ papọ mọ Umurah
O si wo inu iṣẹ Haj lẹyin irun zhuri lẹyinna ni o wa ṣe labbaika ti o si sọ pe: Labbaikal laahummo labbaik, labbaika laa sheriika laka labbaik, innal amda, wan ni'imata, laka wal mul'k, laa sheriika lak. O si gbe ohun re soke pẹlu gbolohun LABBAEKA naa titi ti awọn saabe rẹ fi gbọ ọ, o si pa wọn laṣẹ pẹlu aṣẹ Ọlọhun wipe ki wọn gbe ohun wọn soke pẹlu rẹ, o si dunni mọ ṣiṣe LABBAEKA rẹ, ti awọn nṣe afikun gbolohun mii sinu gbolohun yi ti wọn yọ kuro nibẹ ti ko si kọ fun wọn O si sa awọn saabe rẹ lẹsa gbigbe Arami pẹlu eyikeyi ti o ba wu wọn ninu awọn iran gbigbe arami mẹta ti a ni, lẹyinna ni o gba wọn ni iyanju nigbati o sunmọ Makkah wipe ki ẹniti ko ba fa ẹran adaya lọwọ o sọ arama Haj ti o gbe ati arami dida Haj papọ mọ Umurah ti o gbe di Umurah nikan Lẹ́yìn náà nígbà tí wọ́n sunmọ Mẹka, o pe wọn sibi pe ki wọn o sọ hajj wọn ati kirọọnu wọn di umurah fun ẹni tí ko ba ni ẹran adaaya
"ori gaari ni o ti se hajj rẹ, ko se e ninu gaari ti o ni atibaba lori, ti ounjẹ ati nkan igbadun rẹ si wa ni abẹ rẹ.
Nigbati o wa de Makkah o paṣẹ wipe gbogbo ẹniti ko ma mu ẹran adaya dani ki o sọ ọ di Umurah ki o bọra kuro ninu aṣọ arami rẹ, ẹniti o ba si mu ẹran adaya dani ki o wa ninu aṣọ arami rẹ, lẹyinna ni o wa lọ titi ti o fi de aaye kan ti a npe ni Dhi Tọwa, o si sun ibẹ ni oru aiku (Sunday) ni ọjọ kẹrin ti o rekọja ninu oṣu Dhul hijjah ti o si ki irun asunba nibẹ, lẹyinna ni o wẹ ni afẹmọju rẹ, o si wọ Makkah ni ọsan lati ibi oke rẹ lati As-saniyyatul Ul'yaa eleyi ti o wa ni oke “OKE AL'HAJUUN” Nigbati o de masalasi o kọri si ibi ile Ọlọhun, ko si ki irun ti a maa nfi ki masalasi Nigbati o wa de ibiti okuta dudu wa o fi ọwọ kan an, ti ko si ba awon eeyan difunfun lori ẹ, lẹyinna ni o gba apa ọtun rẹ, ti o si gbe ile si apa osi rẹ, ko si ṣe adua Kankan nibi ẹnu-ọna, bakanna ni ko ṣe e ni abẹ ọsọrọ, ko si tun ṣe e lẹyin kahbah ati nibi awọn origun rẹ Atipe wọn ha lati ẹnu rẹ wipe o maa nṣe adura yi laarin origun mejeeji (rukunul yamaani ati hajarul aswad): Robbana aatina fid duniya asanatan wa aakhirati asanatan wa qina adhaaban naar."Olohun wa se daada fun wa ni aye ki o si se daada fun wa ni ojo ikehin ki o si lawa kuro ninu iya ina". Ko si ṣe adayanri iranti Kankan fun rirokirika ile Ọlọhun yatọ si eleyi
O si yara rin nibi tawaafu re yi, nibi awọn ipooyi mẹta akọkọ, o si jẹ ẹniti maa nyara rin, ti o si maa sun awọn igbesẹ rẹ mọ ara wọn, o si tun ti aṣọ idabora rẹ bọ abẹ abiya rẹ ti o si eti rẹ mejeeji de ọkan ninu awọn ejika rẹ mejeeji ti o si tun yọ ejika keji silẹ
Gbogbo igba ti o ba ti de ibi ti okuta dudu wa yio na ika si i tabi ki o fi ọpa rẹ kan an ti yio si pọn ọpa naa la, ti yio wa sọ pe: Alloohu Akbar
O si tun fi ọwọ kan Ar'ruknul Yamaaniy, ko si pọn ọn la, ko si tun pọn ọwọ rẹ nigbati o fi kan an
Nigba ti o si pari Tawaf {irọkirika ile Ọlọhun to nṣe} o dari si ẹyin maqaamu Ibrahim, o si ka gbolohun pe "WATTAKHISUU MIN MAQAAMI IBRAAHIIMA MUSALLAA" kete to kaa tan lo ki irun nafila raka meji ti maqaamu si wa laarin rẹ ati ile Ọlọhun (kaaba) O si ka awọn Surat afọmọ mejeeji (eyi ni kul yaa ayyuhal kaafiruun ati qul huwwallaahu ahad) lori irun naa lẹyin igba ti o ti ka suratul faatihat Nigba ti o si pari irun rẹ o lọ si ibi ti okuta dudu naa wa (hajarul aswad) o si fi ọwọ ra a lara Lẹyin eyi o jade kuro laaye yii lọ si oke Safaa nigba ti o rin sunmọ ọn tan, o ka gbolohun Ọlọhun pe: Innas sofa wal marwata min sha'aairil laah.Dajudaju Safa ati Marwa ninu awon aaye ami Olohun lo wa. Maa bere pelu ohun ti Olohun bere pelu e. Lẹyin naa o gun un debi ti o fi nwo ile Ọlọhun (kaabah) lọọkan lo ba doju rẹ kọ ọ, o si ṣe gbolohun imọ Ọlọhun lọkan, o si gbe titobi fun Un pẹlu, o sọ wipe: Laailaaha illa-l-laahu wahdahuu laa sharika lahu, lahul mulku walahul hamdu wahuwa alaa kulli shay'in Qadeer Laailaaha illa-l-laahu wahdahuu, anjaza wa'dahu wanasara abdahu wa a'azza jundahu wahazamal ahzaaba wahdahu (Ko si olujosin fun Kankan ayaafi Alloohu nikansoso ko si akegbe fun Un, ti E ni ola nse, ti E sini eyin nse, Oun sini oba ti o ni ikapa lori gbogbo nkan, a nseri pada, a nwa tutuuba, a nse ijosin fun Olohun, a si nfi eyin fun un, Olohun sika adehun Re, O si ran eru Re lowo, O si segun awon Al-A'azaab ni Oun nikan). Lẹyin naa o tọrọ adua laarin awọn gbolohun yii. O si ka gbolohun to kọja yii lẹẹmẹta
Lẹyin naa o sọkalẹ to si n rin lọ si Marwat. Nigba ti ẹsẹ rẹ mejeeji ti wa bọ sinu ọgbun to nbẹ laarin oke mejeeji yii, o sare pọṣẹṣẹ titi o fi rekọja ọgbun naa ti o si ti gun un soke, o bẹrẹ si ni rin pada, eleyii ni laarin aye-ami ti a ti fi awọ ewe da yatọ lode oni, o si tun mu iṣẹ aarin safa ati marwat pọn lẹni to nrin, lẹyin naa o pada pari iṣẹ naa lẹni to gun nkan ọgun, iyẹn nigba ti awọn eniyan ti ṣuru bo o.
O si jẹ ẹnikan to ṣe pe gbogbo igba ti o ba ti de oke Marwat yoo gun un, yoo doju kọ ibudojukọ (qiblat ile Ọlọhun) bẹẹ yoo gbe titobi fun Ọlọhun yoo si ṣe E laṣo, yoo si ṣe gẹgẹ bi o ti ṣe l'ori oke Safa

Nigba ti o pari iṣẹ irọkirika rẹ lori oke Marwat, o pa gbogbo ẹni ti ko mu ẹran adaaya rẹ lọwọ pe ki wọn o bọra silẹ patapata lọranyan laisi ibuyẹ kankan fun wọn, laisi fi ti iru hurumi ti wọn gbe ṣe, ki ba jẹ ẹni ti o gbe aniyan ṣiṣe hajji ati umrat papọ ni o tabi ẹni ti o gbe aniyan hajji nikan.
ṣugbọn oun ko bọra silẹ nitori ẹran adaaya rẹ to ti mu lọwọ. O si sọ wipe: Ka ni mo mọ tẹlẹ ni, mi o ba ma fa ẹran adaaya mi dani lati ile, nba kan sọ gbogbo iṣẹ ti mo ṣe yii di umrat nii. O si ṣe adua aforijin lẹẹmẹta fun awọn ti wọn yoo fa irun wọn. Sugbọn awọn ti wọn yoo ge irun ti wọn, o ṣadua naa fun wọn lẹẹkan pere. O si n kirun fun awọn musulumi ni gbogbo igba ti o lo n'ilu Makkah titi to fi di ọjọ ipọnmirẹngbẹ (iyẹn ọjọ kẹjọ oṣu Dhul-Hijjah) to si nge irun kuru ni aye to mule si nibẹ ni ẹyin ilu makkah
Nigba ti o wa di ọjọ ipọnmirẹngbẹ ni asiko iyalẹta ọjọ naa, oun ati awọn ti wọn wa pẹlu rẹ doju irin wọn kọ agbegbe Mina. Lasiko yii ni gbogbo awọn ti wọn ti bọra silẹ tẹlẹ bẹrẹ si maa gbe aniyan hajji lọtun lati ibudo wọn ti wọn si nwọ aṣọ hurumi wọn. Nigba ti o de Mina o tẹdo sibẹ o si ki irun aila ati alaasari nibẹ. Koda o sunbẹ mọju. Nigba ti oorun si yọ ni aarọ ọjọ keji, o gbera kuro nibẹ lọ si Arafat. A ri ninu awọn sahabe rẹ ẹni ti o n ṣe labbayka, o si nbẹ ninu wọn ẹni ti o n ṣe gbolohun igbọlọhuntobi. Gbogbo rẹ naa ni anabi ngbọ sibẹ ko kọ fun ẹnikẹni wọn {Nigba ti O de'bẹ} O rii pe wọn ti kọ ipagọ olori rogodo kan ti Oun pa laṣẹ lati kọ si agbegbe Namirat sibẹ. Namirat kii ṣe ara Arafat rara ṣugbọn ilu kereje kan to bọ apa iyọ-oorun Arafat lo jẹ - bayii ni O ṣe pagọ sibẹ titi to fi di igba ti oorun yẹ'tari, nigba yii lo wa paṣẹ pe ki wọn lọ fa rakunmi to njẹ Alqaswaa wa. Wọn faa de bẹẹ ni wọn si gbe gaari si i lẹyin. Lẹyin eyii o mu irin pọn titi to fi de aarin afonifoji kan naa to nbẹ lagbegbe Uranat {ibẹ lo ti duro} Bẹẹ lo ba ṣe khutubah (ibanisọrọ) kan ṣoṣo to lagbara fun awọn eeyan pẹlu bi o ṣe wa lori nkan'gun rẹ. Ninu khutubah yii lo ti ṣalaye to si fi awọn ipilẹ ẹsin Isilaamu rinlẹ ṣinṣin bẹẹ lo si bi gbogbo ipilẹ imorogun pọ m'Ọlọhun ati awọn iṣesi to tako awọn ẹkọ Isilaamu wo patapata O fi rinlẹ ninu rẹ (khutubah naa) bi awọn nkan eewọ ti gbogbo awọn ilana ẹsin panupọ l'ori jijẹ eewọ rẹ ṣe jẹ bẹẹ, lo si pa awọn iṣesi ti ko ba ẹkọ Isilaamu ati owo-ele eleyii to tako ẹkọ Isilaamu {eyi ti awọn keferi igba naa maa ńṣe) rẹ patapata. {O paa rẹ pe lati aya-ọjọ naa lọ} oun ti gbẹṣẹ le e. O pa wọn laṣẹ ṣiṣe daadaa si awọn obinrin bẹẹ lo pa ijọ yii laṣẹ nipa jijijọ dirọ mọ tira Ọlọhun. Koda o gba ọrọ lẹnu wọn o si fi Ọlọhun ṣe ẹlẹri le'wọn l'ori pe dajudaju oun mu'ṣẹ Ọlọhun de ogongo, oun ti pe iwọ Ọlọhun bẹẹ oun si ti ṣalaye ṣe waasu fun gbogbo aye
Nigba ti o pari ibanisọrọ naa o pe Bilaal pe ki o pe'run, o si pe e, lẹyin naa o gbe irun duro, oun (anabi) ba si ki irun aila ni iduro meji pere ti o si keu jẹjẹ lori mejeeji, ọjọ naa si jẹ ọjọ jimọ.
Lẹyin (igba to ki i tan) oun (bilaal) tun gbe irun duro, o si ki irun alaasari naa ni iduro meji pere, bo tilẹ ṣe pe awọn eniyan to ngbe ilu makkah naa wa pẹlu rẹ sibẹ ko pa wọn laṣẹ lati ki irun tiwọn pe, ko si ni ki wọn ma ki irun mejeeji naa (aila ati alaasari) papọ lasiko kan naa.
Nigba ti o ki irun rẹ tan, o gun rakunmi rẹ, o si tẹ siwaju titi to fi de aye to pada duro si patapata lọjọ naa. Nigba ti awọn eniyan si nṣe iye meji nipa awẹ gbigba rẹ lọjọ arafat naa, iyawo rẹ Maymunat fi wara ṣọwọ ranṣẹ sii lasiko to ṣi wa laaye ibi to duro si O gba a, o si mu ninu rẹ ti awọn eniyan si nwo o O duro sibi abẹ oke arafat naa nibi ti awọn okuta ti ko tobi ju wa nibẹ O si doju kọ qiblat (ibudojukọ kirun) O si fi ọwọ awọn eniyan to nlọ to nbọ si iwaju rẹ pẹlu bi o ṣe wa lori rakunmi rẹ O si bẹrẹ adua, irawọrasẹ ati idirẹbẹ Ọlọhun ni ṣiṣe titi di asiko wiwọ oorun. O si pa awọn eniyan laṣẹ pe ki wọn o kuro nibi afonifoji Uranat O si sọ pe Mo duro sibi yii, ṣugbọn gbogbo aye arafat yii lo tọ lati duro Bẹẹ nigba ti o n ṣe adua, iṣesi rẹ naa ni pe o gbe ọwọ rẹ mejeeji soke de ipele aya bi igba ti alaini n tọrọ ounjẹ, o si sọ pe Adua to loore ninu ju ni adua ọjọ arafat, eyi ti o si loore ju ninu adua ti emi ati awọn Anabi to ṣiwaju mi maa nṣe ni gbolohun yii "LAAILAAHA ILLA-L-LAAHU WAHDAHUU LAA SHARIKA LAHU, LAHUL MULKU WALAHUL HAMDU WAHUWA ALAA KULLI SHAY'IN QADEER Nigbati oorun wọ ti wiwọ rẹ si fidi mulẹ pẹlu lilọ pupa fẹsifẹsi, o kuro ni Arafah pẹlu ifayabalẹ lẹniti o gbe Usaamah ọmọ Zaid si ẹyin nkan ogun rẹ, ti o si fa ijanu rakunmi rẹ si ọdọ titi ti ori rẹ fi nkan ibi eti gaari rẹ ti o si nsọ pe: Ẹyin eeyan pẹlẹpẹlẹ di ọwọ yin o: toripe dajudaju kii ṣe daada ni yiyara Iyẹn nipe: kii ṣe pẹlu yiyara O si gba oju ọna Al'Mah'zimain, o si wọle si Arafah lati oju ọna Dọbbi, lẹyinna ni o wa nrin diẹdiẹ - Al'Anaqa ni irin tin bẹ laarin yiyara ati lilọra – ti o ba ti wa ri ibiti aaye ti fẹ yio yara O si jẹ ẹniti maa nṣe labaeka nibi irin rẹ ti ko ye ṣe e, o si sọkalẹ ni igbati o wa loju-ọna ti o si tọ ti o si ṣe aluwaala ni fufuyẹ Lẹyinna ni o tun gbera ko si ki irun Kankan titi ti o fi de Muzdalifah, o wa ṣe aluwaala fun irun, lẹyinna ni o paṣẹ wipe ki wọn pe irun, lẹyinna ni o gbe irun duro, o si ki Magrib siwaju ki o to gunlẹ ati ki awọn rakunmi o to wolẹ Nigbati wọn wa gunlẹ, o paṣẹ wipe ki wọn o gbe irun duro, lẹyinna ni o ki irun ishai pẹlu iqọọmoh lai pe irun, ko si ki irun Kankan laarin mejeeji Lẹyinna ni o wa sun titi ti ilẹ fi mọ, ko si ji dide ni orun ọjọ na
O wa yọnda ni oru ọjọ naa nigbati osupa wọ fun awọn ara ile rẹ ti wọn lẹ wipe ki wọn tete maa lọ si Mina siwaju ki alufajari o to yọ, o si pa wọn laṣẹ wipe wọn o gbọdọ ju oko titi ti oorun o fi yọ
Nigbati alufajari wa yọ, o ki irun rẹ ni akọkọ asiko rẹ pẹlu irun pipe ẹyọkan ati ikaamọ ẹyọkan Lẹyinna ni o gun nkan ọgun titi ti o fi de aaye rẹ ni Al'Mash'aril Araam (Muz'dalifah) o si fi mọ awọn eeyan wipe gbogbo Muz'dalifah patapata ni aaye iduro si O wa da oju kọ Qiblah o si bẹrẹ si ni ṣe adura ati idirẹbẹ ati igbe

Ọlọhun tobi ati ṣiṣe gbolohun (laa ilaaha illal loohu) ati iranti titi ti oju ọjọ fi la daada, lẹyinna ni o wa kuro ni Muz'dalifah siwaju ki oorun to yọ lẹniti o gbe Fad'lu ọmọ Abbaas lẹyin Atipe nigbati o si wa loju-ọna o pa Ibnu Abbaas laṣẹ wipe ki o ba oun sa awọn okuta wẹẹwẹẹwẹ  meje ti yio fi sọ'ko; o wa bẹrẹ si ni nka a si atẹlẹwọ rẹ ti o si nsọ pe: Ẹ maa ju oko yin pẹlu iru awọn okuta wọnyi, ki ẹ si sọra fun aṣeju ninu ẹsin Nigbati o wa de aaye ti a npe ni Bat'nu Muas'sir, o yara rin, o si tọ oju-ọna ti o wa ni aarin eleyi ti o ja aaye ijuko ti o tobi ju (Al'jam'rotil Kub'roh) Titi ti o fi de Mina ti o si wa lẹniti nṣe labbaeka rẹ titi ti o fi bẹrẹ si ni nju oko O si ju oko Al'Aqobah (eyiti o gbẹyin) lẹniti o gun nkan ọgun siwaju ki oorun o to yọ, ni isalẹ afonifoji na ti o si gbe Kaaba si apa osi rẹ ti Mina si wa ni apa ọtun rẹ, ti o si ngbe Ọlọhun tobi pẹlu gbogbo okuta kọọkan Lẹyinna ni o ṣẹri pada si Mina ti o si ba awọn eeyan sọrọ ni ibanisọrọ ti o de ogongo ti o nfi mọ wọn ninu rẹ ọwọ ti nbẹ fun ọjọ igunran ati ọla rẹ ati ọwọ ilu Makkah O si tun pa wọn laṣẹ pẹlu gbigbọ ati titele ẹniti o ba dari wọn pẹlu tira Ọlọhun, o si tun fi awọn iṣẹ Haj wọn mọ wọn Lẹyinna ni o kọri si aaye igunran ni Mina ti o si gun Rakunmi mẹta le ni ọgọta pẹlu ọwọ rẹ, ti o si ngun un ni ori iduro leyiti o de ọwọ osi rẹ Lẹyinna ni o wa dawọ duro ti o si pa Aliyy laṣẹ wipe ki o gun eyiti o ṣẹku ninu ọgọrun, lẹyinna ni o tun pa Aliyy laṣẹ wipe ki o fi tọrẹ fun awọn alaini ki o si ma fun alapata ni nkankan ninu ohun ti o pa

O si tun fi mọ wọn wipe dajudaju gbogbo Mina patapata aaye igunran ni, atipe ọna Makkah, oju-ọna ni, aaye igunran si tun ni pẹlu

Nigbati o wa pari gigunran rẹ, o pe farifari ti o si ba a fa ori rẹ, o si bẹrẹ lati apa ọtun Ti o si ko o fun Abu Tol'ha lẹyinna ni o ṣe apa osi, o si ko irun rẹ fun Abu Tol'ha o si sọ pe: Pin in laarin awọn eeyan

O si ṣe adua aforijin fun awọn ti wọn fari ni ẹẹmẹta, o si ṣe e fun awọn ti wọn ge e kuru ni ẹẹkan, iya wa Aaisha si fin oorun aladidun si i lara siwaju ki o to bọra silẹ

Lẹyinna ni o wa kọri si Makkah siwaju ki o to ki irun zhuri lẹniti o gun nkan ọgun O wa ṣe tawaf ifaada, ko si ṣe tawaf mii lẹyin rẹ ko si ṣe ipọṣẹṣẹ pẹlu rẹ, ko si yara rin nibẹ, bẹẹni ko si yara rin nibi tawaf idagbere, nibi tawaf dide si Makkah nikan ni o ti yara rin Lẹyinna ni o wa sibi omi Zamzam lẹyin igbati o pari tawaf rẹ ti awọn eeyan si nbu omi fun awọn eeyan lati mu, wọn wa fun un ni ifami, o si mu u ni ẹniti o duro Lẹyinna ni o pada si Mina ti o si sun ibẹ Wọn wa ṣe iyapa ẹnu lori wipe ibo ni o ti ki irun zhuri ni ọjọ na; Ibnu Umar gbe e wa wipe o ki i ni Mina, Jaabir ati Aaisah sọ wipe o ki i ni Makkah Nigbati o wa ji o reti yiyẹ oorun, nigbati oorun wa yẹ o rin lati ibi ti o wa lọ si aaye ti a ti maa ju oko, ko si gun nkankan, o bẹrẹ pẹlu Jamrah alakọkọ eleyi ti o sunmọ masalaasi Al'khaif, o si ju u pẹlu oko meje, ti nsọ pẹlu oko kọọkan wipe: Alloohu Akbar Lẹyinna ni o wa sun si iwaju nibi Jamarah yẹn titi ti o fi de ibiti o relẹ, o si dide lẹniti o da oju kọ Qiblah, lẹyinna ni o gbe ọwọ rẹ mejeeji si oke ti o si ṣe adura ti o gun ni deede suuratul Baqọrah Lẹyinna ni o wa sibi Jamrah ti aarin o si ju u bakanna, lẹyinna ni o sun si apa osi nibi ti o sunmọ afonifoji naa O si duro lẹniti o da oju kọ Qiblah ti o si gbe ọwọ rẹ mejeeji si oke ni iduro ti o sunmọ ti alakọkọ Lẹyin naa o wa sibi {aye} ijuko ẹlẹẹkẹta eleyii naa ni wọn pé ní al'aqabat, o si ko sinu ọgbun naa O si duro nidabu aye ijuko naa, o si fi ile Ọlọhun (kaaba) si apa osi ati mina si apa ọtun rẹ. Bayii ni o sọ oko meje sii bakan naa Nigba ti o si pari oko jiju tan o ṣẹri ni ko duro nibẹ (lati ṣe adua)

Nkan to rinlẹ ju (labẹ iwadi ti a ṣe) ni wipe o sunmọ ko jẹ pe o ti maa n ju oko naa ṣiwaju ki o to ki irun aila, ti o jẹ pe lẹyin rẹ to ba de ni yoo ṣẹṣẹ ki i. O si yonda fun Abbaas pe ki oun o lọ sun makkah fun gbogbo awọn ọjọ taa fii sun mina nitori iṣẹ ibanibumi (zamzam) mu, eyi to nṣe

Bẹẹ ko si kanju kuro (ni mina) pẹlu lilo ọjọ meji, bi ko ṣe pe o f'ara balẹ sibẹ titi to fi ju oko awọn ọjọ tashreeq (ọjọ pọpọṣinṣin lẹyin ọdun) mẹtẹẹta pe perepere. O si dari si aaye kan to njẹ Almuhassab lẹyin igba ti irun aila ti to O si wa ki irun aila, alaasari, maghribi ati ishai nibẹ. Lẹyin naa o rẹ'ju diẹ. Lẹyin naa o gbera lọ si makkah ti o si ṣe tawaf idagbere loru lasiko saari, ṣugbọn ko pọṣẹṣẹ lori tawaf eleyii. Bẹẹ naa lo ṣe ẹdẹ fun iyawo rẹ Safiyyat nigba ti o ri nkan-oṣu rẹ lasiko naa ti ko fi ṣe tawaf idagbere pe ki o fi i silẹ. Loru yẹn kan naa lo fun iyawo rẹ Aishat ni'yọnda lati ṣe umrat lati fi dun un ninu- eyi ti yoo gbe hurumi rẹ lati adugbo ti wọn npe ni Attan'eem- ti ẹgbọn rẹ Abdurrahman si tẹle e lọ sibẹ. Nigba ti o pari umrat rẹ tan loru yẹn naa, o (Annabi) si polongo fun awọn sahabe rẹ pe irin ajo ipadasile ti ya, bẹẹ ni gbogbo awọn eniyan bẹrẹ si gbera lati rinrin ajo

# Ilana iṣesi rẹ - ki Ọlọhun ṣe ikẹ rẹ fun un - labala ẹran adaaya ati ẹran ileya ati ẹran ikomọjade

## Ilana iṣesi rẹ - ki Ọlọhun ṣe ikẹ rẹ fun un - labala ẹran adaaya (ẹran iṣẹbun fun Ọlọhun nibi iṣẹ hajji)

O lo ẹran agbo ri, bẹẹ naa lo lo rakunmi gẹgẹ bii ẹran adaaya rẹ ri, bẹẹ lo fi maalu ṣe ẹran adaaya fun awọn iyawo rẹ ri, o pa ẹran lasiko ti ko kuro ni madina, nigba hajji ati umurah rẹ

Eyi ti o si jẹ ilana rẹ naa ni pe a maa ṣadayanri ẹran adaaya rẹ ti yoo si fi ranṣẹ si ilu makkah ṣugbọn kii fi ami si i lara. Nigba ti o ba fi ẹran ranṣẹ ti ko si kuro ni madina, ko si nkankan ti yoo jẹ aigbọdọṣe fun un ninu awọn nkan to ti jẹ ẹtọ tẹlẹ tẹlẹ

O si jẹ iṣesi rẹ nigba ti o ba fẹ fi rakunmi ṣe ẹran ẹbun ranṣẹ si makkah pe yoo ṣe adayanri rẹ bẹẹ ni yoo s'ami si i l'ara, yoo fi nkan ṣa a diẹ nibi atẹ ike ẹyin rẹ lapa ọtun ti ẹjẹ yoo fi ṣan jade

Ti o ba fi ẹran adaaya rẹ ran èèyàn, o maa pa ẹni tí ó fi rán láṣẹ pé ti ọkan ninu ẹ ba ti fẹ́ kú, ki o tètè dunbu rẹ, lẹyin naa ki o ki bàtà rẹ bọ inú ẹjẹ rẹ Lẹ́yìn náà ki o wa fi i si ẹgbẹ rẹ, ko si gbọdọ jẹ nibẹ oun ati awọn ti wọn ba jọ wa papọ̀, lẹyin naa ki o wa pín ẹran rẹ

Bẹẹ a maa ṣe eto ipawọpọ pẹran laarin awọn sahabe rẹ (ti wọn yoo pa) rakunmi kan fun ori meje bẹẹ naa ni maalu kan fun ori meje

O si ṣe e lẹtọ fun ẹni ti o ba fa ẹran adaaya tirẹ dani pe o le gun un pẹlu ẹtọ nigba ti o ba ni bukaata si gigun rẹ titi yoo fi ri omiran

Ilana rẹ naa ni mimaa gun rakunmi looro ti wọn yoo si fi okun di ẹsẹ osi rẹ to nbẹ niwaju soke, bẹẹ a maa ṣe BISMILLAHI ALLAHU AKBAR nigba ti o ba fẹ gun un

Bẹẹ a maa dunbu ẹran ijọsin rẹ funra rẹ, o si maa nran ẹlomiran lati dunbu awọn kan ninu awọn ẹran ijọsin naa

O si jẹ ẹni ti o ṣe pe nigba ti o ba fẹ pa ẹran kekere (bii agbo tabi orukọ) yoo gbe ẹsẹ rẹ le ẹgbẹ rẹ, lẹyin naa yoo ṣe BISMILLAAH ALLAHU AKBAR, yoo wa dunbu rẹ

O si ṣe e lẹtọ fun awọn ijọ rẹ lati maa jẹ ninu awọn ẹran adaaya ati awọn ẹran ileya wọn, bẹẹ ki wọn tun mu pamọ paapaa

O si jẹ ẹnikan to ṣe pe nigba miran a maa pin ẹran adaayah rẹ, nigba mii si re a maa sọ pe ẹni to ba fẹ ko ge deede eyi to ba wu

Eyi ti o tun jẹ eto imọna lati ọdọ rẹ naa ni didunbu ẹran adaayah to ba mu fun umrah si ọgangan Marwah, ṣugbọn eyi ti o mu dani fun iṣẹ hajji ati umrah to ṣe, yoo dunbu rẹ ni Mina.

Ko si figba kankan pa ẹran adaayah rẹ ri ayaafi lẹyin igba ti o ba ti bọ hurumi rẹ silẹ. Bakan naa kii pa a ayaafi lẹyin igba ti oorun ba ti yọ bẹẹ ti oun funra rẹ si ti ju oko tan Ko si yọnda rara pe ki ẹnikẹni o dunbu ẹran rẹ ki oorun o to yọ

## Ilana-ọnaamọ rẹ - ki Ọlọhun ṣe ikẹ ati igẹ Rẹ fun un - labala ẹran ileya

Ko figba kankan fi ẹran ileya silẹ lai pa. Bẹẹ iṣesi rẹ ni pe a maa pa agbo meji bẹẹ ni wipe lẹyin irun yidi ni o maa npa a. O si sọ pe Gbogbo awọn ọjọ tash'riiq (mẹtẹẹta) lẹyin ọjọ yidi lo lẹtọ lati pa ẹran ọdun

Bẹẹ lo si sọrọ pe ẹnikẹni to ba pa ẹran tirẹ ki wọn o to kirun yidi iru ẹran bẹẹ ko ni lẹsan pe ẹran ijọsin ni, bi ko ṣe pe yoo wa nipo ẹran apajẹ lasan to kan gbe kalẹ fun awọn araale rẹ.

O si pa wọn laṣẹ pe eyi to ti yọ nlẹ (eyi ni ẹran oloṣu mẹfa ó kere ju) ninu awọn agbo ni ki wọn maa pa fun ọdun. Ki wọn o si maa pa ẹran to ti nka ọdun le ọdun ti kii ba tii ṣe agbo. To ba jẹ rakunmi ni o gbọdọ ti pe ọdun marun. To ba si jẹ maalu ni o gbọdọ ti mẹnu le ọdun kẹta.

Ninu ohun to si jẹ Ilana rẹ naa ni ṣiṣẹṣa ẹran ọdun, ririi wipe o rẹwa bẹẹ naa ni lai nii ni aleebu lara pẹlu O kọ fun wọn lati pa fun ileya, ẹran ti eti rẹ ti gé, tabi ti iwo ori rẹ ti ṣẹ, tabi eyi ti oju rẹ tí da tabi ẹran ti o mukun, tabi ẹran ti ẹsẹ rẹ ti ṣẹ ati ẹran to ti ru hohoho O si paṣẹ pe ki wọn o maa wo oju ati eti rẹ bi o ba lalaafia (tabi bẹẹ kọ) O si paṣẹ fun ẹnikẹni ti o ba fẹ pa ẹran ileya pe ki o ma mu nkankan kuro ninu irun tabi lara rẹ mọ ti ọjọ mẹwa akọkọ naa (ninu oṣu Dhul-Hijjah) bá ti bẹrẹ O si jẹ lara iṣesi-ọnaamọ rẹ pe aaye ti o ba ti kirun yidi naa ni yoo ti pa ẹran ileya (rẹ)

O si jẹ lara iṣesi-ọnaamọ rẹ pe ẹran aṣẹsin (ó jé orukọ tabi agbo) ẹyọ kan ti to fun eniyan kan ati awọn araale rẹ koda bi onka wọn pọ ju bẹẹ lọ.

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi pipa ẹran suna ọmọ

O rinlẹ lati ọdọ rẹ wipe: Gbogbo ọmọ kọọkan ni a fi doogo pẹlu ẹran suna rẹ ti wọn o pa a ni ọjọ keje, ti wọn o si fa ori rẹ ti wọn o si tun sọ ọ ni orukọ O sọ pe: A maa pa agbo meji fun ọmọkunrin, ti a si maa pa ẹyọkan fun ọmọbinrin

# Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi tita rẹ ati rira rẹ ati ibaṣe pọ rẹ

O ta – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – o si tun ra, ti rira rẹ si pọ ju tita rẹ lọ lẹyin ti o di ojiṣẹ

O fi nkan haya, wọn si fi nkan haya fun un, o fa iṣẹ le eeyan lọwọ oun naa si gba ki wọn fa iṣẹ le oun lọwọ, ti fifaṣẹ rẹ le eeyan lọwọ si pọ ju gbigba lati jẹ ki wọn o fa iṣẹ le oun lọwọ lọ

O si tun raja pẹlu sisan owo ni oju ẹsẹ ati dida igba si i, o ṣipẹ fun eeyan, wọn si tun ṣipẹ fun eeyan lọdọ rẹ̀, o jẹ gbese pẹlu fifi nkan dogo ati ai fi nkan dogo, o si tun ya nkan

O si tun tọrẹ ti oun naa si tun gba ọrẹ, o fun eeyan lẹbun ti oun naa si tun gba ẹbun ti o si san ẹniti o fun un ni ẹsan lori ẹ, ti ko ba si fẹ ẹ yio wa nkan sọ fun ẹniti o fun un, awọn lọbalọba si maa n gbe ẹbun fun un, ti o si maa ngba ẹbun wọn, ti o si maa npin in laarin awọn saabe rẹ

O si jẹ ẹniti ibanişepọ rẹ fi ndaa ju ninu awọn eeyan, o si jẹ ẹniti o ṣe wipe ti o ba ya nkan lọwọ ẹnikẹni yio da a pada pẹlu eyiti o fi ndaa ju u lọ, yio si tọrọ alubarika fun un lori awọn ara ile rẹ ati dukia rẹ, o si ya rakunmi kan ti ẹniti o ni i si wa sin in, ti o si le mọ Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – awọn saabe rẹ si gbero lati dide si i O si sọ pe: Ẹ fi i silẹ; toripe dajudaju ọrọ tọ si ẹnu oninkan

Wiwuwa aimọkan si i o ki nle e kun ni nkankan tayọ suuru, o si pa ẹniti ibinu rẹ ba lekoko laṣẹ wipe ki o pa ina ibinu rẹ pẹlu aluwaala, ati pẹlu wipe ki o jokoo ti o ba wa ni inaro tẹlẹ, ati pẹlu wipe ki o fi Ọlọhun wa iṣọra kuro lọdọ eṣu

O si jẹ ẹniti kii dọla lori ẹnikẹni, bikiiṣe wipe o maa nrẹ ara rẹ nilẹ fun awọn saabe rẹ ti o si maa salaamọ si ọmọde ati agbalagba

O si tun jẹ ẹniti maa nṣe awada ti si maa nsọ otitọ nibi awada rẹ, o si tun maa nlo taoriya (lilo gbolohun ti o ni ìtumọ̀ meji, ti o ṣe pe itumo ti o ba foju han kọ ni a maa gba lero, eyi ti o ba pamọ ni a maa gba lero) ko si ki nsọ nkankan nibi taoriya rẹ tayọ otitọ

O si tun dije funra rẹ lori ẹsẹ, o si tun ran bata rẹ funra rẹ, o si tun ran aṣọ rẹ to ya funra rẹ, ti o si tun ran ifami rẹ funra rẹ, o si tun fun wara agutan rẹ funra rẹ, o yọ kokoro ati idọti asọ rẹ̀ kuro funra rẹ̀, o si tun ran ara rẹ ati awọn ara ile rẹ lọwọ, o si tun gbe biriki pẹlu awọn saabe rẹ nigbati wọn nmọ masalasi

O si jẹ ẹniti inu rẹ maa ndun si nkan ju ninu awọn ẹda, ti o si tun jẹ ẹniti ẹmi rẹ fi nmọ julọ

Wọn o si ni ki o sẹsa ọkan ninu alamọri meji ri ayaafi ki o sẹsa eyiti o ba rọrun ju ninu mejeeji lopin igbati kii ba ti ṣe ẹṣẹ

Ko si gba ẹsan lori nkan ti wọn fi ṣe abosi rẹ ri lopin igbati wọn o ba ti ṣe àwọn nkan ti Ọlọhun ṣe leewọ, amọ ti wọn ba ti ṣe nkan ti Ọlọhun ṣe leewọ, ko si nkankan ti o le da ibinu rẹ̀ duro

O maa nfun awọn eeyan ni imọran oun naa si maa ngba imọran, o si maa nbẹ alaisan wo, o si tun maa n fi oju gaani sisin oku, o si tun njẹ ipe, o si tun maa wa pẹlu awọn opo ati alaini ati ọlẹ nibi gbigbọ bukaata wọn

O si tun maa nṣe adua fun ẹniti o ba fun un ni nkan ti o ba dun mọ ọn ninu, ti o si tun sọ pe: Ẹnikẹni ti wọn ba ṣe daada si i ti o wa sọ fun ẹniti o ṣe e wipe: "jazaakalloohu khoiran" Ọlọhun A san ẹ ni ẹsan rere, nitipaapa o ti mu ẹyin de ogongo

## Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi igbeyawo ti ibara-ẹni-lopọ

O rinlẹ lati ọdọ rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – wipe o sọ pe: Wọn jẹ ki n nífẹ̀ẹ́ ninu aye yin: obinrin ati oorun aladidun, wọn si fi titutu oju mi sibi irun kiki O sọ pe: Mo pe ẹyin ọdọkunrin, ẹniti o ba ti ni ikapa ninu yin ki o yaa lọ ṣe iyawo, o si tun sọ pe: ẹ fẹ obinrin ti yio nifẹ yin ti yio si tun bimọ fun yin Itan rẹ pẹlu awọn iyawo rẹ da lori ibanilopọ daada, ati iwa daada, o si jẹ ẹniti maa nsọ pe: Ẹniti o daa ju ninu yin ni ẹniti o daa si awọn ara ile rẹ, atipe emi ni mo daa ju ninu yin si awọn ara ile mi Atipe o jẹ ẹniti o ṣe wipe ti ọkan ninu wọn ba fẹ́ ṣe nkankan ti ko si ikofunni nibẹ yio kun un lọwọ lori ẹ, o si maa nran awọn ọmọdebinrin ansọọri lọ si ọdọ Aisha lati lọ ṣere pẹlu rẹ Ti o (Aaisha) ba si mu omi ninu ife yio gba a ti yio si gbe ẹnu rẹ si aaye ẹnu rẹ (Aaisha) ti yio si mu un O si tun jẹ ẹniti maa nrọgbọkun lori itan rẹ, o si tun maa nke Al'quraani ti ori rẹ o si wa nibi itan rẹ (Aaisha), atipe nigba mi o le jẹ ẹniti nṣe nkan oṣu lọwọ O si maa npa a laṣẹ wipe ki o san bantẹ lẹyinna ni yio wa maa fi ara ro o O si tun jẹ ẹniti o ṣe wipe ti o ba ti ki irun Asri yio tọ ọdọ awọn obinrin rẹ ka; yio si sunmọ wọn ti yio si ṣe iwadi nipa awọn iṣesi wọn Ti ilẹ ba ti wa ṣu yio lọ si iyara ẹniti ipin ba kan ti yio si ṣẹsa oru naa fun un

O si tun jẹ ẹniti maa npin oorun, ile ati inawo laarin wọn, atipe nigba mii a maa na ọwọ si ọkan ninu awọn iyawo rẹ (ti yio fun un ni nkan) ni iseju awọn yoku.

O si tun maa nsunmọ awọn iyawo rẹ ni igbẹyin oru ati akọkọ rẹ Ti o ba se ibalopọ ni akọkọ oru o maa nwẹ nigba mii ti yio si sun Atipe nigba mii ẹwẹ yio ṣe aluwala ti yio si sun O sọ pe: Ẹni epe ni ẹniti o ba ba iyawo rẹ lopọ ni idi O sọ pe: Ti ẹnikan ninu yín ba sọ nígbà tí ó ba fẹ ba ìyàwó rẹ ni ajọṣepọ wipe: ALLAHUMMO JANNIB'NAA SHAYTỌỌNA WA JANNIBI SHAYTỌỌNA MAA RỌZAK'TANAA, ti wọn ba kádàrá ọmọ láàrin àwọn méjèèjì nibi ajọṣepọ naa, eṣu ko nii ni ọmọ naa lara lailai O sọ pe: Ti ẹnikan nínú yín ba ṣẹ̀ṣẹ̀ fẹ ìyàwó kan, tabi o gba ọmọ-ọdọ kan, tabi o ra ẹranko kan, ki o ya gbá irun iwájú orí rẹ̀ mú, ki o si tọrọ alubarika lọdọ Ọlọhun, ki o si dárúkọ Ọlọhun, ki o si sọ pé: ALLOOHUMMA INNII AS'ALUKA KHAERAHAA WA KHAERA MAA JUBILAT ALAEHI, WA AUUZU BIKA MIN SHARRIHAA WA SHARRI MAA JUBILAT ALAEHI O maa nsọ fun ẹni tí ó ba ṣe ìgbéyàwó pé: Baarọkallọọhu laka, wa baarọka alayka, wa jamaha baenakumaa alaa khaer.  Olohun a fun e ni alubarika, yio si tun se alubarika le o lori, yio si fi oore si idapo yin.

O maa ńṣe èyí-jẹ-eyi-o-jẹ láàrin àwọn ìyàwó rẹ ti o ba fẹ rin ìrìn àjò, ẹni tí ìpín rẹ ba jáde ni o maa tẹle e lọ, ko si nii pín nkankan fún àwọn to ṣẹku
Ko si ninu ìlànà rẹ ki o maa ko ọrọ ibùgbé lekan, tabi ki o maa kọ ọ ga gogoro, tabi ki o maa ṣe e ni ọsọ, tabi ki o maa fẹ ẹ.
Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- kọ ìyàwó, o si tun gba ìyàwó pada, o búra pé òun ko nii sunmọ ìyàwó oun fun oṣù kan, ko si fi ẹyin ìyàwó rẹ we ti ìyá rẹ rí.

# Ìlànà rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- nibi oúnjẹ ati nkan mímu

## Ìlànà rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi oúnjẹ:

Kii da oúnjẹ ti o ba wa nílẹ padà, kii si fi agidi wa èyítí ko ba si nílẹ̀ Wọn o le gbe nkan ti o ba lẹtọ láti jẹ fun un àyàfi ki o jẹ ẹ, àyàfi ti ẹmi rẹ ba korira rẹ lo ku O maa gbe e ju sílẹ̀ láìní ṣe e leewọ, ko si nii fi agidi jẹ ẹ ni túláàsì ko bu oúnjẹ kankan ri, ti o ba wu u, yoo jẹ ẹ, bi bẹẹ kọ, yoo gbe e ju sílẹ̀, gẹ́gẹ́ bí ko ṣe jẹ alangba dabb; torí pé ko mọ ọn lára O maa njẹ nkan ti o ba ti ri, ti ko ba wa si nkankan ti o maa jẹ, o maa ṣe sùúrù, débi pé yoo de òkúta mọ ikùn rẹ látàrí ebi Iletesu mẹta a maa kọjá ti wọn o nii dáná ni ilé rẹ
Ko si nínú ìlànà rẹ ki o máa jẹ oúnjẹ orísi kan ṣáá láìní jẹ òmíràn
O jẹ nkan dídùn ati oyin, o si nífẹ̀ẹ́ méjéèjì O jẹ ẹran ràkúnmí ati àgùntàn, àti adìẹ, àti ẹran ẹyẹ hubaarah, àti ẹran kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ igbó, àti ehoro, àti àwọn nkan jíjẹ to wa láti inú odo O jẹ ẹran yiyan, o si jẹ dabinu tútù àti dabinu gbígbẹ O jẹ thareed; òun naa ni búrẹ́dì àti ẹran, o si tun jẹ búrẹ́dì àti òróró O jẹ elegede pẹ̀lú dabinu tútù, o si tun jẹ eso dubbaa' ti wọn se, o si nífẹ̀ẹ́ rẹ O jẹ ẹran gige ti o ni iyọ̀ ti wọn fi oorun gbẹ, o si tun jẹ dabinu gbígbẹ pẹ̀lú bọta
O nífẹ̀ẹ́ ẹran, èyí tí ó sì nífẹ̀ẹ́ sí jù lára ẹran náà ni apá àti iwájú ẹran
O maa njẹ ninu èso ìlú rẹ̀ nígbà tí ó bá dé, kii sii kọ ọ
Ọpọlọpọ oúnjẹ rẹ, wọ́n maa ngbe e si ilẹẹlẹ ni nínú ìtẹ́ ti wọn máa n gbe oúnjẹ sinu ẹ
O maa n pàṣẹ pe ki wọn o maa fi ọwọ́ ọtun jẹun, o si maa n kọ ki wọn maa fi ọwọ́ òsì jẹun O tun maa nsọ pe: Dájúdájú èṣù ni maa n fi ọwọ́ òsì rẹ jẹun ti o si tun maa nfi ọwọ òsì rẹ mu O maa nfi ìkà mẹta rẹ jẹun, o si maa ńlá wọn ti o ba jẹun tan Kii jẹun lẹniti o rọgbọku, rirọgbọku si pe orísi mẹta; ọkan ninu ẹ ni fifi ẹgbẹ rọgbọku, ìkejì ni lilọ ẹsẹ mejeeji papọ̀ labẹ itan, ikẹta ni fifi ọkan ninu ọwọ mejeeji rọgbọku ti èèyàn a si maa fi ẹyọ kan yoku jẹun, meteeta yii naa ni ko dára, a si maa jẹun lẹniti yoo joko iq'haa'u Al-Iq'haa'u naa ni: ki èèyàn o fi alawẹ ìdí rẹ mejeeji joko, lẹniti yoo gbe ojugun rẹ mejeeji sókè Emi maa ń jókòó gẹ́gẹ́ bí ẹrú ṣe maa ń jókòó, mo si maa ń jẹun gẹ́gẹ́ bí ẹrú ṣe maa ń jẹun. Ti o ba ti gbe ọwọ́ rẹ sibi oúnjẹ, o maa sọ pé: BISMILLAAH, o si maa n pàṣẹ fún ẹni tí o ba fẹ jẹun ki o sọ pe BISMILLAAH O sọ pe: Ti ẹni kọọkan ninu yin ba fẹ jẹun ki o yaa dárúkọ Ọlọhun, ti o ba wa gbàgbé ki o wi i ni ibẹrẹ, ki o yaa sọ pé: BISMILLAAHI FII AWWALIHII WA AAKHIRIHI O sọ pe: Dájúdájú èṣù maa n sọ oúnjẹ di ẹtọ ni ti wọn o ba ti dárúkọ Ọlọhun si i. O maa n sọ̀rọ̀ lórí oúnjẹ rẹ, o si maa n fi oúnjẹ lọ àwọn àlejò rẹ lemọ-lemọ; gẹ́gẹ́ bí àwọn ọlọrẹ ṣe maa nṣe Ti wọn ba ti gbé oúnjẹ kúrò níwájú rẹ, o máa nsọ pe: ALHAMDU LILLAAHI HAMDAN KASIIRAN TỌYYIBAN MUBAARỌKAN FIIH, GAERA MAK'FIYYIN, WALAA MUWADDAHIN, WALAA MUS'TAG'NAN AN'HU RỌBBUNAA (Ope ni fun Olohun, o pe topo to daa to si ni ibukun ninu, ope ti n ko le du ti yoo fi dogba pelu oore ti Olohun se fun mi, ope ti ko se e pati ti ko si see ma se rara). Ti o ba si jẹun lọdọ àwọn eeyan kan, ko nii jáde titi ti yoo fi ṣe adua fun wọn O tun maa nsọ pe: Af'tọra in'dakumus-sọọ'imuun, wa akala tọ' aamọkumul-abrọọr, wa sọllat alaykumul-Malaaikat {Awon alaawe sinu lodo yin, awon eniire si je ounje yin, awon malaika si ti se adura fun yin}.
O maa n ṣe adua fun ẹniti ba maa n gba alejo àwọn alaini, o si maa n yin wọn
Ko si ẹni ti ko le ba jẹun papọ̀, yala o jẹ ọmọdé ni o abi àgbàlagbà, boya ọmọlúwàbí ni tabi ẹrú, boya larubawa oko ni tabi ẹniti o ṣe hijira
Ti wọn ba gbe oúnjẹ sunmọ ọn ti o si n gba aawẹ, o maa sọ pe: Dájúdájú èmi n gba awẹ, O pàṣẹ fun ẹniti wọn ba gbe oúnjẹ fun pe ki o ṣe adua fun ẹniti o gbe oúnjẹ fun un ti o ba jẹ alaawẹ, ki o si jẹ oúnjẹ naa ti ko ba gba aawẹ Ti wọn ba pe e si oúnjẹ kan, ti ẹnìkan si tẹle e, o maa jẹ ki onile o mọ, o maa sọ pé: Awa ni ẹni yii tẹle wa, ti o ba fẹ o le yọnda fun un, ti o ba si wu ọ, o le padà.
O pàṣẹ fun àwọn ti wọn ke gbajari wa ba a pe àwọn kii yo pe ki wọn maa jẹun papọ̀, ki wọn si dárúkọ Ọlọhun si i, ki wọn le baa ba wọn fi alubarika si i
O sọ pe: Ọmọ Anọbi Adam ko kun abọ kan ti o buru ju ikùn lọ, o ti to fun ọmọ Anọbi Adam àwọn okele kéékèèké ti yoo gbe eegun ẹyin rẹ duro, ti ko ba wa si ibuyẹ afi ki o jẹun ju bayẹn lọ, ki o ya jẹ ki idamẹta o wa fun oúnjẹ rẹ, ki idamẹta o wa fun nkan mímu rẹ, ki idamẹta o wa fun mimi rẹ O wọ ilé rẹ ni ọjọ́ kan, o wa oúnjẹ ni ko ba ri nkan ti o maa jẹ, O si sọ pe: Irẹ Olohun, bọ ẹniti o bọ mi, ki O si fun ẹniti o fun mi ni nkan mu ni nkan mu

## Ìlànà rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi nkan-mimu:

Ilana rẹ nibi nkan-mimu wa lára ilana ti o pe ju lati da àábò bo ìlera, ninu nkan ti o si nífẹ̀ẹ́ si ju lati maa mu naa ni nkan ti o dùn ti o si tutu

O maa n mu wàrà ti o mọ nígbà míì, o si tun maa n mu wàrà ti wọn ti po pọ mọ omi nígbà míì naa, o maa wa n sọ pé: Irẹ Ọlọhun, ba wa fi alubarika si i, ki O si ba wa ṣe alekun rẹ; tori ko si nkan ti o le rọrọ kúrò nibi nkan jíjẹ ati nkan mimu ju wàrà lọ Ko si ninu ìlànà rẹ ki o maa mu nkan lori oúnjẹ, wọ́n maa n ba a ṣe nkan imu ti njẹ "nabiiz" ni ibẹrẹ alẹ, yoo si mu u ti o ba ji ni àárọ̀ ọjọ́ yẹn, ati ni alẹ ti o ba tẹle e, ati ni àárọ̀ rẹ, ati ni alẹ miran, ati ni àárọ̀ rẹ titi di asiko alaasari. Ti nkan ba ṣẹku ninu ẹ, yoo fun ọmọ-ọdọ rẹ mu tabi ki o ni ki wọn o da a nu.

(Ohun tí a n pe ni nabiiz ni: nkan ti wọn maa nju dabinu sinu rẹ ki o le dùn. Kii mu u lẹyin ọjọ́ kẹta lẹniti npaya ki o ma lọ maa pani bi ọtí)

Ninu ìlànà rẹ ti o ti ba sáábà naa ni mimu nkan lórí ijoko, o si kọ ki a maa mu nkan ni ìdúró, o si mu nkan ni ìdúró ni ẹẹkan Wọn sọ pé: o ni ìdí tí o fi ṣe bẹ́ẹ̀, àwọn kan sọ pe: wọn ti pa ìdájọ́ yẹn rẹ torí pé o ti kọ ki a maa mu nkan ni ìdúró, àwọn kan tun sọ pé: mejeeji ni o lẹtọ O maa n mi nibi nkan mimu ni ẹẹmẹta O tun maa nsọ pe: O maa n sọ pé: dajudaju oun ni o fi n rẹ òùngbẹ ju, ti o si fi n lọ tinrin ju ni ọfun, ti o si tun fi n lani kúrò nibi àìsàn ju Ìtumọ̀ mimi rẹ nibi nkan mimu ni: gbígbé nkan imumi kúrò ni ẹnu lati mi síta gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wa ninu ọ̀rọ̀ rẹ ti o sọ pe: Ti ẹnìkan ninu yin ba mumi, ko gbọdọ mi sínú ife-imumi, ṣùgbọ́n ki o gbe e kúrò ni ẹnu rẹ, o si kọ ki a maa mu nkan lati iho ti o wa lara ife-imumi ati lati ẹnu ife-imumi. Ìtumọ̀ THULAMAT ni: iho tabi oju ibi ti nkan ti là O maa n ṣe BISMILLAAH ti o ba fẹ mu nkan, o si maa n dúpẹ́ fun Allah ti o ba mu nkan tan O sọ pe: Dájúdájú Ọlọhun maa n yọnu si ẹrú ti o maa n dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ̀ ti o ba jẹun, ti o si tun maa n dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ ti o ba mu.

Wọn maa n wa omi ti o ba dun fun un, oun naa ni omi ti o da ti ko ni iyọ ninu, o si maa n ṣesa omi ti òru kan ba ti rekọja lórí ẹ

Ti o ba si ti mu nkan tan, o maa ngbe e fun ẹniti o wa ni ọwọ ọtun rẹ, koda ki ẹni tí ó wà ní ọwọ osi rẹ o dàgbà jù ú lọ.

O si pàṣẹ pe ki wọn maa fi nkan bo ife-imumi kódà ki wọn kan na igi le e lórí lati bo o, ki wọn si dárúkọ Ọlọhun nígbà tí wọ́n ba fẹ bo o

Ìtumọ̀ al-IIKAA'U ni: ki wọn de ẹnu abọ

# Ìlànà rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi ipepe si oju ọna Ọlọhun

O maa n pepe si ti Ọlọhun ni ọsan ati alẹ, ni kọkọ ati ni gbangba O wa ni Mẹka fun ọdun mẹta ni ìgbà tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ di Anọbi ti o n pepe si oju ọna Ọlọhun ni bonkẹlẹ Nígbà tí wọ́n wa sọ aaya kalẹ fun un pé ( wi ohun ti wọn pa ọ láṣẹ sita) ni oun naa ba wi àṣẹ Ọlọhun sita Kii bìkítà nipa ẹ̀gàn apẹgan kankan O pe àgbàlagbà si oju ọna Ọlọhun, ati ọmọdé naa, ati ọmọlúwàbí ati ẹrú, àti akọ àti abo, ati alujannu ati èèyàn.

Nígbà tí iya pọ ju fun àwọn saabe rẹ ni Mẹka, o yọnda fun wọn lati ṣe hijra lọ si ìlú Habasha

O jade lọ sí ilu Taif boya wọn le ran an lọ́wọ́, o pe wọn si ti Ọlọhun, ṣùgbọ́n ko ri oluranlọwọ kankan Wọ́n fi suta to ni agbára kàn án Wọn si fi ìyà ti àwọn ìjọ rẹ gan o fi jẹ ẹ, wọ́n fi jẹ ẹ Wọn le e jade lọ sí Mẹka O wa wọ ibẹ pẹ̀lú Mut'him ọmọ Adiyy O ṣi wa lẹniti npepe ni gbangba fun ọdun mẹwa " O maa n tẹle àwọn alalaaji ni àwọn aaye wọn, ati ni àwọn ibukojọpọ àwọn eeyan ni Ukaaz, ati Majinnat, ati Zul-Majaaz " Koda o maa n beere nipa aaye àwọn ìdílé lẹyọkọọkan Lẹyin naa ni o pade àwọn eeyan mẹfa kan lati ìdílé Khaz'raj ni oju ọna ti o wa lori àpáta. O pe wọn sinu Islam, ni wọn ba gba Islam, lẹyin naa ni wọn pada si Mẹdina Ni àwọn naa ba bẹrẹ si ni pe àwọn eeyan sinu Islam, ni Islam ba tan ka titi ti ko fi si ile kan ti Islam ko wọ Nígbà tí ó di ọdun ti o tẹle e, ọkùnrin méjìlá ni o wa nínú wọn O ba wọn ṣe adehun bae'hatul aqabah, wọn ṣi da májẹ̀mú fun un lati maa gbọ ọ̀rọ̀ rẹ ati lati maa tẹle e, ati lati maa náwó si ti Ọlọhun, ati lati maa pàṣẹ dáadáa, ati lati maa kọ ìwà ibajẹ Ati lati maa sọ nípa Ọlọhun láìní bìkítà ẹgan apẹgan "Ati lati maa ran an lọ́wọ́, ati lati maa dáàbò bo o nibi nkan ti wọn ba ti maa n dáàbò bo ara wọn ati awọn iyawo wọn ati awọn ọmọ wọn nibẹ, ti Alujanna yoo si jẹ tiwọn, lẹ́yìn náà ni wọ́n padà sí Mẹdina O ran Ibnu Ummi Maktoom ati Mus'hab ọmọ Umayr tẹle wọn lati maa kọ Kuraani ati lati maa pepe si ti Ọlọhun Àwọn èèyàn to pọ si gba Islam lati ọwọ àwọn mejeeji " Lara wọn ni Usayd ọmọ Hudhayr, ati Sah'd ọmọ Muaz Lẹ́yìn náà ni Anọbi- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- wa yọnda fun àwọn Mùsùlùmí lati ṣe hijra lọ si Mẹdina, àwọn èèyàn sì yara lọ Lẹ́yìn náà ni oun ati ọrẹ rẹ tẹle wọn O so àwọn Muhaajiruun ati Ansaar papọ bii ọmọ ìyá ti onka wọn si je aadọrun

# Ilana rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi ifunni ni ifayabalẹ ati iṣe àtúnṣe ati bíbá àwọn ojiṣẹ lo pọ

O rinlẹ lati ọdọ rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – wipe o sọ pe: Adehun ifayabalẹ àwọn Musulumi ẹyọkan ni, ti ẹnikan nínú wọn ba ti ṣe adehun ifayabalẹ, gbogbo wọn ni wọ́n ti ṣe adehun nìyẹn O sọ pe: Ẹnikẹ́ni tí adehun ba n bẹ láàrin rẹ àti àwọn ìjọ kan, ko gbọdọ tú kókó kan tabi ki o de e títí ti asiko rẹ yoo fi ré kọjá, tabi ki o ju àdéhùn wọn pada si wọn lori dọ́gba dọ́gba O sọ pe: Ẹnití o ba fi ẹnikan laya balẹ̀ lórí ẹ̀mí rẹ̀, ti o tun wa pa a, emi ti bọpa bọsẹ kúrò lọdọ ẹniti o pa èèyàn yẹn. Nígbà tí ìránṣẹ́ meji wa ba a lati ọdọ Musaylimat, ni wọn wa sọ nkan ti wọn fẹ sọ, o sọ fun wọn pe: Ti kii ba ṣe pe wọn o ki n pa àwọn ìránṣẹ́ ni, mi o ba bẹ ọrùn ẹyin mejeeji ni "Báyìí ni o ṣe di sunnah rẹ pe ki wọn ma maa pa ìránṣẹ́ Kii si de ìránṣẹ́ mọlẹ lọ́dọ̀ rẹ ti o ba taku lori ẹsin rẹ, bi ko ṣe wípé yoo da a padà ni "Ti ọkan ninu awọn ọ̀tá rẹ ba ṣe adehun pẹ̀lú ọkan ninu awọn saabe rẹ láì yọnu si i, yoo ṣe àmúlò rẹ O fi ẹnu ko pẹ̀lú àwọn Kuraysh lati ma ba ara wọn jagun fun ọdun mẹwa, àti pé ẹni tí ó ba wa sọdọ rẹ lati gba Islam, o maa da a pada Àti pé ẹni tí ó ba wa ba àwọn Quraysh lati ọdọ Anọbi, àwọn ko nii da a pada, ni Ọlọhun wa pa a rẹ nipa ti àwọn obìnrin, o wa pàṣẹ pe ki wọn o dan wọn wo Ẹni tí wọ́n ba ti mọ pe olugbagbọ ododo ni, wọn ko nii da a pada O pa àwọn Musulumi láṣẹ pe ki wọn o da owo ori obìnrin ti o ba koomọ fun ọkọ rẹ ti wọn ba ti ko ọrọ ogun lẹ́yìn tí wọ́n ba borí àwọn Kèfèrí " Wipe wọn gbọ́dọ̀ da owó orí obìnrin ti o ba ṣe hijra pada fun ọkọ rẹ Kèfèrí "Ko kọ fun wọn lati gba ẹni tí ó ba wa ba a ninu àwọn ọkùnrin, ko si ni jan an nipa lati pada, ko si ni pa a láṣẹ lati ṣe bẹ́ẹ̀ " Ti o ba fi ọwọ ara rẹ pa èèyàn ninu àwọn Kèfèrí tabi o gba owo kan ti ko si lọ́wọ́ rẹ mọ, ti koi si tii darapọ mọ àwọn Musulumi, a o nii tako o lori nkan ti o ṣe, Anọbi o si nii san ìtanràn rẹ "O fi ẹnu kò pẹ̀lú àwọn ará khaybar nígbà tí ó bori wọn pe o maa le wọn kúrò ni ìlú ti Nkan ti rakunmi wọn ba gbe si maa jẹ ti wọn " Ti wura ati fàdákà ati nkan ijagun si maa jẹ́ ti ojiṣẹ Ọlọhun (kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) " O fẹnu ko pẹ̀lú wọn pe idaji ohun ti ba njade nínú ilẹ maa jẹ ti ẹ, ti idaji si maa jẹ ti wọn naa " Atipe o le fi wọn sílẹ̀ ninu ìlú di ìgbà tí ó bá fẹ́ " Ọdọọdun ni o maa n ran si wọn ẹni tí yoo fi ojú dá àwọn èso wọn Wọn o wa wo ìdiwọ̀n ti wọn maa ká ninu ẹ, yoo wa ni ki wọn o fi àwọn Musulumi lọkan balẹ̀ lori ìpín wọn lati le fi ṣe ohun tí o ba wu wọn

## Ìlànà rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi pípe àwọn ọba, ati riran àwọn iranṣẹ ati ìwé si wọn

" Nigba ti o ṣeri pada lati Hudaybiyyat, o kọ lẹ́tà si awọn ọba aye " O si ran àwọn iranṣẹ si wọn " O kọ lẹ́tà si ọba ilu Roomu " O ranṣẹ si i, o ku diẹ ki o gba Islam, ṣùgbọ́n ko gba a " O ranṣẹ si Najaashiyy, o si gba Islam " O ran Abu Musa Al-Ash'ariyy ati Muaz ọmọ Jabal lọ sí ìlú Yemen " Ilana rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi biba àwọn munaafiki lo pọ " O maa n gba ohun ti wọn ba fi han wọlé, o si maa nfa kọkọ wọn le Ọlọ́hun lọ́wọ́ " O maa n ba wọn ja pẹ̀lú ẹ̀rí O maa n gbunri kúrò lọ́dọ̀ wọn, a si tun maa le koko mọ wọn A si tun maa mu ọrọ ti o de ogongo de ẹmi wọn . Ko pa wọn lati le pa àwọn ọkàn pọ̀ O sọ pe: Ki àwọn èèyàn ma baa maa sọ pé Muhammad npa àwọn saabe rẹ.

## Ìlànà rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi asikiri

O jẹ ẹni tí ó pé jù nínú àwọn ènìyàn nibi ìrántí Ọlọhun Ọba ti O biyi ti O gbọngbọn Bi ko ṣe wípé gbogbo ọrọ rẹ pátá ìrántí Ọlọhun ni ati nkan ti o tẹle e Àṣẹ rẹ àti kikọ nkan rẹ àti ṣíṣe òfin rẹ fun ìjọ rẹ, ìrántí Ọlọhun ni wọn láti ọdọ rẹ Didakẹ rẹ náà jẹ ìrántí Ọlọhun pẹlu ọkàn rẹ Ìrántí Ọlọhun rẹ máa n lọ pẹ̀lú èémí rẹ ti o ba dúró ati ti o ba jókòó, ati ti o ba fi ẹgbẹ le lẹ, ati nígbà tí ó ba n rin ati ti o ba gun nkan, ati nígbà tí ó bá n rin lọ ati nígbà tí ó bá de si ibikan, ati ni ìgbà tí ó bá ṣe ìrìn-àjò ati ni ìgbà tí ko ba rin ìrìn àjò, ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a.

# Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi asikiri ni àárọ̀ ati irọlẹ

O maa n sọ ni àárọ̀ pe: AS'BAH'NAA ALAA FIT'RỌTIL ISLAAM, WA KALIMATIL IKH'LAAS, WA DIINI NABIYYINAA MUHAMMADIN-SOLLA LOOHU ALAEHI WA SALLAM- WA MILLATI ABIINAA IBRỌỌHIIMA HANEEFAN MUSLIMAN, WA MAA KAANA MINAL MUSH'RIKIIN (A ji saye lori esin Islam, ati lori gbolohun ise afomo Olohun, ati lori esin ti Olohun fi ran anabi Muhammad, ati loju ona anabi wa Ibrahim, ti o je eni ti o gba fun Olohun ti o jupa juse sile fun Olohun, Ko si si ninu oluse ebo si Olohun). O si maa nsọ pe ALLAHUMMO BIKA AS'BAH'NAA, WA BIKA AM'SAENAA, WA BIKA NAH'YAA WA NAMUUT, WA ILAEKAN-NUSHUUR (Ire Olohun Oba, pelu agbara Re ni a fi ji saye, pelu agbara Re naa ni a fi di ale, pelu agbara Re naa ni a fi nsemi, pelu agbara Re naa ni ao fi ku, odo Re ni a o fi abo si). O sọ pe: Ti ẹni kọ̀ọ̀kan yin ba ji ni àárọ̀ ki o yaa sọ pe: AS'BAH'NAA WA AS'BAHAL MUL'KU LILLAAHI RỌBBIL AALAMIIN, ALLAHUMMO INNII AS'ALUKA KHAERA AAZAL YAOM, FAT'HAHUU WA NAS'RỌ̀HUU, WA NUURỌHUU WA BARỌKATAHUU WA IDAAYATAHUU, WA AUUZU BIKA MIN SHARRI MAA FIIHI WA SHARRI MAA BAADAHUU, ti o ba ti wa di irọlẹ, ki o sọ iru nkan yẹn naa O sọ

pe: Ọga iwa-aforijin ni ki ẹrú o sọ pe: ALLAHUMMO ANTA RỌBBII LAA ILAAHA ILLA ANTA, KHALAK'TANII WA ANA AB'DUKA WA ANA ALAA AH'DIKA WA WAH'DIKA MAS'TATAH'TU, AUUZU BIKA MIN SHARRI MAA SỌNAH'TU ABUUHU LAKA BI NIH'MATIKA ALAYYA WA ABUUHU BIZAM'BII, FAG'FIR'LII, INNAHUU LA YAG'FIRU ZUNUUBA ILLAA ANT, ẹni tí ó ba sọ ọ ni àárọ̀ ti o ni amọdaju nípa rẹ̀, ti o wa ku ni ọjọ́ naa, yoo wọ Alujanna, ẹni tí ó ba wi i ni irọlẹ ti o ni amọdaju pẹlu ẹ, ti o wa ku ni alẹ́ ọjọ́ naa, yóò wọ Alujanna. O sọ pe: Ẹni tí ó ba sọ ni àárọ̀ pe: LAA ILAAHA ILLAA LOOHU WAH'DAHUU, LAA SHARIIKA LAHUU, LAHUL MUL'KU WA LAHUL HAM'DU, WA UWA ALAA KULLI SHAY'HIN KỌDIIR, ẹni tí ó ba wi i ni ìgbà ọgọrun, laada ti yoo gba maa ṣe deede ti ẹni tí ó bọ okun kúrò lọrun ẹrú mẹwa, wọn a si kọ dáadáa ọgọrun silẹ fun un, wọ́n a si pa ọgọrun rẹ nínú aida rẹ, yoo si tun jẹ idaabobo fun un kúrò lọ́wọ́ èṣù ni ọjọ́ naa titi yoo fi di irọlẹ, ẹni kankan o si nii mu ohun ti o lọla ju u lọ wa afi ẹni tí ó ba ṣe ju bẹẹ lọ O maa n ṣe àwọn adua yii ni àárọ̀ àti ni irọlẹ: ALLAHUMMO INNII AS'ALUKAL AAFIYATA FII DUN'YAA WAL AAKHIRAT, ALLAHUMMO INNII AS'ALUKAL AF'WA WAL AAFIYATA FII DIINII WA DUN'YAAYA WA AH'LII WA MAALII, ALLAHUMMỌ US'TUR AORỌỌTII, WA AAMIN RAO'AATII, ALLAHUMMỌ IH'FAS'NII MIN BAENI YADAYYA WA MIN KHAL'FII, WA AN YAMIINII WA AN SHIMAALII, WA MIN FAOKII, WA AUUZU BI AZỌMATIKA AN UG'TAALA MIN TAH'TII (Iwo Olohun, emi ntoro amojukuro Re ati ini Alafia ara ni aye ati orun, Olohun emi ntoro ni odo Re amojukuro Re ati ike Re ninu aye mi ati orun mi, ati araale mi ati lori dukia mi, Olohun ba mi gbe aleebu mi pamo ki O si fi aya mi bale nibi gbogbo ohun ti npami laya, Olohun fi iso Re so mi ni iwaju mi, ati ni eyin mi, ati otun mi, ati osi mi, ati ni oke mi, mo si fi O wa isora nibi ki a yo mi pa lati isale mi). O sọ pe: Ko si ẹrú kankan ti yoo sọ ni àárọ̀ àti irọlẹ ni ojoojumọ pe: BISMILLAAHI LAZII LAA YADURRU MAHAS'MIHII SHAE'HUN FIL AR'DI WA LAA FI SAMAA'I WA UWA SAMIIHUL ALIIM, ni ẹẹmẹta, àfi ki nkankan ma ni i lara. Abubakr sọ fún un pé: kọ mi ni nkan ti maa maa wí ni àárọ̀ àti irọlẹ O sọ fún un pé maa sọ pé: ALLAHUMMỌ FAATIRỌ SAMAAWAATI WAL AR'DỌ, AALIMAL GAEBI WA SHA'HAADAT, RỌBBA KULLI SHAE'HIN WA MALIIKAHU WA MAALIKAHU, ASH'HADU AN LAA ILAAHA ILLAA AN'TA, AUUZU BIKA MIN SHARRI NAF'SII, WA MIN SHARRI SHAYTỌỌNI WA SHIR'KIHI, WA AN AK'TARIFA ALAA NAF'SII SUU'AN AO AJURRỌHUU ILAA MUSLIM. O sọ pe: maa wí i ni àárọ̀ àti irọlẹ ati ti o ba fẹ sun.

## Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Olohun maa ba a- nibi asikiri nígbà tí ó ba jáde kúrò nílé àti nígbà tí ó ba wọlé:

Ti o ba jáde kúrò ní ilé rẹ̀, o maa n sọ pe: BISMILLAAHI TAWAKKAL'TU ALAL LỌ̀ỌHI, ALLAHUMMỌ INNII AUUZU BIKA AN ADILLA AO UDỌLLA AO AZILLA AO UZALLA, AO AZ'LIMA AO UZ'LAMỌ, AO AJ'HALA AO YUJ'HALA ALAYYA (Ire Olohun Oba dajudaju emi sa di O nibi ki nsonu tabi ki won somi nu, tabi ki nye ese gere tabi ki won yemi lese gere, tabi ki nse abosi eniyan tabi ki won se abosi simi, tabi ki nwu iwa aimokan tabi ki won wu iwa aimokan simi). O sọ pe: Ẹni tí ó bá sọ nígbà tí o jáde kúrò ni ilé rẹ pe: BISMILLAAHI TAWAKKAL'TU ALAA LỌ̀ỌHI WA LAA AOLA WA LAA QUWWATA ILLAA BILLAAHI, wọ́n maa sọ fún un pé: wọn ti fi ọ mọna, wọn ti to ọ, wọn ti ṣọ ẹ, eṣu yoo ṣi maa jìnà si i. Ti o ba jáde lọ ki irun alufajari, yoo sọ pe: ALLAHUMMỌ IJ'HAL FII KỌL'BII NUURAN, WAJ'HAL FII LISAANII NUURAN, WAJ'HAL FII SAM'HII NUURAN, WAJ'HAL FII BASỌRII NUURAN, WAJ'HAL MIN KHAL'FII NUURAN, WA MIN AMAAMII NUURAN, WAJ'HAL MIN FAOKII NUURAN, WAJ'HAL MIN TAH'TII NUURAN, ALLAHUMMỌ AH'ZIM LII NUURAN. O sọ pe: Ti èèyàn ba wọ ilé rẹ, ki o yaa sọ pe: ALLAHUMMỌ INNII AS'ALUKA KHAERAL MAOLIJ, WA KHAERAL MAKH'RAJ, BISMILLAAHI WALAJ'NAA, WA ALAA LỌỌHI RỌBBINAA TAWAKKAL'NAA, lẹ́yìn náà ki o salamọ si araale rẹ.

# Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- nibi asikiri ti o ba fẹ wọ mọṣalaaṣi ati ti o ba fẹ jáde kúrò nibẹ

Ti o ba wọ mọṣalaaṣi, o maa sọ pe: AUUZU BILLAAHIL AZIIM, WA BI WAJ'HIHIL KARIIM, WA SUL'TỌỌNIHIL KỌDIIM, MINASH-SHAYTAANI-R-RAJIIMI. O sọ pe: ti o ba ti sọ bayẹn, eṣu maa sọ pe: wọn ti sọ ọ kúrò nibi aburú mi kolẹ òní. O sọ pe: Ti ẹni kọ̀ọ̀kan yin ba wọ mọṣalaaṣi, ki o yaa salamọ si Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- ki o wa sọ pe: ALLAHUMMOF-TAH LII AB'WAABA RAH'MATIKA, ti o ba ti jáde ki o sọ pe: ALLAHUMMO INNII AS'ALUKA MIN FAD'LIK.

# Ìlànà rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi asikiri rírí iletesu

Ti o ba ti ri iletesu, o maa n sọ pe: ALLAHUMMỌ AHILLAHUU ALAENAA BIL AM'NI WAL IIMAANI WAS-SALAAMATI WAL ISLAAM, RỌBBII WA RỌBBUKAL-LỌỌH

# Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- nibi asikiri nígbà tí o ba sin ati nígbà tí o ba yan:

O rinlẹ lati ọdọ rẹ, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, pe: Ọlọhun nífẹ̀ẹ́ si sisin, O korira yiyan, ti ẹnikan ninu yin ba sin, ti o wa sọ pe ALHAMDULILLAAH, ẹtọ ni fun gbogbo Musulumi ti o ba gbọ ọ ki o sọ fun un pe: YAR'HAMUKAL-LỌỌH, ṣùgbọ́n yiyan ń tiẹ wa láti ọ̀dọ̀ èṣù, ti ẹnikan ninu yin ba yan, ki o yaa da a padà bi o ba ṣe kapa mọ; toripe ti ẹnikan ninu yin ba yan, eṣu maa n fi i ṣe yẹyẹ ni.

Ti o ba sin, o maa n fi ọwọ́ rẹ tàbí aṣọ rẹ bo ẹnu rẹ, yoo wa rẹ ohùn rẹ nilẹ pẹ̀lú ẹ

Ti o ba sin, ti wọn wa sọ fun un pe: YAR'HAMUKAL-LỌỌHU, o maa sọ pe: YAR'HAMUNAL-LỌỌHU WA IYYAAKUM, WA YAG'FIRU LANAA WA LAKUM O sọ pe: Ti ẹnikan ninu yin ba sin, ki o yaa sọ pe: ALHAMDULILLAAH, ki ọmọ-iya rẹ o si sọ fun un pe: YAR'HAMUKAL-LỌỌHU, ti o ba ti wa sọ fún un pe: YAR'HAMUKAL-LỌỌHU, ki o yaa sọ pe: YAH'DIIKUMUL-LỌỌHU WA YUS'LIHU BAALAKUM O sọ pe: Ti ẹnikan ninu yín ba sin, ti o wa sọ pe: ALHAMDULILLAAH, ki ẹ yaa sọ fun un pe: YAR'HAMUKAL-LỌỌHU, ti ko ba sọ pe: ALHAMDULILLAAH, ẹ o gbọdọ sọ YAR'HAMUKAL-LỌỌHU fun un Ti ẹni ti o n sin ba ti sin kọja ẹẹmẹta, ko nii sọ YAR'HAMUKAL-LỌỌHU fun un O sọ pe: Eléyìí ti ni kata O tun ni alaafia lati ọdọ rẹ pe: Àwọn Yahuudi maa n ṣe bii ẹni tí n sin lọdọ Anọbi tori ki o le baa sọ fun wọn pe: YAR'HAMUKUMUL-LỌỌHU (Ọlọhun yoo kẹ yin), o maa n sọ fun wọn pe: YAH'DIIKUMUL-LỌỌHU WA YUS'LIHU BAALAKUM (Ọlọhun yoo fi yin mọna, yoo si tun ọkàn yin ṣe)

# Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi nkan ti o maa n sọ ti o ba ri ẹni tí àdánwò ba kan:

O sọ – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a– pe: Ko si ẹnikan ti o ri ẹni tí àdánwò kan, ti o wa sọ pe: ALHAMDULILLAAH, ALLAZII AAFAANII MIMMAAB-TALAAKA BIH, WA FADDỌLANII ALAA KASIIRIN MIMMAN KHỌLAKỌ TAF'DIILAN, àfi ki àdánwò naa ma kan an, ohunkóhun tí ki baa jẹ.

Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nígbà tí ó bá gbọ ohun kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ ati kíkọ àkùkọ:

O pa ijọ rẹ láṣẹ pe ti wọn ba ti gbọ ohùn kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́, ki wọn o wa iṣọ pẹ̀lú Ọlọhun kúrò lọdọ èṣù ẹni tí a le jina si ike Olohun Ti wọn ba ti gbọ kíkọ àkùkọ, ki wọn o maa tọrọ lọ́wọ́ Ọlọhun nínú ọlá Rẹ.

Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi nkan ti o maa n sọ ati nkan ti o maa n ṣe ti ìbínú rẹ ba lágbára:

O pa ẹni tí ìbínú rẹ bá lágbára láṣẹ pe ki o lọ ṣe aluwala ki o si jókòó ti o ba jẹ pe ori ìdúró ni o wa ki o fi ẹgbẹ le ilẹ̀ ti o ba jẹ pe orí ìjókòó ni o wa ki o si wa iṣọ pẹ̀lú Ọlọhun kúrò lọdọ èṣù ẹni tí a le jina si ike Olohun.

# Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi irun pipe ati àwọn asikiri rẹ

O ṣe irun-pipe pẹ̀lú tar'jiih ati láìní tar'jiih ni sunnah, (ìtumọ̀ tar'jiih ni ki èèyàn o sọ ASH'HADU AN LAA ILAAHA ILLAL-LỌỌH ni ẹẹmeji, ASH'HADU ANNA MUHAMMADAN RỌSUULUL-LỌỌH ni ẹẹmeji pẹ̀lú ohun jẹẹjẹ, èèyàn a tu wa tun gbólóhùn méjèèjì yẹn wi padà ni méjì méjì pẹ̀lú ohun ti o maa lọ sókè) O ṣe ikaamọ ni méjì méjì àti ni ẹyọ kọ̀ọ̀kan lofin Ṣùgbọ́n ko ṣe gbolohun KỌD KỌỌMATIS-SỌLAAT ni ẹyọ kan rárá. O ṣe lofin fún ìjọ rẹ ki ẹni tí ba n gbọ oluperun ki o maa wi ohun ti oluperun ba n wi, àyàfi nibi gbólóhùn HAYYA ALAS-SỌLAAT, ati HAYYA ALAL- FALAAH O ni àlàáfíà láti ọ̀dọ̀ rẹ̀ pé èèyàn maa paarọ méjèèjì pẹ̀lú gbólóhùn LAA HAOLA WA LAA KUWWATA ILLAA BILLAAH O wa sọ pe ẹni tí o ba sọ nígbà tí o n gbọ irun-pipe pe: WA ANA ASH'HADU AN LAA ILAAHA ILLAL-LỌỌH, WA ANNA MUHAMMADAN RỌSUULUL-LỌỌH, RỌDIITU BILLAAHI RỌBBAN, WA BIL ISLAAMI DIINAN, WA BI MUHAMMADIN RỌSUULAN Ẹni tí ó bá sọ ìyẹn, wọ́n maa fi orí ẹsẹ rẹ jin in. O ṣe lofin fun ẹni tí o n gbọ oluperun ki o ṣe asalatu fun Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- lẹyin ti o ba ti parí wiwi ohun ti oluperun n wi tan, o ṣe lofin fun un ki o sọ pe: ALLAHUMMỌ RỌBBA AAZIHID-DAH'WATIT-TAMMAT, WAS-SỌLAATIL-KỌỌ'IMAT, AATI MUHAMMADANIL WASIILATA WAL FADIILAT, WAB' HAS'HU MAKỌỌMAN MAH'MUUDAN, ALLAZII WAHAD'TAHUU (Ire Oluwa Oba ti O ni ipepe ti o pe yi, ati irun ti won gbe duro yi, fun anabi wa Muhammad ni aga wasila ati ola, atipe gbe e dide ni aye eleyin eyiti O ti se adehun re fun un)

O sọ pe wọn kii da adua ti èèyàn ba ṣe láàrin irun-pipe ati ikaamọ padà

# Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi asikiri ninu oṣù zul-hijjat

O maa n ṣe adua lọpọlọpọ nínú ọjọ́ mẹwa zul-hijjat O maa n pàṣẹ pe ki èèyàn o maa ṣe LAA ILAAHA ILLAL-LỌỌHU ati ALLỌỌHU AKBAR ati ALHAMDULILLAAH lọpọlọpọ nínú ẹ

# Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi kika Kuraani

O ti ni eesu Kuraani ti o maa n ka ti kii ja
O maa n ka Kuraani dáadáa pẹ̀lú ẹlẹ, kii kanju rárá, o maa n ka a ni kika ti èèyàn a maa gbọ nkan ti o n wi ketekete ni arafi arafi
O maa n ge kika rẹ, o si maa n dúró nibi aaya kọọkan O maa n ka suurah pẹ̀lú ẹlẹ titi ti yoo fi gun ju èyí tí o gun ju nínú ẹ lọ Ti o ba ti de ibi arafi fa-a-gun yoo fa a gun O maa n fa AR-RAH'MAAN gun O maa n fa AR-RỌHIIM gun O maa n wa iṣọra pẹ̀lú Ọlọhun kúrò lọ́dọ̀ èṣù ẹni tí a lé jina si ikẹ Ọlọhun ni ibẹrẹ kika rẹ, o maa n sọ pe: AUUZU BILLAAHI MINASH-SHAYTOONIR-RỌJIIM (Mo fi Olohun Allah Oba wa iso kuro nibi shaitoon eni egbe eni eko ) O tun le sọ pe: ALLAHUMMO INNII AUUZU BIKA MINASH-SHAYTỌỌNI-R-RAJIIMI MIN HAM'ZIHI, WA NAF'KHI'HI, WA NAF'SIHI
O maa n ka Kuraani ni ìdúró àti ni ìjókòó, ati ni ifi ẹgbẹ le ilẹ, ati ti o ba ni aluwala ati ti ko ba ni aluwala, janaba nìkan ni kii jẹ ki o ka Kuraani
O maa n fi ohùn dídùn ka Kuraani O tun maa nsọ pe: Ko si nínú wa ẹni tí kii ba fi ohùn dídùn ka Kuraani O sọ pe: Ẹ maa ṣe Kuraani ni ọṣọ pẹ̀lú ohùn yin O nífẹ̀ẹ́ si ki o maa gbọ kika Kuraani láti ẹnu ẹlòmíràn Ti o ba ti de ibi aaya iforikanlẹ, yoo sọ pe ALLỌỌHU AKBAR, yoo si fi ori kanlẹ O maa n sọ ni iforikanlẹ rẹ pe: SAJADA WAJ'HII LILLAZII KHỌLAKỌHU WA SỌWWARỌHU, WA SHAKKỌ SAM'HAHU WA BASỌRỌHU BI HAOLIHI WA KUWWATIHI O tun le sọ pe: ALLAHUMMỌH-TUT ANNII BIHAA WIZ' RAN, WAK'TUB LII BIHAA AJ'RAN, WAJ'HAL'HAA LII IN'DAKA ZUKH'RAN, WA TAKỌBBAL'HAA MINNII KAMAA TAKỌBBAL'TAHAA MIN AB'DIKA DAA'UD A o ri i gbà wá lati ọdọ rẹ pe o maa n kabara ti o ba fẹ gbori kúrò ni iforikanlẹ yii, ko si ṣe ataaya, ko si salamọ bi tii wù bi tii mọ

# Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- níbi khutubah rẹ

Ti o ba ṣe khutuba, ojú rẹ méjèèjì maa n pọ́n ni, ti ohùn rẹ yóò sì lọ sókè, ti ìbínú rẹ yóò sì le koko Bii ìgbà tí ó ṣe pé olukilọ fun àwọn èèyàn nípa àwọn ọmọ ogun ti wọn n bọ wa kogun jalu ni O maa n sọ pe: Àwọn ọ̀tá máa wọlé tọ yin wa ni ààrọ̀ ati irọlẹ O tun maa nsọ pe: Wọn gbe èmi àti ọjọ́ alukiyaamọ dide gẹ́gẹ́ bíi méjèèjì yìí O wa n so ìka odun-un-labẹ ati ìka o-ga-ju-wọn-lọ papọ̀ O tun maa nsọ pe: Lẹ́yìn wá ìgbà náà, dájúdájú ọ̀rọ̀ ti o lóore ju ni Tira Ọlọhun, imọna ti o lóore ju ni imọna Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- èyí tí ó burú jù nínú àwọn àlámọ̀rí náà ni àwọn adadaalẹ rẹ, gbogbo adadaalẹ si nìyí anu ni Ko lee ṣe khutuba kankan àfi ki o bẹ̀rẹ̀ rẹ pẹ̀lú yíyin Ọlọhun O maa n kọ àwọn saabe rẹ ni khut'batul haajat: ALHAMDULILLAAH, NAH'MADUHU WA NAS'TAHIINUHU WA NAS'TAG'FIRUH, WA NA'UUZU BILLAAHI MIN SHURUURI AN'FUSINAA WA SAYYI'AATI AH'MAALINAA, MAN YAH'DIL-LAAHU FALAA MUDILLA LAH, WA MAN YUD'LIL FALAA AADIYA LAH, WA ASH'HADU AN LAA ILAAHA ILLAL-LỌỌHU, WA ANNA MUHAMMADAN AB'DUHU WA RỌSUULUH Lẹ́yìn náà ni yoo ka àwọn aaya mẹtẹẹta náà "YAA AYYUHAL-LAZIINA AAMANUU, ITTAKUL-LỌỌHA HAKKỌ TUKỌỌTIH "YAA AYUUHAN-NAASUT-TAKU RỌBBAKUMUL-LAZII KHỌLAKỌKUM MIN NAF'SIN WAAHIDAH "YAA AYYUHAL-LAZIINA AAMANUU, ITTAKUL-LỌỌHA WA KUULUU KAOLAN SADIIDAN O maa n kọ wọ́n ni is'tikhaara nibi gbogbo alaamọri pátá, gẹgẹ bi o ṣe maa n kọ wọ́n ni suurah inú Kuraani, o sọ pe: Ti ẹnikan ninu yín ba ti pinnu láti ṣe nkan, ki o ya ki raka méjì tí kii ṣe ọranyan, lẹyin ìgbà náà ki o wa sọ pe: ALLAHUMMỌ INNII AS'TAKHIIRUKA BI IL'MIKA, WA AS'TAK'DIRUKA BI KUD'RỌTIKA, WA AS'ALUKA MIN FAD'LIKAL-AZIIM, FA INNAKA TAK'DIRU WA LAA AK'DIRU, WA TAH'LAMU WA LAA AH'LAMU, WA ANTA ALLAAMUL-GUYUUB, ALLAHUMMỌ IN KUN'TA TAH'LAMU ANNA AAZAL-AM'RỌ (yoo dárúkọ nkan ti o fẹ) KHAERUN LII FII DIINII WA MAHAASHII WA AAKIBATI AM'RII (tabi o sọ pe: HAAJILIHII WA AAJILIHII) FAK'DUR'HU LII WA YASSIR'HU LII, SUMMỌ BAARIK LII FIIH, WA IN KUN'TA TAH'LAMU ANNA AAZAL-AM'RỌ SHARRUN LII FII DIINII WA MAHAASHII WA AAKIBATI AM'RII (tabi o sọ pe: HAAJILIHII WA AAJILIHII) FAS'RIF'HU ANNII WAS'RIF'NII AN'HU, WAK'DUR LIYAL-KHAERỌ HAESU KAANA SUMMỌ RỌDDINII BIHII

# Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi oorun-sisun ati jiji ati àwọn àlá

A maa sun lórí bẹẹdi nígbà míì, a si tun maa sun lórí rọọgi alawọ nígbà míì ẹ̀wẹ̀, bakannaa a tun maa sun sórí ẹni, a si tun maa sun lórí ilẹ̀ nígbà míì, o tun maa n sun sórí ibùsùn nígbà míràn ẹ̀wẹ̀ Awọ ni wọ́n fi ṣe ibùsùn rẹ, ti wọn rọ epo igi dabinu sínú rẹ, bẹ́ẹ̀ náà ni irọri rẹ ṣe rí Kii sun oorun kọjá odiwọn ti o ni bukaata si Ko si ki n fi oorun dun ara rẹ O maa n sun ni ibẹrẹ oru, o si maa n dìde ni ìparí rẹ Ìgbà míì a maa ṣe aisun ni ibẹrẹ oru tori anfaani àwọn Musulumi Ti o ba wa ni ìrìn-àjò, ti o wa de si aaye kan ni igbẹyin oru lati sinmi, o maa fi ẹgbẹ ọtun rẹ le ilẹ̀ Ti o ba wa sinmi nígbà ti o ba ku diẹ ki asunba o wọlé, o maa gbe apa rẹ sókè, o si maa gbé ori rẹ lórí ọwọ́ rẹ Ti o ba ti wa sun, wọn ko nii ji i títí tí yoo fi jí fúnra rẹ Oju rẹ mejeeji ni o maa n sun, ọkàn rẹ kii sun Ti o ba ti fẹ́ bọ si ori ibùsùn rẹ láti sùn, o maa sọ pé: BIS'MIKALLỌỌHUMỌ AH'YAA WA AMUUTU O maa n pa ọwọ́ rẹ mejeeji papọ̀, lẹ́yìn náà yoo ta ọda si i O maa n ka si ọwọ́ rẹ mejeeji: KUL AUUZU mejeeji ati KUL UWALLỌỌH, lẹyin naa yoo wa fi pa eyi ti o ba le fi pa ni ara rẹ Yoo bẹ̀rẹ̀ lati orí rẹ ati ojú rẹ, ati iwájú ara rẹ Yoo ṣe ìyẹn ni ẹẹmẹta O maa n fi ẹgbẹ ọtun rẹ sun O maa n gbe ọwọ́ rẹ si abẹ ẹẹkẹ ọtun rẹ Lẹyin naa yoo wa maa sọ pe ALLAHUMMỌ KINII AZAABAKA YAOMA TAB'HASU IBAADAKA "Olohun so mi nibi iya Re ni ojo ti O maa gbe erusin Re dide" O sọ fún àwọn kan nínú àwọn saabe rẹ pe: Ti o ba ti fẹ́ sùn, ṣe aluwala bii aluwala rẹ fun irun, ki o wa fi ẹgbẹ ọtun rẹ le ilẹ̀, ki o wa sọ pe: ALLAHUMMỌ INNII AS'LAM'TU NAF'SII ILAEK, WA WAJJAH'TU WAJ'HII ILAEK, WA FAWWAD'TU AM'RII ILAEK, WA AL'JAH'TU ZAH'RII ILAEK, RỌG'BATAN WA RAH'BATAN ILAEK, LAA MAL'JAHA WA LAA MAN'JAA MIN'KA ILLAA ILAEK, AAMAN'TU BI KITAABIKAL-LAZII AN'ZAL'TA, WA BI NABIYYIKAL-LAZII AR'SAL'TA, àwọn gbólóhùn náà ni ki o wi kẹyin, ti o ba kú ni oru ọjọ́ naa, o kú lórí adamọ ni tii ṣe Isilaamu. Ti o ba dìde ni oru, o maa sọ pe: ALLAHUMMỌ RỌBBA JIB'RIILA WA MIIKAA'IILA WA IS'RỌỌFIIL, FAATIRỌS-SAMAAWAATI WAL-AR'DI, AALIMAL-GAEBI WASH-SHA'HAADAT, AN'TA TAH'KUMU BAENA IBAADIKA FII MAA KAANUU FIIHI YAKH'TALIFUUN, IH'DINII LIMAKH-TULIFA FIIHI MINAL-HAKKI BI IZ'NIK, INNAKA TAH'DII MAN TASHAA'U ILAA SIRỌỌTIN MUS'TAKIIM (Oluwa Jubril ati Mikail ati Israafiil, Ire ti O da sanmo ati ile ti O je olumo nipa ohun ti o wa nikoko ati eyiti o han. Ire ni yio se idajo laarin awon eru Re nibi ohun ti won se iyapa enu si, fimi mona nibi ohun ti won yapa enu si ninu otito pelu iyonda Re, dajudaju Ire ni o maa nfi eniti o ba wu O mona losi oju ona ti o to) Ti o ba taji lójú oorun, o maa n sọ pe: ALHAMDULILLAAH, ALLAZII AH'YAANAA BAH'DA MAA AMAATANAA WA ILAEHIN-NUSHUUR (Eyin ti Olohun Oba ni, eniti O ji wa leyin igba ti O pa wa, Oun naa si ni yoo gbe wa dide ni alukiyaamo) O si maa n run pako, o tun le ka aaya mẹwa ti o gbẹyin suurat AAL IM'RAAN O maa n ji nígbà tí àkùkọ ba kọ, Yoo wa ṣe ALHAMDULILLAAH, yoo tun ṣe ALLỌỌHU AK'BAR, yoo tun ṣe LAA ILAAHA ILLAL-LỌỌHU, yoo wa ṣe adua O sọ pe: Ala gidi láti ọ̀dọ̀ Ọlọhun ni, ala burúkú láti ọ̀dọ̀ èṣù ni, ẹni tí ó ba la àlá kan ti o wa korira nkankan ninu ẹ, ki o yaa ta ọda si apa ọtun rẹ ni ẹẹmẹta, ki o wa sọ AUUZU BILLAAHI MINASH-SHAYTOONIR-RỌJIIM, àlá naa ko nii ni i lára, ko si gbọdọ rọ ọ fún ẹni kankan, ti o ba wa la àlá gidi, ki o maa dunnu, ki o si ma rọ ọ fún ẹni kankan àyàfi ẹni tí ó ba nífẹ̀ẹ́.

O pàṣẹ fún ẹni tí ó ba ri nkan ti o korira lójú àlá pé ki o yi kúrò ni ẹgbẹ ti o fi sùn tẹ́lẹ̀, ki o si ki irun

# Ìlànàa rẹ, kí ìkẹ́ Ọlọ́hun àti ọlàa rẹ kó máa bá a, níbi àdámọ́, ìmúra, ìríṣí, àti ẹ̀ṣọ́.

Ó jẹ́ ẹni tíí máa ń fín tùràrì sára lọ́pọ̀lọ́pọ̀, ó sì nífẹ̀ẹ́ rẹ̀, kò sì kíń hánnà rẹ̀. Èyí tó nífẹ̀ sì jù nínú tùràrí ni "Al-Misk". Ó fẹ́ràn orín, a sì máa rún orín nígbà tí kò láàwẹ̀ àti ìgbà tó bá ń gbààwẹ̀. A máa run orín nígbà tí ó bá tají láti ojú orun, àti nígbà tí ó bá fẹ́ ṣe àlùwàlá, àti nígbà tí ó bá fẹ́ kírun, àti nígbà tí ó bá fẹ́ wọlé. Ó jẹ́ ẹni tíí máa ń lé tìróo, kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ̀hun kó máa bá a, ó ṣọ wípé: Èyí tó lóore jù nínú àwọn tìróò yín ni Al-Ithmid, a máa gbé ojú yọ, a sì máa múrun hù. Ó jẹ́ ẹni tíí máa ń yarun fúnra rẹ̀ nígbà míì, Aishah a sì máa bá a yà á nígbà míì. Ìlànà rè níbi fífá irun jẹ́: fífi irun rẹ̀ sílẹ̀ tàbí mímú ú kúrò tán patapata. Wọn ò ṣì sọ́ fífá irun làti ọ̀dọ̀ re àyàfi ní àsìkò ìjọsìn (Hajj). Irun rẹ ju "jummah (irun ti o da wale debi eti)" lo, sugbon ko to "wafro (irun ti o da wale koja eti)" Irun jummah re máa n kan eti. Ó sì kọ̀ fún wa níbi gígẹ irun apá kan dápá kan sì. Ó sọ wípé: ẹ yapa àwọn elebo, ẹ dá irùngbọ̀n yín sí, kí ẹ sì ge túnbọ̀mu yín. Ó jẹ́ ẹni tíí máa ń wọ èyí tó bá rọ̀ o lọ́rùn nínú aṣọ: nígbà míràn a máa wọ èyí tí a ṣe látara irun, nígbà míràn èyí tì a ṣe látara òwú, tàbí èyí tí a ṣe látara eṣo "kattan nígbà mìràn. Èyí tí ó nífẹ̀ẹ sí jù nínú aṣọ ni ẹ̀wù. Àti pé ó wọ aṣọ gbàgẹ̀rẹ̀ Yẹmẹn, àti aṣọ gbàgẹ̀rẹ̀ aláwò ewé, O wọ aṣọ gbàgẹ̀rẹ̀ tí a là níwájú ati àwọ̀lékè ẹ̀wù àti ṣòkòtò àti ìró àti aṣọ àti bata alawo, àti bàtà, àti láwàní. Ó jẹ́ ẹni tíí máa ń wé láwàní aláwè mágbọ̀n. A máa sọ ọwọ́ láwàní sílè lẹ́yìn nígbà míràn, a sì máa gbé ṣíṣe bẹẹ jù sílẹ̀ nígbà míràn. Ó wọ aṣọ dúdú, ó

wọ aso tòkètilẹ̀ pupa, Ìtùmò "hulla" ni ìró àti ìdà bora. Ó wọ òrùka fàdákà, ó jẹ́ ẹni tí ó maa n tí orí òrùka sínú. Tí ó bá ra aṣọ tuntun yóò dá orúkọ rẹ̀ O sọ pe: "Ìrẹ Ọlọ́hun, Ìrẹ ni O dá ẹ̀wù yì fún mi, tàbí aṣọ tàbí láwàní, mo ń béèrè lọ́dọ̀ Rẹ oore rẹ̀ àti oore nǹkan ti wọn torí rẹ ṣe é, mo sì ń fi Ọ́ wá iṣọ kúrò níbi aburú rẹ̀ àti aburú nǹkan ti wọn torí rẹ ṣe é. "Ó jẹ́ ẹni tí ó bá fẹ́ wọ ẹ̀wù yóò bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú apá ọ̀tún.
"Bíbẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ọtun jẹ ẹ lógún níbi wíwọ bàtà rẹ̀, àti yíya irun rẹ̀, àti ìmọ́ra rẹ̀, àti gbígbà rẹ̀, àti fífún rẹ̀. "
"Ìlànà rẹ̀- kí ìkẹ́ Ọlọ́hun àti ọlà Rẹ máa ba a- nígbà tí ó bá sín, yóò fi ọwọ́ rẹ̀ tàbí aṣọ rẹ̀ bo ẹnu rẹ̀, yóò sì fi rẹ ohùn rẹ̀ nílẹ̀. "
"Ó jẹ́ ẹni tí ó pọ̀ ní ìtìjú ju wúńdíá lábẹ́ gàgá ààbò rẹ̀ lọ. "
"Ó jẹ́ ẹni tíí máa ń rẹẹrin si ohun tí a máa ń rẹẹrin si. " "Ògóńgórí ẹ̀ẹ̀rín rẹ̀ ni ẹ̀ẹ̀rín músẹ́, èyí tó ga jù nínú ẹ̀ẹ̀rín rẹ ni kí eyín ọ̀gàn rẹ̀ kó hàn síta. " "Ẹkún rẹ́ jẹ́ irú ẹ̀ẹ̀rín rẹ̀, kò kí n wu tàbí gbóhùn sókè, bósejẹ́ wípé ẹ̀ẹ̀rín rẹ ó kí n ṣe ẹ̀ẹ̀rín kèé kèé. " "Ṣùgbọ́n ojú rẹ̀ a maa damijé, a ó sì máa gbọ́ sísọ pì pì àyà rẹ̀."

# "Ìlànà re, ki ìkẹ́ Ọlọ́hun àti ọlà Rẹ̀ máa ba a- níbi ìkíni àti ìgba ìyọ̀ǹda. "

"Ó ń bẹ nínú ìlànà rẹ̀, kí ìkẹ́ Ọlọ́hun àti ọlà Rẹ máa ba a, sisalamọ nígbà tí ó bá dé sí inú àkójọ, " "Àti sisalamọ nígbà tí ó bá fẹ́ kúrò lọ́dọ̀ wọn, " "O pàṣẹ fífọ́n salamọ ká. " O sọ pe: "Ọmọ kékeré ni yóò sálámọ̀ sí àgbàlagbà, ẹni tó ń ré kọjá ní yoo sálámọ̀ sì ẹni tó wà níkàlẹ̀, ẹni tó wa lórí nǹkan ìgùn ni yóò sàlámọ̀ sì ẹni to ń fẹsẹ̀ rìn, àwọn òǹkà kékeré ni yóò sàlámọ̀ sì àwọn pupo " "O máa ń kọ́kọ́ sálámọ̀ sí ẹni tí ó bá pàdé rẹ̀. " "Tí ènìyàn bá sálámọ̀ si i, yóò fi èyí tó ṣe déédéé rẹ̀ dá a padà, tàbí èyí tí ó lóore jù ú lọ ní kíákíá àyàfi ti o ba ni ìdíwọ́; " "Fún àpẹrẹ: Irun tàbí gbigbọ bukaata. " "Ó máa ń bẹ̀rẹ̀ báyìí pé: " "As-salaamu alaykum warahmatul Lọọhi wabarọkaatuh" "Ó máa ń kọ kí olùbẹ̀rẹ̀ sálámọ̀ sọ pe: "Alaykas salaam", "O máa ń dáhùn sálámọ̀ ẹnití ó sálámọ̀ pẹ̀lú: " "Wa alaykas salaam" pẹ̀lú "waaw"
"Ó wà nínú ìlànà rẹ̀ níbi sísálámọ̀ sí ọ̀pọ̀lọpọ̀ èèyàn, àwọn tó ṣe wípé sálámọ̀ kan kò leè tó fún wọn, ki o sálámọ̀ lẹ́ẹ̀meta. "
"Ó wà nínú ìlànà rẹ̀ pé ẹni tó bá wọ máṣáláàṣí, yóò kọ́kọ́ kí ìrun rákà méjì láti kí máṣáláàṣí, lẹ́yìn náà yóò wàá sálámọ̀ sì àwọn jànmọ́ọ̀n. "
"Kò kí n dáhùn sálámọ̀ pẹ̀lú ọwọ́ rẹ̀, tàbí orí rẹ̀, tàbí ọmọnìka rẹ̀ àfi nígbà tí ó bá wà lórí ìrun; " "Torí wípé ó dáhùn lórí ìrun pẹ̀lú ìtọ́ka " "Bákan náà ó ré kọjá àwọn ọmọ kéékèèké ó sì sálámọ̀ sí wọn, " "Bákan náà ó ré kọjá àwọn obìnrin ó sì sálámọ̀ sí wọn, " "Àtipé àwọn sàábé a máa kúrò níbi tí wọ́n ti kí Jímọ̀n tí wọ́n ó sì ré kọjá ìyá arúgbó lójú ọ̀nà, wọn ó sì sálámọ̀ si i. " "A máa fi sálámọ̀ ránṣẹ́ si èèyàn, a sì máa fi jíṣẹ́, " "Tí wọ́n bá fi sálámọ̀ jíṣẹ́ fún un, yóò da a padà fún ẹni ti o fi jíṣẹ́ àti ẹni tí ó fi ṣọwọ́ si i. " "Wọn béèrè lọ́wọ́ rẹ̀ pé: tí ènìyàn (musulumi) bá pàdé ọmọ ìyá rẹ̀, ǹjẹ́ ó le tẹ̀ fún un bí? Ó dáhùn pé: Rárá, wọ́n tún béèrè pé: ṣe ó lè di mọ́ ọn tàbí fẹnu kò ó ní ẹẹkẹ? Ó dáhùn pe: rárá, wọ́n tún béèrè pé: ṣe ó lè bà á lọ́wọ́? Ó dáhùn pé: Bẹ́ẹ̀ni. " "Kò kí ń já lu àwọn ará ilé rẹ̀ lójijì ní ẹni tó fi ń fura sí wọn. " "A máa sálámọ̀ sí wọn, "
"Ó jẹ́ eni tó bá wọlé yóò bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ìbéèrè tàbí bíbéèrè wọn. "
"Ti o bá wọlé tọ̀ àwọn aráalé rẹ̀ lóru, yóò sàlámọ̀ tí ẹni tí kò sùn yóò gbọ́, tí kò sì nii jí ẹni tí ó ti sùn. "
"Ó wà nínú ìlànà rẹ̀ pé olùgbàyọ̀ǹda (láti wọlé) tí wón bá sọ fún un wí pé: Taani ọ́? Ki o dáhùn pé: Lágbájá ọmọ lágbájá ni, tàbí ki o dàrúkọ bàbá àbí ìyá lágbájá, tàbí ki o dárúkọ àlàjẹ́ rẹ̀, kò gbọ́dọ̀ sọ pé: Èmi. "
"Ó jẹ́ ẹni tí ó bá fẹ́ gba ìyọ̀ǹda yóò gbà a lẹ́ẹ̀meta; tí wọn kò bá yọ̀ǹda fún un yóò padà. "
"Ó máa ń kọ́ àwọn sàábé rẹ̀ pe sálámọ̀ ṣíwájú ìyọ̀ǹda. "
"Tí ó bá wá sí ẹnu ìlẹ̀kùn àwọn èèyàn (láti gba ìyọ̀ǹda fún wíwọlé) rẹ̀, kò nii dojú kọ ìlẹ̀kùn. " "Ṣùgbọ́n ó máa ń bọ́ sí ẹ̀gbẹ́ ọ̀tún tàbí òsì rẹ̀" O sọ pe: "Ìyọ̀ǹda ò ṣàdédé sí bi ko ṣe pé kí ojú má baa rí ohun tí kò yẹ "

# "Ìlànà rẹ̀, kí ìkẹ́ Ọlọ́hun àti ọlá Rẹ máa bá a- níbi ọ̀rọ̀ àti ìdákẹ́, àti níbi sisọ ọrọ, àti ìṣẹ̀ṣà àwọn gbólóhùn àti orúkọ "

"Ó jẹ́ ẹni tí ó dá lahọn jù nínú àwọn ẹ̀dá atí ẹni tí ọ̀rọ̀ rẹ̀ dùn jùlọ, tí ọ̀rọ̀ rẹ já geere jùlọ, tí èdè ahọ́n rẹ̀ sì dùn jùlọ. "
"Ó jẹ́ ẹni tí ó máa ń dúnní mọ́ ìdákẹ́ jẹ́jẹ́, tí kò sì kí n sọ̀rọ̀ láìnídìí. " "Kii dá sí ohun tí kò kan an, kìí sii sọ̀rọ̀ láìnídìí. "
"Ó máa n sọrọ pẹ̀lú àdìtú, àti pẹ̀lú ọ̀rọ̀ ìfọ́síwẹ́wẹ́ tí yóò ṣeé kà lẹ́yẹẹyọ, kò jẹ ẹni tí máa ń sọ̀rọ̀ bere bere ti wọn o nii ri i há, kò sì kíń sọ̀rọ̀ lẹ́yẹẹyọ tí yoo maa dakẹ lẹẹmẹwaa."

"Ó máa ń ṣẹ̀ṣà ọ̀rọ̀ nígbà tí ó bá ń sọ̀rọ̀, Ó sì máa ń ṣẹ̀ṣà èyí tí ó rẹwà jù nínú àwọn gbólóhùn léyì tí ó jìnnà sí gbólóhùn àwọn ẹni agọ̀ àti ìbàjẹ́. "
"Ó kórira lílo gbólóhùn àpọ́nlé fún ẹni tí kò lẹ́tọ̀ọ́ si i, " "Àti lílo gbólóhùn àbùkù fún ẹni tí kò lẹ́tọ̀ọ́ si i, " "Ó kọ kí a sọ fún munafiki (olójú èjì) pé: asíwájú, ó kọ sísọ Abu Jahl (Baba Agọ̀) ní Abul Hakam (Bàbá Ọgbọ́n), àti ká pe ọba ní: ọba gbogbo ọba tàbí àrólé Ọlọ́hun. " "Ó tọ́ka ẹni tí Èṣù bá gbá mú lọ síbi ki o sọ wípé: Bismillah, " "Kò gbọdọ̀ ṣẹ́bi le e, tàbí ki o bu u, kò sì gbọdọ̀ sọ wípé: èṣù pofo, àbí ohun ti o jọ ó. " "Ó fẹ́ràn orúkọ ti o rẹwà, " "Ó pàṣẹ tí a bá fẹ́ fi iṣẹ rán òjíṣẹ́ si i, kí ó jẹ́ ẹni tí orúkọ rẹ̀ rẹwà, olójú tútù, a si máa mú ìtumọ̀ jáde látara orúkọ. " "Ó máa ń wo àjọṣe tó ń bẹ láàrin orúkọ àti ẹni tí ń jẹ ẹ. " O sọ pe: "Dájúdájú èyí tí Ọlọ́hun nífẹ̀ẹ́ sí jù nínú àwọn orúkọ yín ni: Abdullah (Ẹrú Ọlọ́hun), Abdur Rahman (Ẹrú Ọlọhun Ọba Àjọkẹ́ Ayé), èyí tó fi ń jódodo jù nínú wọn ni: Haarith (Dákodáko), Hammam (Akínkanjú), èyí ti o fi ń burú jù ni: Harb (Ogun), Murrọh(Ìkorò). " "Ó pààrọ̀ orúkọ Aasiyah (Ẹlẹ́ṣẹ̀ lóbìnrin), Ó sọ wípé: Jamiilah ni orúkọ rẹ. " "Ó pààrọ̀ orúkọ Asram sí Zur'ah, " "Nígbà tí ó dé Mẹ̀dínà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Yathrib nígbà náà, o pààrọ̀ rẹ sí Tiibah. "
"Ó jẹ́ ẹni tí ó máa ń pe àwọn sààbé rẹ̀ ni "Abu Lágbájá", o le pe ọmọ kékeré naa ni "Abu Lágbájá", o sọ àwọn kan nínú àwọn ìyàwó rẹ naa ni "Ummu Lágbájá. "
"Ó jẹ́ ohun tó wà nínú ìlànà rẹ̀, kí ìkẹ́ Ọlọ́hun àti ọlà Rẹ máa ba a, ki o maa pe ẹni tí o ba bímọ ni" Abu Lágbájá". "Àbí ẹni tí kò ba bímọ, o sọ pé: " "Ẹ máa jẹ́ orúkọ mi, ẹ má ṣe jẹ kun'ya mi (Abu Lágbájá), bí mo ti ṣe n jẹ ẹ." O si tun kọ ki wọn pa orúkọ "al-‘ishā’i" tì, ki orúkọ "al-‘atama" wa leke rẹ. O si tun kọ mimaa pe eso inabi ni karmu, o wa sọ pé: Nkan ti n jẹ "al-Karmu" ni: Ọkan olugbagbọ ododo. O si tun kọ ki wọn máa sọ wipe: Wọn ro ojo fún wọn latara irawọ kan bayi, ati sísọ pe: Nkan ti Ọlọhun ati iwọ ba ti fẹ. Ati ki wọn maa búra pẹlu nǹkan miran lẹyin Allāh. Ati kuro nibi mimaa bura lọpọlọpọ. Ati ki o maa sọ nibi ibura rẹ wipe: Yahūdi ni oun - ati nkan ti o jọ bẹ́ẹ̀- ti oun ba ṣe nkan bayii, ati ki olówó máa sọ fún ẹrú rẹ wipe: Ẹrúkunrin mi ati ẹrubinrin mi. (‘abdī wa ’amatī). Ati ki ọmọnìyàn máa sọ wípé: Ẹ̀mí mi bajẹ, tabi eṣú ti ṣe oriburuku. Ati kuro nibi gbolohun: Oluwa mi, ṣe aforinji fún mi ti O ba fẹ. O si tun kọ kuro nibi bibu igba, ati kuro nibi bibu atẹgun, ati bibu ibà, ati bibu akukọ. Ati kuro nibi pipepe pẹlu ipepe igba aimọkan; Gẹ́gẹ́ bii pipepe lọ sí awọn idile, ati ṣíṣe ẹyamẹya nítorí ẹ.

# Ilana rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- nibi irin rẹ ati ìjókòó rẹ

O jẹ ẹnití o ṣe wipe ti o ba rin, o maa n fì sí iwájú gẹgẹ bii wipe o n sọkalẹ lati ibi tí ààyè ti da walẹ. O si tun jẹ ẹnití irin rẹ fi n yara julọ ninu awọn eeyan ti o si tun dara julọ ni irin ti o si tun balẹ julọ ni irin.
O jẹ ẹnití máa n rin lai wọ bàtà àti ni ẹnití o wọ bata.
O si tun jẹ ẹnití máa n gun ràkúnmí ati ẹsin, ati ibaaka ati kẹtẹkẹtẹ. O si tun maa n gun ẹṣin ti o ni gàárì ni igba míràn, o sí máa n gun eyiti ko ni nkankan lori ni igba miran. O si tun jẹ ẹnití máa n gbe èèyàn sí ẹyin ati iwájú lori nkan ọ̀gùn.
O si tun jẹ ẹnití máa n jokoo ni ori-ilẹ ati lori ẹni ati lori itẹ.
O si tun jẹ ẹnití máa n rọgbọku lori ìrọ̀rí. Ati pe nigba miran o maa n rọgbọku sí apá alaafia rẹ, a sì tún máa rọgbọku pẹlu ọtun rẹ ni igba míràn. O si tun jẹ ẹnití máa n jo ìjókòó ìlóṣòó, o si tún máa n fi ẹyin le ilẹ nígbà míràn. Ati pe nigba miran o maa n gbe ọkan ninu awọn ẹsẹ rẹ mejeeji lori ìkejì. O sí jẹ ẹnití máa n fi ara ti awọn kan ninu awọn saabe rẹ ti o ba rẹ ẹ nigbati o ba bukaata sí i.
O si tun kọ kí ọmọnìyàn jókòó laarin iboji ati oòrùn
O si tun kọ fun awọn ti wọn ba wà ni ìjókòó ki iranti Ọlọhun má sii ni ìjókòó wọn, o sọ pe: Ẹnití o ba jókòó ni ìjókòó kan ti wọn kò rántí Ọlọhun Ọba níbẹ̀, yoo jẹ abamọ fun un ni ọdọ Ọlọhun. Nkan ti n jẹ "At-tirotu" ni: Abamọ. O sọ pe: Ẹnití o ba jókòó sí ìjókòó kan ti ọrọ rẹ si pọ nibẹ, ti o wa sọ kí o to dide kuro ni ìjókòó rẹ yẹn pe: "Subhaanaka Allaahummo wa bihamdika, ash'hadu an laa ilaaha illaa anta, astagfiruka wa atuubu ilaeka", ayaafi ki wọn ṣe aforijin fún un gbogbo nkan ti o waye ni ìjókòó rẹ yẹn.

# Ìlànà rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - ati ilana awọn saabe rẹ ni iforikanlẹ ọpẹ nígbà tí oore ọtun ti maa n dun ni ninu ba ṣẹlẹ tabi ìyà kan ba kúrò.

Wọn sí fún un ni ìró idunnu - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - lori bukaata kan, o si wolẹ l'ẹniti o fi ori kanlẹ fún Ọlọhun.

# Ìlànà rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - nibi wiwa ọna àbáyọ sí ibanujẹ ati ifooro.

O jẹ ẹnití máa n sọ nígbà ibanujẹ pé: Laa ilaaha illaal Loohul Aziimul Aliim, laa ilaaha illaal Loohu Robbul Arshil aziim, laa ilaaha illaal Loohu Robbus samaawaatis sab'hi wa Robbul ar'di wa Robbul arshil kariim O si tun jẹ ẹnití o ṣe wipe ti àlámọ̀rí kan ba n ba a ni inu jẹ yíò sọ pé: Yaa Hayyu yaa Kọyyuumu bi rahmatika astagiis O sọ pe: Awọn adua ẹnití o wa ninu ibanujẹ: Allaahummọ, rahmataka arjuu, falaa takil'nii ilaa nafsii tọrfata aen, wa as'lih lii shah'nii kullahuu, laa ilaaha illaa anta.
O si tun jẹ ẹnití o ṣe wipe ti àlámọ̀rí kan ba n ba a ni inu jẹ yíò lọ ki irun.
O sọ pe: Ìbànújẹ́ kan o nii ṣẹlẹ sí ẹrú kan ti yíò wàá máa tara bẹ́ẹ̀ sọ pe: "Allaahummọ innii abduka, ibnu abdika, ibnu amatika, naasiyatii biyadika, maadin fiyya hukmuka, adlun fiyya kọdọọ'uka, as'haluka bikullis min uwa laka, sammaeta bihii nafsaka, ao anzaltahuu fii kitaabika, ao allamtahuu ahadan min halkika, awis tah'sarta bihii fii ilmil gaebi indaka, an taj'halal Kur'aanal aziima rọbiiha kọlbii wa nuurọ sọdrii, wa jalaa'ha huznii, wa zahaaba hammii", ayaafi ki Ọlọhun O mu ibanujẹ rẹ ati ifooro rẹ lọ, kí O si tun fi idunnu rọpo rẹ fun un. O si tun jẹ ẹnití máa n kọ wọn ni igbati ipaya bá ṣẹlẹ ki wọn maa sọ pe: Auuzu bikalimaatil Laahit taammọt min gọdọbihii, wa ikọọbihii, wa sharri ibaadihii, wa min amazaatish shayaatiin, wa auuzu bika Rọbbi an yahduruun. O sọ pe: Ko si ẹnì kankan ti àjálù kan o ṣẹlẹ sí i ti yíò wá máa sọ wipe: “Innaa lil Laahi wa innaa ilaehi rọọjihuun, Allaahummọ uh'jur'nii fii musiibatii, wah'luf lii haeran min'haa", ayaafi ki Ọlọhun O san an ni ẹsan nibi àdánwò rẹ, ki O si tun fi èyí tí o daa ju u lọ rọpo fún un.

# Ìlànà rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - nibi irin-ajo.

O jẹ ẹnití o maa n nífẹ̀ẹ́ sí jijade lọ sí irin-ajo ni ibẹrẹ ojúmọmọ, ati ni ọjọ alamisi.
O si tun jẹ ẹnití máa n kọ fún ẹnití n ṣe irin-ajo ni oun nikan ki o maa rin ni oru, o si tun maa n kọ kí ẹnikan o da irin-ajo ṣe.
O si tun pa awọn oluṣe irin-ajo laṣẹ wipe ti wọn ba ti jẹ mẹta kí wọn o fi ẹnikan ninu wọn ṣe olori.
O si tun jẹ ẹnití o ṣe wipe ti o ba ti gun nkan ọgun rẹ yíò gbé titobi fún Ọlọhun ni ẹẹmẹta, lẹyin naa yíò sọ pé: "Subhaanal lazii sahhọrọ lanaa aazaa wa maa kunnaa lahuu muk'riniin, wa innaa ilaa Rọbbinaa lamun'kọlibuun". Lẹyin naa yoo wa maa sọ pe Allaahummọ innii as'haluka fii safarii aaza al'birrọ wat takwaa, wa minal amali maa tardọọ, Allaahummọ awwin alaenaa safarọnaa aazaa wat'wi annaa buh'dah, Allaahummọ antas sọọhibu fis safar, wal haliifatu fil ah'l, Allaahummọs hab'naa fii safarinaa, wah'lufnaa fii ah'linaa". O sí tun jẹ ẹnití o ṣe wipe ti o ba ṣẹri pada lati irin-ajo yíò ṣe alekun gbólóhùn: Aayibuuna taa'ibuuna aabiduuna li Rọbbinaa haamiduun. O si tun jẹ ẹnití o ṣe wipe ti o ba ti gun awọn oke yíò gbé titobi fún Ọlọhun. Ti o ba sọkalẹ sí àwọn àfonífojì yíò ṣe afọmọ. Arakunrin kan sọ fún un pé: Mo fẹ ṣe irin-ajo, o sọ pe: Mo n pa ọ ni aṣẹ pẹlu ibẹru Ọlọhun, ati gbigbe titobi fún Ọlọhun ni gbogbo ààyè ti o ba ti ga. O si tun jẹ ẹnití o ṣe wipe ti al-fajari ba yọ bá a ni irin-ajo yíò sọ pé: "Sammaha saamihun bihamdil Laahi wa husni balaahihii alaenaa, Rọbbanaa sọọhibnaa wa afdil alaenaa aaizan bil Laahi minan naar". O ṣe tun jẹ ẹnití o ṣe wipe ti o ba sìn awọn Saabe rẹ sí ọnà irin-ajo yíò máa sọ fún ọkọọkan ninu wọn wípé: "Astaodihul Lọọha diinaka wa amaanataka wa hawaatiima ah'maalika". O sọ pe: Ti ẹnikẹni ninu yin ba de sí ààyè kan, kí o yaa sọ pe: "Aʿūdhu bi kalimātil lāhi at-Tāmmāti min sharri mā khọlaqọ", dajudaju nkankan ko nii ni í lara titi yíò fi gbera kuro níbẹ̀.
O si tun maa n pa arìnrìn-àjò ni aṣẹ wipe ti o ba ti gbọ bukaata rẹ tan ni àjò rẹ, ki o yara pada sí ọdọ àwọn ará ile rẹ.
O si tun maa n kọ fún obìnrin ki o ṣe irin-ajo lai sí eleewọ pẹlu rẹ, koda ki o ma ju mẹẹli mejila lọ. O si tun kọ ki wọn ṣe irin-ajo pẹlu Alukuraani lọ sí ilu àwọn ọta, ni ẹniti n bẹ̀rù ki ọwọ ọta o ma tẹ ẹ. O si tun kọ gbigbe Musulumi laarin awọn ọṣẹbọ nígbà tí o ba kapa láti kúrò níbẹ̀. O sọ pe: Emi bọpa-bọṣẹ kuro lọdọ gbogbo Musulumi ti o ba n gbe laarin awọn ọṣẹbọ. O sọ pe: Ẹnití o ba ro papọ mọ ọṣẹbọ, ti o si tun gbe pẹlu rẹ, oun naa ti da gẹgẹ bii rẹ.
Ìrìn-àjò rẹ jẹ irin-ajo mẹẹrin: Ìrìn-àjò fun hijirah, irin-ajo fún jijagun sí oju-ọna Ọlọhun, oun naa ni o si pọ ju, irin-ajo fún Umurah, irin-ajo fún Hajj.
O si tun maa n din irun olopoo mẹẹrin ku ni irin-ajo rẹ, ti yíò sì ki i ni rakaa meji lati ìgbátí o ba ti jade titi yíò fi ṣẹri pada. O si tun jẹ ẹnití máa n fi irun rẹ mọ (ni irin-ajo) lórí ọranyan nìkan ayaafi witiri ati sunna alfajari.
Ko sì fi silẹ fún ìjọ rẹ odiwọn irin kan pato fún didin irun ku ati jija aawẹ.

Ko sì sí ninu ilana rẹ kiki irun meji papọ l'ẹniti o wa lori nkan ọgun ni irin-ajo rẹ, ko sì tún sí kiki irun papo ni igba isọkalẹ rẹ, bi kii ṣe wipe kiki papọ máa n wáyé nígbàtí o ba fẹ yara rin irin-ajo, ati nigba ti o ba gbera kété lẹyin irun. O jẹ ẹnití o ṣe wipe ti o ba gbera lọ irin-ajo ṣíwájú ki oorun tó yẹ àtàrí, yíò lọ irun aila lara di àsìkò alaasari, lẹyin náà yíò sọkalẹ, yíò sì ki mejeeji papọ. Ti oorun ba yẹ àtàrí ṣíwájú ki o to gbera lọ irin-ajo, yio ki irun aila, lẹ́yìn náà yíò gun nkan ọgun rẹ. O si tun jẹ ẹnití o ṣe wipe ti o ba tete gbera irin-ajo, yíò lọ irun magribi lara titi yíò fi ki i papọ pẹlu ishai ni àsìkò ishai. O si tun maa n ki irun aṣegbọrẹ ni oru ati ọsan ni ori nkan-ọgun rẹ ni irin-ajo sí eyikeyi ibi tí o ba da oju rẹ kọ. Yíò waa rukuu, yíò sì tún sujada lori rẹ pẹ̀lú itọka. O sí máa n ṣe iforikanlẹ rẹ ni nkan ti yíò lọ silẹ ju rukuu rẹ lọ.

O ṣe irin-ajo ninu Ramadan ti ko si gba aawẹ, o waa sa àwọn saabe rẹ l'ẹsa laarin àlámọ̀rí meji (gbigba aawẹ tabi titu ẹnu).

O jẹ ẹnití maa n wọ ibọṣẹ alawọ ni irin-ajo ni gbogbo igba tabi ni ọpọlọpọ awọn ìṣesí rẹ.

O si tun kọ ki ọkunrin o maa fi oru wọle tọ àwọn ará ile rẹ nígbàtí o ba ti fi wọn sílẹ fún ọjọ pipẹ (ti o ba ṣe irin-ajo).

O sọ pe: Awọn malaika o nii wa pẹlu ikọ kan ti aja ba wa pẹlu wọn tabi aago. O tun jẹ ẹnití o ṣe wípé ti o ba ti ti àjò de, yíò kọkọ de mọsalaasi, ti yíò si ki irun rakaa meji nibẹ. O si jẹ ẹnití wọn maa n gbe awọn ọmọde ninu awọn ara ile rẹ pàdé rẹ.

O si tun jẹ ẹnití maa n di mọ ẹniti o ba n ti ìrìn-àjò bọ̀, ti yíò si fi ẹnu ko o ni ẹ̀ẹ̀kẹ́ rẹ ti o ba jẹ ọkan ninu awọn ara-ile rẹ.

# Ìlànà rẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) nipa ìtọ́jú aláìsàn, ati lilo oogun, ati mimaa bẹ alaisan wo.

Ninu ìlànà rẹ naa ni lilo oogun fun ara rẹ, ati pipaṣẹ pẹlu rẹ fun ẹniti aisan ba n ṣe ninu awọn ara ile rẹ ati awọn saabe rẹ.

O sọ pe: Ọlọhun ko sọ aisan kankan kalẹ ayaafi ki O sọ iwosan kalẹ fún un. O sọ pe: Mo pe ẹyin ẹrusin Ọlọhun, ẹ maa lo oogun.

Ìwòsàn rẹ ṣiṣẹ fun aisan iran mẹta: Akọkọ rẹ ni: Pẹ̀lú lilo awọn egboogi àdánidá, ẹlẹẹkeji ni: Pẹ̀lú lilo awọn oogun ati ọdọ Ọlọhun, ẹlẹẹkẹta ni: Pẹ̀lú dida mejeeji papọ.

O si tun kọ lati maa fi ọti ṣe oogun ìwòsàn, o si tun kọ lati maa fi nnkan ẹlẹgbin ṣe oogun iwosan.

O si tun jẹ ẹnití maa n bẹ ẹniti o ba n ṣe aisan ninu awọn saabe rẹ wo, o bẹ ọdọmọdekunrin kan wo ninu awọn ti wọn fun ni tira, o si tun bẹ ẹgbọn bàbá rẹ̀ ti o jẹ ọṣẹbọ wo. O si fi isilaamu lọ awọn mejeeji, yahuudi naa si gba Isilaamu ti ẹgbọn baba rẹ o si gba Isilaamu.

O si tun jẹ ẹnití o maa n sunmọ alaisan, ti yio si jokoo si igberi rẹ, ti yio waa maa bi i leere nipa ìṣesí rẹ.

Ko si si ninu ilana rẹ ki o da ọjọ kan ninu awọn ọjọ inu aye ya sọtọ lati bẹ alaisan wo abi asiko kan ninu awọn asiko. O si tun ṣe lofin fun ijọ rẹ bibẹ awọn alaisan wo ni ọsan ati òru, ati ni awọn asiko ti o ku.

Ilana rẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) nibi mimaa ṣe iwosan pẹlu awọn oògùn àdánidá.

O sọ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) pe: Dajudaju ibà- abi iba ti o le koko- maa nwa lati ibi gbígbóná jainjain jahannama; nitori naa ẹ maa mu un tutu pẹlu omi. O sọ pe: Ti ara ẹni kọọkan yin ba n gbona, ki o yaa wọn omi tutu le e lori fun oru mẹta ni asiko saari.

O si tun jẹ ẹnití o ṣe wípé ti ara rẹ ba n gbona, yio sọ pe ki wọn ba oun gbé awọ ti wọn fi n pọn omi wa, yio waa da a si ori rẹ, ti yíò si tun fi wẹ.

Wọn darukọ ara gbigbona lọdọ rẹ ni asiko kan, ni arakunrin kan ba bu u, o wa sọ pe: Oo gbọdọ bu u; nitori pe o maa n gbọn ẹṣẹ danu gẹgẹ bi ina ṣe maa n gbọn idọti irin danu. Arákùnrin kan wa ba a, o wa sọ pe: Dájúdájú ọmọ iya mi n kigbe inú, ninu ẹgbawa miran: O n ya ìgbẹ́ ọ̀rìn- o wa sọ pe: fun un ni oyin mu, O si maa n po omi pọ mọ ọn, ti yíò sì mu un lai tii fi nkankan sí ẹnu. Awọn ijọ kan ti Mẹdina ko ba lára mu ké gbajari àìsàn inú wíwú. o wa sọ pe: Ẹ ba lọ sí ibiti awọn rakunmi sàká wa, ki ẹ si mu ninu awọn itọ rẹ ati awọn wara rẹ, wọn sì ṣe bẹẹ, wọn si gbádùn. Al-Jawaa: Àìsàn kan ni ninu awọn aisan ikun. Alis'tis'kọọ'u ni: Àìsàn kan ti o maa n fa ki ikun o wu sita.

Nigba ti wọn ṣá a ni ọgbẹ ni ojú ogun Uhud, Faatimah mu egige ẹni kan, o wa jo o titi ti o fi di eeru, o wa fi i si oju ọgbẹ naa, ni ẹjẹ ba da.

O si tun gbe dokita kan dide lọ si ọdọ Ubayy ọmọ kah'b, o si ge iṣan rẹ kan, o si fi iná tẹ ẹ (kí ẹjẹ rẹ le baa da).

O sọ pe: Ìwòsàn nbẹ nibi nnkan mẹta kan: Mimaa mu oyin, ati mimaa dego, ati mimaa fi ina jora. Mo si kọ fun awọn ijọ mi kuro nibi mimaa fi ina jo ara (fún ìwòsàn). O sọ pe: atipe mio nífẹ̀ẹ́ sí kí n máa fi iná jora lati fi ṣe iwosan.

itọka kan ni o jẹ lọ sibi lilọ ṣiṣe àmúlò rẹ lara titi ti laluri o fi pepe lọ si i latari nkan ti n bẹ nibi lilo rẹ nibi kikanju wa ìrora ti ó le.

O si tun dego (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ti o si fun ẹniti o n ba awọn eeyan dego ni owo ọya rẹ. O sọ pe: Nnkan ti o loore ti ẹ le maa ṣe oogun iwosan pẹlu rẹ naa ni didego (hijaamah) o dego si ori rẹ l'ẹniti o wa nínú aṣọ áràmí fun ori fifọ. o si tun dego sibi ibadi rẹ latari koko (ọgbẹ) ti o wa nibẹ.
o si tun jẹ ẹnití maa n dego ni ẹẹmẹta: Ẹyọkan si ibi oke ẹyin rẹ (laarin ejika mejeeji), meji sibi iṣan ẹgbẹ ọrun méjèèjì.
o si dego sibi oke ẹyin rẹ (laarin ejika mejeeji) ni ẹẹmẹta nigba ti o jẹ ninu ẹran ti wọn fi májèlé si, o si tun pa awọn saabe rẹ laṣẹ pẹlu didego (hijaamah)
ẹnikankan o si nii kigbe ìrora ọgbẹ kan ni ori rẹ lọ si ọdọ rẹ ayaafi ki o sọ fun un pe: lọ dego. ẹnikankan o si nii ke ìrora ọgbẹ kan ni ẹsẹ rẹ mejeeji lọ si ọdọ rẹ ayaafi ki o sọ fun un pe: le laali o wa ninu sunanut-tirmidhiy, lati ọdọ salma', iya Raafih, ọmọ ọdọ anabi (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) o sọ pe: O jẹ ẹnití o ṣe wipe ọgbẹ kan o nii mu un, ègún kan o si nii gun un ayafi ki o fi laali si i. O sọ pe: Ìwòsàn àrùn ‘irqun nasā ni ọ̀rá alawẹ idi ẹran (wọn yíò yọ ọ, wọn yíò sì pin in si ọna mẹta), wọn o maa mu ipin kan ninu rẹ ni ojoojumọ lai tii jẹ nkankan.
Ir'kun-nasaa ni: Ọgbẹ kan ti o maa n bẹrẹ lati ibi ti eegun meji ti pade papọ nibi ibadi, ti yíò sì sọkalẹ wa lati ọwọ ẹyin sibi itan.
O sọ nipa iwosan àìrí ìgbẹ́ yà, ati bi bukaata rẹ si nkan ti yio jẹ ki ìgbẹ́ rẹ o maa jáde pẹ̀lú irọrun: O di ọwọ yin lati maa lo eso sanaa ati sanuut (oyin); nítorí pé iwosan n bẹ nibẹ fun gbogbo aisan pátápátá ayafi saam, oun naa ni iku. O sọ pe: Èyí tí o ni oore julọ ninu awọn tìróò yin naa ni ithmid: O maa n mu ojú la kedere, o si maa n jẹ ki irun o wu.
Al-Ith'mid: Oun ni tiroo dudu
O sọ pe: Ẹni tí o ba ji jẹ eso dabinu meje ninu dabinu aaliya ni afẹmọjumọ, iwọ kankan abi asasi kan o le ni í lára ní ọjọ́ naa. O sọ pe: Ẹ ma fi tipatipa fun awọn alaisan yin ni ounjẹ ati mimu; nítorí pé Ọlọhun yio fun wọn ni ounjẹ, yio si tun fun wọn ni mímú. Anabi kọ fún Suhaybu kuro nibi dabinu, o si tun kọ jíjẹ rẹ fún un nigbati o jẹ ẹnití àpólò (àìsàn oju pipọn) mu. Ko si kọ fun un nibi awọn eso dabinu ti o kere. O si tun kọ fun Aliy kuro nibi jíjẹ eso dabinu tutu nigba ti apolo (àìsàn oju pipọn) mu un. O sọ pe: Ti eṣinṣin ba ko sinu igba ẹnikẹni ninu yin, kí ẹ yaa tẹ ẹ ri sinu rẹ; nítorí pé aisan wa lara apa kan iyẹ rẹ, ti iwosan si wa ni apa keji. O sọ pe: At-talbiinatu jẹ nkan ti máa n fun ọkan alaisan ni isinmi, o si maa n mu apa kan ibanujẹ rẹ lọ.
At-talbiinatu ni ọbẹ̀ (nkan mímú) kan ti wọn ṣe jáde latara ọkà bálì ti a ti sọ di lúbúlúbú pẹlu eeta rẹ.
O sọ pe: Habbatus-saudaa di ọwọ yin; nitori pé iwosan n bẹ nibẹ fun gbogbo aisan ayafi iku. O sọ pe: Sá fun ẹniti o dẹtẹ gẹgẹ bi o ṣe maa n sa fun kìnnìún. O sọ pe: Ẹni tí ràkúnmí rẹ n ṣe àìsàn ko gbọdọ ko o papọ mọ ti ẹni ti ràkúnmí ti ẹ ni àlàáfíà Arakunrin adẹtẹ kan nbẹ ninu awọn ikọ thaqiif, ni anabi (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) wa ranṣẹ sí i pe: Pada, a ti ba ọ gbe àdéhùn (baeha).
ìlànà rẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) nibi ṣiṣe iwosan pẹlu awọn oogun iwosan ti Ọlọhun:
O maa n wa iṣọ kuro lọdọ alijannu ati kuro nibi ojukoju awọn eeyan, o si pa aṣẹ pẹlu imaa ṣe rukiya latara ojukoju. O sọ pe: Ojúkójú, ododo ni, ka ni pe nkankan n bẹ ti o maa n ṣaaju kadara ni, ojukoju o ba ṣaaju rẹ, ti wọn ba béèrè fún ki ẹnikẹni ninu yin o wẹ, ki o yaa wẹ. O ri arabinrin kan ti ami dudu kan n bẹ ni oju rẹ, o wa sọ pe: ẹ wa ẹni tí yoo ke rukiya fun un; nítorí pé dajudaju ojukoju ti wa lara rẹ.
As-saf'hah ni: Ojúkójú lati ọdọ awọn alijannu.
O tun sọ fun apa kan ninu awọn saabe rẹ nigba ti o ṣe rukiya fun ẹniti nnkan olóró ta pẹlu kike faatiah, ti o si gbadun, pe: kini o mu ọ mọ wipe rukiya ni. Arákùnrin kan waa ba a, o wa sọ pe: Àkekèé kan ta mi ni alẹ ana, o wa sọ pe: Ka ni pe o sọ ni igba ti o di irọlẹ ana pe: "Auuzu bi kalimatil Laahit taammaati min sharri maa halak", ko nii ni ọ lara.
Ìlànà rẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) nipa iwosan ti o rọrun, ti o ṣe anfaani, ti o jẹ oníbejì.
O jẹ ẹnití o ṣe wipe ti ọmọnìyàn ba kigbe inira tabi ti o ba ni ọgbẹ kan, yíò gbe ika ifabẹla rẹ le ori ilẹ, lẹyin naa ni yíò gbe e soke, yíò wa sọ pe: “Bismillāhi turbatu ardinā, bi riikọti ba‘dinā yushfā sakiimunā, bi izni Rọbbinā”. Ẹnìkan ninu awọn saabe rẹ ke gbajare inira kan lọ si ọdọ rẹ, o wa sọ fun un pe: Gbe ọwọ rẹ lori ibi ti n ro ọ ni ara rẹ, ki o si sọ lẹẹmeje pe: “Auūzu bi ‘izzati Ilāhi wa qudratihi min sharri máa ajidu wa ’uhāzir”. O si maa n wa iṣọ fun apa kan awọn araale rẹ, o maa n fi ọwọ ọtun rẹ pa a lara, ti yoo si maa sọ pe: “Allahummo robban nās az'hibil bah's, wash'fi antash shāfi, laa shifāha illā shifāhuka, shifāhan laa yugādiru saqoman”. O jẹ ẹniti o maa n sọ ti o ba ti wọle tọ alaisan pe: "Laa bah'sa tọhūrun ìn shā allāhu”.
O pari pẹ̀lú ọpẹ fún Ọlọhun.

Ilana Muhammad – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi awọn ijọsin rẹ ati awọn ibaṣepọ rẹ ati awọn iwa rẹ
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi imọra ati bibiya bukaata
Ilana rẹ nibi aluwala ṣiṣe:
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi pipa khuffi rẹ mejeeji
Ilana rẹ nibi aluwaala eleepẹ
Ilana rẹ nibi irun
Ilana rẹ nibi bibẹrẹ irun ati kika nkan
Ilana-iṣe rẹ- ki Ọlọhun ṣe ikẹ ati igẹ rẹ fun un- nipa bi a ṣe nkirun
Itọnisọna ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi awọn nkan ti o maa nṣe lori irun
Itọnisọna ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - nibi awọn iṣesi rẹ nigba ti o ba kirun tan :
Itọnisọna ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - nibi awọn iṣẹ ifinufindọṣe ati didide loru.
Itọnisọna ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi irun Jimoh.
Itọnisọna ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - nibi irun yidi mejeeji ( Eidul fitr' ati Eidul-Ad'ha).
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nigbati ọsan ba di oru
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi wiwa ojo
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi irun oju-ogun
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi ipalẹ oku mọ
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi irun kiki si oku lara
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi sisin oku ati awọn nkan ti o sorọ mọ ọn
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – ni itẹ ati ibanikẹdun
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi zakah ati saara
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi zakah
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi zakaatul fitri
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi aawẹ gbigba
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi aawẹ ramadan
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – ninu aawẹ afinufindọ gba
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - nibi ṣiṣe atipo ni ile Ọlọhun
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi Haj ati Umurah
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi Umurah
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi Haj
Ilana iṣesi rẹ - ki Ọlọhun ṣe ikẹ rẹ fun un - labala ẹran adaaya ati ẹran ileya ati ẹran ikomọjade
Ilana iṣesi rẹ - ki Ọlọhun ṣe ikẹ rẹ fun un - labala ẹran adaaya (ẹran iṣẹbun fun Ọlọhun nibi iṣẹ hajji)
Ilana-ọnaamọ rẹ - ki Ọlọhun ṣe ikẹ ati igẹ Rẹ fun un - labala ẹran ileya
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi pipa ẹran suna ọmọ
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi tita rẹ ati rira rẹ ati ibaṣe pọ rẹ
Ilana rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – nibi igbeyawo ti ibara-ẹni-lopọ
Ìlànà rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- nibi oúnjẹ ati nkan mímu
Ìlànà rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi oúnjẹ:
Ìlànà rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi nkan-mimu:
Ìlànà rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi ipepe si oju ọna Ọlọhun
Ilana rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi ifunni ni ifayabalẹ ati iṣe àtúnṣe ati bíbá àwọn ojiṣẹ lo pọ
Ìlànà rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi pípe àwọn ọba, ati riran àwọn iranṣẹ ati ìwé si wọn
Ìlànà rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi asikiri
Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi asikiri ni àárọ̀ ati irọlẹ
Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Olohun maa ba a- nibi asikiri nígbà tí ó ba jáde kúrò nílé àti nígbà tí ó ba wọlé:
Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- nibi asikiri ti o ba fẹ wọ mọṣalaaṣi ati ti o ba fẹ jáde kúrò nibẹ
Ìlànà rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi asikiri rírí iletesu
Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- nibi asikiri nígbà tí o ba sin ati nígbà tí o ba yan:
Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi nkan ti o maa n sọ ti o ba ri ẹni tí àdánwò ba kan:
Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi irun pipe ati àwọn asikiri rẹ
Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi asikiri ninu oṣù zul-hijjat
Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi kika Kuraani
Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- níbi khutubah rẹ
Ìlànà rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- nibi oorun-sisun ati jiji ati àwọn àlá
Ìlànàa rẹ̀, kí ìkẹ́ Ọlọ́hun àti ọlàa rẹ̀ kó máa bá a, níbi àdámọ́, ìmúra, ìríṣí, àti ẹ̀ṣọ́.

"Ìlànà re, ki ìkẹ́ Ọlọ́hun àti ọlà Rẹ̀ máa ba a- níbi ìkíni àti ìgba ìyọ̀ǹda. "
"Ìlànà rẹ̀, kí ìkẹ́ Ọlọ́hun àti ọlá Rẹ máa bá a- níbi ọ̀rọ̀ àti ìdákẹ́, àti níbi sisọ ọrọ, àti ìṣẹ̀ṣà àwọn gbólóhùn àti orúkọ "
Ilana rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- nibi irin rẹ ati ìjókòó rẹ
Ìlànà rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - ati ilana awọn saabe rẹ ni iforikanlẹ ọpẹ nígbà tí oore ọtun ti maa n dun ni ninu ba ṣẹlẹ tabi ìyà kan ba kúrò.
Ìlànà rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - nibi wiwa ọna àbáyọ sí ibanujẹ ati ifooro.
Ìlànà rẹ - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - nibi irin-ajo.
Ìlànà rẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) nipa ìtọ́jú aláìsàn, ati lilo oogun, ati mimaa bẹ alaisan wo.